**NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA**

**SCHOOL OF ARTS AND SOCIAL SCIENCES**

**COURSE CODE: YOR 341**

**COURSE TITLE: PHONOLOGY OF YORUBA II**

# COURSE GUIDE

**YOR 341**

**PHONOLOGY OF YORUBA II**


| | |
|---|---|
| **COURSE TEAM** | **DR. CLEMENT ODOJE (COURSE DEVELOPER/WRITER) UNIVERSITY OF BADAN** |
| | **To be Determined (Course Editor)** |
| | **To be determined (Programme Leader)** |
| | **To be determined (Course Coordinator)** |

**Akòónú**

Ìfáárà

Èrèdí ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Àfojúsùn ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí léréfèé

Àwọn èròjà fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ìpín ẹ̀kọ́ kọ̀ọ̀kan

Ìwé lílò àti àtòjọ ìwé tí a lò

Ìgbéléwọ̀n

Fífún ìṣẹ́ àmúrelé ní máàkì

Ìdánrawò òpin ẹ̀kọ́ àti máàkì

Ìlànà mímáàkì iṣẹ́

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ní sókí

Ọ̀nà àágbà sàmúlò ìwé yìí dé góngó

Ìranniọ́wọ́/ kíkọ́ni/

Ìsọniṣókí

Commented [O.J1]: Èròǹgbà àti Àfojúsùn ni àbá Ọ̀jọ̀gbọ́n Ọlátẹ́jú

Commented [O.J2]: Ọnà àgbàṣàmúlò ìwé yìí

**ÌFÁÁRÀ**

A ti gbé díẹ̀ wò nínú àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì nínú LIY 214. Lára àwọn ohun tí a wò ni àrànmọ́, ìpajẹ/ìparójẹ, ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ìtẹ̀síwájú ìjíròrò wa nínú 241 ni LIY 341 yìí jẹ́. Àwọn kókó tí a wò ní LIY 214 tí wọ́n tún jẹyọ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí jẹ́ àwàjinlẹ̀. A kàn wò wọ́n ní eréfèé nínú LIY 214, àwàdégbò ni a ṣe

àwọn kókó bẹ́ẹ̀ níbí. Nítorí náà, ó ṣe é ṣẹ kí o bá àwọn àkórí kọ̀ọ̀kan tí a ti sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ nínú LIY 214 níbí kí àpẹẹrẹ tí a sì lò jọra; àmọ́ ìyàtọ̀ ìbẹ̀ ní pé àlàyé èyí kún ju ti tẹ̀lẹ̀ lọ. Lára àwọn kókó ti a ó wò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni àǹkóò fáwẹ̀lì, ìyọ́pọ̀ fáwẹ̀lì, ìsọdi-ìránmú, ìsọdàìránmú, abbl. Èrò tiwa ni pé kí o ka ẹ̀kọ́ yìí ní àkàgbádùn, àmọ́, jù bẹ́ẹ̀ lọ, kí ìwọ náà lè mú ẹ̀kọ́ inú ìwé yìí fi kọ́ ẹlòmíràn. Kí èyí lè wá sí ìmúṣẹ, o gbọdọ̀ farabalẹ̀ ka àwọn ẹ̀kọ́ inú ìwé yìí kí o sì ṣe amúlò àwọn ẹ̀kọ́ tí o bá rí fà jáde gẹ́gẹ́ bí ó bá ti yẹ.

A ó pẹ̀kẹ́ lu ohun tí àwọn onímọ̀ ìsaájú ti sọ lórí àwọn kókó ọ̀rọ̀ tí a fẹ́ gbé yẹ̀wò à ó sì ṣe àwílé tiwa náà. Ìgbà mìíràn wa tí àríyànjiyàn yóò wà lórí kòkò ìjírọ̀rọ̀ kan, bí ọ̀rọ̀ bá rí báyìí, a ó kan sọ ohun tí àwọn onímọ̀ sọ ni, nítorí pé, a ó fẹ́ kí ó jẹ́ pé o yan èyí tí ó bá wù ọ́ nínú àríyànjiyàn náà.

Ohun tí ó dájú ni pé inú èdè Yorùbá ni a ó ti mú àwọn àpẹẹrẹ wa, ìpèdè ojóojúmọ́ ni wọn yóò sì jẹ́. Àmọ́ sá o, ó ṣe é ṣe kí á tún wọnú ẹ̀ka èdè lọ láti le fìdí ẹ̀rí kókó ọ̀rọ̀ wa múlẹ̀. A ní ìrètí pé ìwọ́ náà yóò wa ọ̀pọ̀lọpọ̀ àpẹẹrẹ fi kín ọ̀rọ̀ wa lẹ́hìn tàbí fi takò ó. Kò sí ohun tí ó burú bí o bá ní ìdí láti fi ojú mìíràn wo àlàyé wa. O kan gbọdọ̀ gbé e kalẹ̀ lọ́nà tó mọ́gbọ́n dání kí o sì fi ọ̀pọ̀ àpẹẹrẹ gbe àlàyé rẹ lẹ́sẹ̀.

## ÈRÈDÍ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Àwọn èrèdí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a là kalẹ̀ sí ìsàlẹ̀ yìí:

- Sàlàyé àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì tí ó wà ní èdè Yorùbá
- Tọ́kasí àwọn sàkání tí àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì yìí ti jẹyọ
- Ní èrò tí ó dájú lórí àwọn ìgbésẹ̀ tí ó ní àlàyé ju ẹyọ kan lọ

## ÀFOJÚSÙN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Lópin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, àwọn wọ̀yí ni àfojúsùn wa: Akẹ́kọ̀ọ́ yóò le:

**Commented [O.J3]:** ṣe
**Commented [O.J4]:** pàdé níbí
**Commented [O.J5]:** a lò sì
**Commented [O.J6]:** ìsọdìránmú
**Commented [O.J7]:** Fi "mẹ́nu ba" dípò
**Commented [O.J8]:** náà ni
**Commented [O.J9]:** yìí. Ó gbọ́dọ̀ lè:
**Commented [O.J10]:** Ṣàlàyé
**Commented [O.J11]:** wọnyí

- Fi àpẹẹrẹ ṣàlàyé ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì
- ṣe àgbékalẹ̀ àǹkóò fáwẹ́lì èdè Yorùbá
- Ṣàfihàn ìgbésẹ̀ ìsọdìránmú àti ìsọdàìránmú

## JÍJẸ ÀǸFÀÀNÍ ÌWÉ YÌÍ

Láti jẹ àǹfààní ìwé yìí ni ọ̀nà tí yóó ràn ọ́ lọ́wọ́, kí o lè kógo já lẹ́nu ẹ̀kọ́ rẹ, o ní láti gbé àwọn ìgbésẹ̀ kan. Ohun àkọ́kọ́ tí ó yẹ kí o mọ̀ ni pé, o ní láti farabalẹ̀ ka ìwé yìí. Àwọn ìbéèrè wà ní ìbẹ̀rẹ̀ ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan. Kìí ṣe dandan kí o lè dáhùn àwọn ìbéèrè náà. Kìí sì ṣe ìsòro bí o kò bá mọ̀ èsì sí ọ̀kankan àwọn ìbéèrè yẹn. A tò wọ́n jọ síbẹ̀ láti jẹ́ àfojúsùn ohun tí ó yẹ kí o lè ṣe lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ni. Nítorí náà, ìpòǹgbẹ́ fún ìmọ̀ ni wọ́n wà fún. Ṣùgbọ́n, bí o kò bá lè dáhùn àwọn ìbéèrè náà, lẹ́yìn tí o ti ka ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà tán, ìyẹn túmọ̀ sí pé, ohun tí o kà, kò yé ọ. Nítorí náà, o nílò láti tún un ka tàbí wá ìrànlọ́wọ́ lọ sọ́dọ̀ àwọn onímọ̀. Àmọ́, ohun kan dá mi lójú pé ọ̀nà tí a gbà ṣàlàyé àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí jẹ́ èyí tí ó rọrùn púpọ̀ láti jẹ́ kí àwọn kókó náà yé ènìyàn dáadáa. A ní in lọ́kàn pé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí yóó gbà ọ́ ni ọ̀sẹ̀ mẹ́ẹ̀ẹ́dógún láti kọ́ gbogbo ẹ̀kọ́ inú rẹ̀ tán, lẹ́yìn náà ni wà á wá ṣe ìdánwò. A tún ti ṣe àlàkalẹ̀ bí wà á ṣe ka ìwé yìí lọ́nà tí yóó fi ràn ọ́ lọ́wọ́ láti ṣe àmúlò àkókò rẹ dáadáa tó bẹ́ẹ̀ tí ìṣẹ́ náà yóó ṣe wọ̀ ọ́ ní akínyẹmi ara rẹ.

Commented [O.J12]: Kì í

## ÈRÒJÀ FÚN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Àwọn wọ̀nyí ni èròjà ìdánilẹ́kọ̀ọ́:

- Àtọ́nisọ́nà Ẹ̀kọ́
- Ẹka Ẹ̀kọ́
- Ìwé Àmúlò
- Ìgbéléwọ̀n
- Àlàkalẹ̀ Ìṣẹ́
- Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́

Móòdù mẹ́tà (3) àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́ mẹ́wàá (10) ni ó wà. Móòdù àkọ́kọ́ dá lórí àtúngbéyẹ̀wò àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì tí a ti yẹ̀wò ni LIY 214. Èyí ni yóó ṣe ìpìlẹ̀ fún àwọn ìjíròrò wa lórí àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì ní èdè Yorùbá yòókù. Nípasẹ̀ Móòdù yìí, yóó jẹ́ kí ó rọ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti olùkàwé yìí lọ́rùn láti mú un wá sí ìrántí wọn àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì tí a ti gbé yẹ̀wò séyìn. Yóó sì ràn wọ́n lọ́wọ́ láti máa ba wa lọ nígba tí a bá mú ìmọ̀ ọ̀tun fún ìjíròrò. Nínú móòdù kejì ni a ó ti wo àǹkóò fáwẹ́lì àti ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì; ní ìgbà tí a wo ìró àránmúpè, ìsọdìránmú àti ìsọdàìránmú ní móòdù kẹta.

Commented [O.J13]: Ṣé Móòdù ni àbí Módù?

Commented [O.J14]: Móòdù

Commented [O.J15]: yóò

Commented [O.J16]: Ó tún máa

Commented [O.J17]: ìjíròrò jáde

**Móòdù Àkọ̀kọ̀: Àbùdá Afọ̀ Geere**

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkínní: ìpajẹ/ìpàrójẹ

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkejì: àrànmọ́

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkẹta: Ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkẹrin: Ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn

**Móòdù Kejì: Ìjẹyọ, Ànkóò àti Ìyọ́pọ̀ Fáwẹ́lì**

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkínní: Àǹkóò fáwẹ́lì

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkejì: ìyàtọ̀ àǹkóò fáwẹ́lì àti ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkẹta: ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì

**Móòdù Kẹta: Ìránmú àti Ọ̀rọ̀ Àyálò**

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkínní: ìró aránmúpè

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkejì: ìsọdìránmú

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkẹta: ìsọdàìránmú

**ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ ÀTI ÌWÉ TÍ A ṢÀMÚLÒ**

Yàtọ̀ sí ìwé yìí, ìbá dára bí ó bá le nawọ́ mú àwọn ìwé mìíràn fún kíkà. Àwọn ìwé tí a ó là kalẹ̀ ní ìsàlẹ̀ yìí yóó ràn ọ́ lọ́wọ́ nígbà tí o bá fẹ́ ṣe ìṣẹ́ àmúrelé/aṣetiléwá rẹ


Ayo Bamgboṣe (1990) *Fonọ̀lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ibadan. Uiversity Press Linited.

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá 1: Fonẹ́tíìkì àti Fonọ̀lọ́jì*. Ìbàdàn. Universal Akada Book Nigeria Limited

Francis Oyebade (2001) Ìgbésẹ̀ àti Ìlànà Fonọ̀lọ̀jì Èdè Yorùbá nínú *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá-Èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà* tí Bádé Àjàyí jẹ́ olóòtú fún


**ÌGBÉLÉWỌ̀N**

Ìgbéléwọ̀n méjì ni ó wà fún iṣẹ́ yìí, ìṣẹ́ àṣetiléwá àti ìdánwò, àpapọ̀ méjéèjì yóó jẹ́ ọgọ́nrùn-ún. Àpapọ̀ máàkì fún iṣẹ́ àmúrelé yóó jẹ́ ogójì (40%). Máàkì ìdánwò á sì jẹ́ ọgọ́ta (60%). Ìrètí wa ni pé ìmọ̀ rẹ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ àti yege rẹ nínú ìgbéléwọ̀n yìí.

**Commented [O.J18]:** àṣetiléwá

**Commented [O.J19]:** ọgọ́rùn-ún

**Commented [O.J20]:** àtiyege

## MÓÒDÙ ÀKỌ́KỌ́

## ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ ÌKÍNNÍ

## ÌPAJẸ/ÌPÀRÓJẸ

### 1.0 Ìfáárà

Fonọ́lọ́jì gẹ́gẹ́ bí ẹ̀kọ́ ètò ààtò ìró àti bí àwọn ìró èdè ọmọnìyàn ṣe ń yan ara wọn nígbà tí a bá ń fọ̀ ṣe pàtàkì gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára ìpele ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ẹ̀dá èdè. Àwọn ìró èdè kìí kàn ṣàdédé jẹ́ títòpọ̀ láti gbé wúnrẹ̀n kan jáde, bí kò ṣe pé wọ́n ní ààtò bí wọ́n ṣe máa ń yanra àti ṣiṣẹ́ pọ̀. Nítorí náà, ètò, ìlànà àti òté tí ó de bí àwọn ìró èdè yìí ṣe ń yanra wọn ni ó jẹ wá lógún nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.

Ìlànà àti òté tí a ó kọ́kọ́ gbé yẹ̀wò ni ìpajẹ tí àwọn onímọ̀ kan tún pè ní ìpàrójẹ. Gẹ́gẹ́ bí elédè, bí a bá ń safọ̀ geere, àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì kan máa ń wáyé, lára wọn ni ìpajẹ. A ó wo àwọn ìró tí a máa ń pajẹ nínú èdè Yorùbá, òfin tí ó de pípa ìró jẹ, sàkání/agbègbè tí a ti máa ń pa ìró jẹ.

### 2.0 Èròngbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó

a. ṣàlàyé ìró tí a lè pajẹ
b. ṣàlàyé òfin tí ó de pípa ìró jẹ
d. ṣàfihàn ìhun tí ìpajẹ ti lè wáyé

#### 2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ẹ̀kọ́

a. Ṣe àlàyé àwọn ìró tí a lè pajẹ
b. Ṣe àlàyé àwọn òfin tí ó de pípa ìró jẹ
d. Ṣe àfihàn ìhun tí pípa ìró jẹ ti lè wáyé

**Commented [O.J21]:** ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè

**Commented [O.J22]:** Àtúnwí gbólóhùn ìṣáájú ni, ẹ lè yọ́ kúrò

**Commented [O.J23]:** ṣafọ̀

**Commented [O.J24]:** ìró jẹ, àti

**Commented [O.J25]:** Ṣé **yóò** ni àbí **yóò**? Mo mọ **yó, ó, óò**, ṣùgbọ́n n kò mọ̀ bóyá **yóò** nàà tún wà.

## 3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 3.1 Ìpajẹ

Ìpajẹ jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ìlànà àfọ̀ geere nínú èdè Yorùbá. Oyẹbádé (2001) ṣàlàyé pé bí a bá fẹ́ẹ́ mọ ìyàtọ̀ láàrin ọmọ bíbí ilẹ̀ Yorùbá àti àjèjì tí ń kọ́ èdè Yorùbá, nínú àfọ̀ geere ni a ó ti mọ̀. Ẹ jẹ́ kí a wo àwọn ìpèdè ìsàlẹ̀ yìí

i. Kín ni orúkọ rẹ?

ii. Kín loókọ rẹ?

Èwo nínú àwọn ìpèdè òkè yìí ni ti àjèjì? Èwo ni tí onílé o? A ó ṣe àkíyèsí pé ìpèdè méjéèjì ni ojúlówó èdè Yorùbá ṣùgbọ́n ọ̀kan jẹ́ ohun tí gbogbo àwọn tí wọ́n bá gbọ́ tàbí kọ́ èdè Yorùbá lè ṣọ; ìyẹn ìpèdè (i). Àmọ́, ìpèdè (ii) jẹ́ ti àwọn elédè. Kín ni ó wa ya ìpèdè (i) sí (ii)? A ó rí pé ọ̀pọ̀ ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì ti ó ti bá (ii). Ọ̀kan pàtàkì lára wọn ni ìpàjẹ.

Commented [O.J26]: ti

### 3.2 Kín ni Ìpajẹ?

Gẹ́gẹ́ bí i àlàyé Oyèbádé (2001:72) nígbà tí ìró bá sọ nù nínú ọ̀rọ̀, àpólà tàbí gbólóhùn bí a ti hun ìsọ ni àwọn onímọ̀ fonọ́lọ́jì máa ń sọ pé ìpàrójẹ ti wáyé. Owólabí (2013:172) pè é ní ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì kan, tí fifo àwọn ìró tàbí sísọ àwọn ìró nù nígbà tí a bá ń safọ̀ geere. Fáwẹ́lì, kọ́nsónáǹtì, ohùn àti àpapọ̀ wọn ni a lè pa jẹ.

Commented [O.J27]: Yọ èyí kúrò

Commented [O.J28]: sọnù

Commented [O.J29]: fífo

#### 3.2.1 Pípa Ìró Kọ́nsónáǹtì jẹ

Bángbóṣe (1990:71) ṣàlàyé pé ọ̀nà méjì ni a lè gba pa ìró kọ́nsónáǹtì jẹ. Ọ̀nà kìíní ni kí a pa kọ́nsónáǹtì jẹ kí a sì fi fáwẹ́lì sílẹ̀ bí ó ṣe wà. Wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí.

ahọ́n → aọ́n

tìrẹ → tìẹ

Ọ̀nà kejì ni kí á pa kọ́nsónáǹtì jẹ, lẹ́hìn náà kí a wá ṣe àrànmọ́ fún àwọn fáwẹ̀lì tó bá yàtọ̀; àpẹẹrẹ ni

Commented [O.J30]: fáwẹ́lì méjì wá fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ lẹ́yìn ipajẹ tí àwọn fáwẹ̀lì méjì náà bá yàtọ̀

| | | |
|---|---|---|
| òrìsà → | *[1]òìsà | → òòsà |
| agogo → | *aogo | → aago |
| ajá rẹ → | ajá ẹ | → ajẹ́ẹ |

Oyèbádé (2001) sọ pé Oyèláràn (1971) ní ìró kọ́nsónáǹtì aréhọ́n *r*, afàfàsefètèpè *w*, àti afàjàpè *y* ni a máa ń pa jẹ jù lédè Yorùbá. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Owólabí (2013:172) ṣe àfikún sí èrò Oyèláràn pé ó sòrò láti sọ ní pàtó iye àti irú àwọn kọ́nsónáǹtì tí a lè pa jẹ nínú ọ̀rọ̀. Ó ṣàlàyé pé, ó dàbí ẹni pé bí a bá pa ìkọ̀ọ̀kan nínú àwọn kọ́nsónáǹtì wọ̀nyí jẹ: *r*, *w*, *y*, *h*, *l* àti *k* nínú ọ̀rọ̀, a lè mú ìsọ aṣeégbà jáde. Ó fi kún un pé ìró kọ́nsónáǹtì *r* ni a sábà máa ń pajẹ jùlọ. Oyèbádé (2001) ṣe àfikún àwọn kọ́nsónáǹtì tí a lè pa jẹ lédè Yorùbá. Ó tilẹ̀ ní pé, ó fẹ́rẹ̀ dàbí ẹni pé gbogbo kọ́nsónáǹtì ni a lè pa jẹ. Àwọn kọ́nsónáǹtì tí ó ṣe àpẹẹrẹ rẹ̀ tí ó yàtọ̀ sí ti Oyèláràn àti ti Owólabí ni: *d*, *s*, *g*, *p*, abbl. Àpẹẹrẹ ni

Commented [O.J31]: Ǹjẹ́ kò ní yẹ kí a yẹra fún dídárúkọ àwọn onímọ̀ nínú ìpèsè èròjà ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ lè máa fi ọkàn bá ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà lọ, níwọn bí kì í ti í ṣe àríyànjiyàn ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà forí sọ

**Ìpajẹ *r***

kúrò → kúò
dára → dáa
koríko → koóko
orúkọ → oókọ
èkùrọ́ → èkùọ́

**Ìpajẹ *y***

Àjàyí → Àjàí
láyé → láé
gbáríyẹ̀ → gbáríẹ̀

**Ìpajẹ *w***

**Ìpajẹ *l***

[1] Àmì ìràwọ̀ yìí fi hàn pé ìpèdè bẹ́ẹ̀ jẹ́ àìṣeégbà "kò ṣeé gbà" já gaara ju èyí lọ

báwo → bá o → bóo
kéwú → kéú
ọmọlúwàbí → ọmọlúàbí

Méjìlélógún → méjìélógún
tilẹ̀ → tiẹ̀

**Ìpajẹ *h***

gbohùngbohún → gboùngboùn
kẹ́hìndé → kẹ́ìndé

**Ìpajẹ *k***

| | |
|---|---|
| kò | → ò |
| ọlákìítán | → ọláìítán |
| àkíké | → àíké → àáké |
| èkíkánná | → èíkánná → èékánná |
| ọ̀kánkán | → ọ̀ánkán → ọ̀ọ́kán |

**Ìpajẹ *d***

Àdídùn → àídùn → àádùn
ọ̀dẹ̀dẹ̀ → ọ̀ẹ̀dẹ̀ →ọ̀ọ̀dẹ̀
èdúdú → èúdú → èédú

**Ìpajẹ *s***

esinsin → einsin →eesin

**Ìpajẹ *g***

agogo → aogo → aago
egungun → eungun →eegun
egúngún → eúngún → eegún

**Ìpajẹ *p***

èpìpo → èìpo → èèpo

A ó ṣàkíyèsí pé Oyèláràn (1971), Bangbóṣé (1990) àti Owólabí (2013) kò fún wa ní òfin kan pàtó tí ó de pípa ìró kọ́nsónàǹtì jẹ. Àmọ́ Akinlabí (1990) gbé òfin méjì kalẹ̀ fún pípa ìró Kọ́nsónáǹtì *r* jẹ. Òfin náà nì yìí:

i. Pa *r* jẹ bí ó bá sú yọ láàrin fáwẹ́lì méjì tí ó jọ ara wọn;
ii. Pa *r* jẹ láàárín fáwẹ́lì méjì bí ọ̀kan nínú wọn bá jẹ́ àhánupè

Àpẹẹrẹ ni:

Commented [O.J32]: Ǹjẹ́ kò ní yẹ kí a yẹra fún dídárúkọ àwọn onímọ̀ nínú ìpèsè èròjà ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ lè máa fi ọkàn bá ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà lọ, níwọ̀n bí kì í ti í ṣe àríyànjiyàn ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà forí sọ

| (i) | | | (ii) | | |
|---|---|---|---|---|---|
| kúrò | → | kúò | dára | → | dáa |
| koríko | → | kóoko | fẹ́rẹ̀ | → | fẹ́ẹ̀ |
| òrìsà | → | òòsà | oríkì | → | oókì |
| àdúrà | → | adúà | ẹ̀rẹ̀kẹ́ | → | ẹ̀ẹ̀kẹ́ |

Àmọ́ sá o, àwọn àyàfi kan wà gẹ́gẹ́ bí èrò Akinlabí, ọ̀kan lára wọn sì ni pé, a kò lè pa *r* jẹ bí ó bá jẹ́ pé òun nìkan ni kọ́nsónáǹtì tí ó wà nínú ọ̀rọ̀ náà:

ara → * aa
ọ̀rọ̀ → *ọ̀ọ̀
ìró → *ìó

àwọn kòbẹ́gbẹ́mu mìíràn ni

ewúrẹ́ → *ewúẹ́
yàrá → * yàá
ọgọ́rin → *ọgọ́in abbl

Ṣé a wá lè sọ pé tórí àwọn kòbẹ́gbẹ́mu yìí kí a da àbá òfin tí Oyelaran gbé kalẹ̀ nù? Èrò Oyèbádé (2001) ni pé, à kò lè da àbá òfin náà nù, ìdí ni pé bí ìpajẹ bá ti kọ́kọ́ wáyé, a kò lè ṣe ìpajẹ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àwọn kòbẹ́gbẹ́mu òkè yìí. Ẹ jẹ́ kí a wo àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

ṣaworo → ṣaoro → *saoo
ewúrẹ́ → eúrẹ́ → * eúẹ́
àwòrò → àòrò → *àòò

Oyebádé fi kún un pé, ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé bakan-méjì ni a fi ń pe *òrúwọ* → *òrúọ* tàbí *òówọ*.

Òfin tí Oyèláràn dá lábàá fún pípa ìró w jẹ ni pé, kí a tó lè pa ìró *w* jẹ fáwẹ́lì tí yóó tẹ̀lé *w* gbọdọ̀ ní àbùbá roboto. Àpẹẹrẹ ni

òwúrọ̀ → òórọ̀
owólàákẹ́ → oólàákẹ́

A ó rí i pé fawẹ́lì *u* àti *o* ni ó tẹ̀lé ìró *w* nínú àpẹẹrẹ òkè yìí, fáwẹ́lì roboto sì ní àwọn méjéèjì, ó sì bá òfin tí Oyèláràn  gbé kalẹ̀ mu. Àmọ́ Oyèbádé (2001) tọ́ka sí àwọn kòbẹ́gbẹ́mu kan, bí àpẹẹrẹ

ìwo → *ìo
iwọ → *iọ
ẹ̀wọ̀n → *ẹ̀ọ̀n

Oyèdádé ní, kì í sí kòbẹ́gbẹ́mu bí fáwẹ́lì tí ó tẹ̀lé *w* bá jẹ́ àhánupè roboto *u*. Ó yẹ kí á tọ́ka rẹ̀, kí á sì dún nu mọ́ ọn pé òfin Oyelaran àti àlàyé Oyèbádé kò mẹ́nu bá ìpajẹ w nínú ọ̀rọ̀ bí i *ọmọlúwàbí* tí ó di *ọmọlúàbí*. Fáwẹ́lì tí ó tẹ̀lé *w* kìí ṣe àhánupè roboto bí kò ṣe àyanupè pẹrẹsẹ. Èyí yàtọ̀ sí èrò àwọn méjéèjì síbẹ̀ àyọrísí rẹ̀ jẹ́ aṣeégbà. Nítorí náà a lè tún òfin yìí rọ pé kí a tó lè pa kọ́nsónáǹtì *w* jẹ, fáwẹ́lì tí ó tẹ̀lé *w* gbọdọ̀ jẹ́ ẹ̀yìn roboto tàbí àyànupè pẹrẹsẹ. Òfin yìí yóò fàyè gba ìpajẹ *w* nínú ọ̀rọ̀ bí *ọmọlúwàbí* → *ọmọlúàbí*.

Òfin tí ó de pípa Kọ́nsónáǹtì *y* jẹ gẹ́gẹ́ bí àlàyé Oyèláràn ni pé, fáwẹ́lì tí ó gbọ́dọ̀ tẹ̀lé e gbọ́dọ̀ jẹ́ fáwẹ́lì iwájú nínú irú ọ̀rọ̀ bí i:

èyíkéyìí → èíkéìí
Àjàyí → Àjàí
adìyẹ → adìẹ
ríyẹrìyẹ → ríẹrìẹ

ìdí tí òfin yìí kò fi ṣiṣẹ́ fún ọ̀rọ̀ bí i:

ẹyẹ → *ẹẹ
ayé → *aé

kò tîì di mímọ̀ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó ṣiṣẹ́ fún ọ̀rọ̀ bí

afẹ̀sọ̀jayé → afẹ̀sọ̀jae

Commented [O.J33]: ì

Commented [O.J34]: é

Òfin tó de pípa kọ́nsónáǹtì alápètúnpè bí i:

ọ̀kánkan → ọ̀ánkan → ọ̀ọ́kan
ògùngùn→ òùngùn → òògùn

ni pé, kọ́nsónáǹtì bẹ́ẹ̀ gbọdọ̀ jẹ yọ láàrin fáwẹ́lì, kí fáwẹ́lì tí ó tẹ̀lé e jẹ àhánupè tàbí kí fáwẹ́lì yẹn àti fáwẹ́lì inú sílèbù tí ó tẹ̀lé e jẹ́ ọ̀kanhun. Bí a bá tẹ̀lé òfin yìí báwo ni a ó ti ṣe àwọn kòbẹ́gbẹ́mu ìsàlẹ̀ yìí sí?

agbègbè → *aègbè → *aàgbè
àtàtà → *ààtà →
àkùkọ → * aùkọ → ààkọ

Àlàyé Oyèbádé (2001) ni pé, ó ṣe é ṣe kí ó jẹ́ pé àwọn kòbẹ́gbẹ́mu òkè wọ̀nyí kan jọ àpètúnpè ni, wọ́n le má jẹ́ àpètúnpè.

Ǹjẹ́ ohun tí Oyèbádé ń sọ ni pè, láti kọ́nsónáǹtì jẹ nínú àwọn ọ̀rọ̀ alápètúnpè, irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ ọ̀rọ̀ ìsẹ̀dá? A jẹ́ pé bí wọ́n bá jẹ́ ọ̀rọ̀ ìpìlẹ̀, a kò ní lè pa kọ́nsónáǹtì ibẹ̀ jẹ gẹ́gẹ́ bí àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí ṣe fi hàn. Èyí ó wù ó jẹ́, a ní láti tún wá àwọn ẹ̀rí máa jẹ́ mi nì só kí a tó lè fi ẹ̀sẹ̀ gbogbo òfin tí wọ́n ti dá lábàá múlẹ̀.

### 3.2.2 Pípa Ìró Fáwẹ́lì jẹ

Lẹ́yìn tí a ti wo ìpajẹ kọ́nsónáǹtì, ohun tí ó bójú mu ni láti wo ìpajẹ fáwẹ́lì náà. Oyèbádé (2001) ni ó fẹ́rẹ̀ẹ́ jẹ́ pé orí ìpajẹ fáwẹ́lì èdè Yorùbá ni àwọn onímọ̀ fonọ́lọ̀jì ti ṣiṣẹ́ jù nítorí àríyànjiyàn dí ìgbésẹ̀ fonọ́lajì náà mú dá ni.
Bamgbóṣé (1965) ṣàlàyé pé bí ba bá so ọ̀rọ̀ méjì pọ̀, bí fáwẹ́lì bá parí ọ̀rọ̀ àkọ́kọ́, tí fáwẹ́lì sì tún bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ kejì, ọ̀kan nínú àwọn fáwẹ́lì yìí yóò di pípajẹ. Bámgbóṣe (1990) ní ọ̀nà méjì ni a lè gba fi pa ìró fáwẹ́lì jẹ. Ọ̀nà àkọ́kọ́ ni kí a pa fáwẹ́lì kan jẹ nínú fáwẹ́lì tó fẹ̀gbẹ́ kẹ̀gbẹ́, àpẹẹrẹ ni:

ra ewé → rewé
ṣe iṣẹ́ → ṣiṣẹ́

**Commented [O.J35]:** láàárin

**Commented [O.J36]:** láti pa kọ́nsónáǹtì jẹ

**Commented [O.J37]:** mìíràn

**Commented [O.J38]:** ní ó /sọ pé

**Commented [O.J39]:** a

fẹ́ owó → fówó
ọmọ ọkùnrin → ọmọkùnrin

ọ̀nà àkọ́kọ́ yìí ni Bámgbóṣe sọ pé ó wọ́pọ̀.

Nítorí náà, Bámgbóṣe gbé òfin ìsàlẹ̀ yìí kalẹ̀ fún pípa fáwẹ́lì jẹ́ ní ílànà àkọ́kọ́ yìí:

**$F_1 + F_2 \rightarrow F_1$**
tàbí
**$F_2$**

Òfin yìí sọ pé àbájáde fáwẹ́lì pípajẹ lè jẹ́ fáwẹ́lì àkọ́kọ́ tàbí fáwẹ́lì ẹ̀kejì. Bí fáwẹ́lì méjéèjì bá jẹ́ irú kan náà, kò ṣẹ̀ṣẹ̀ lílò kí a máa tọ pinpin bóyá fáwẹ́lì kìnní tàbí ìkejì ni a pa jẹ. Nítorí náà nínú àpẹẹrẹ *ọmọ* + *ọkùnrin* → *ọmọkùnrin*, ó dábàá òfin yìí:

ọmọ + ọkùnrin → ọmọkùnrin
1 2 x x 1 3 4

Èyí túmọ̀ sí pé a kàn mú ọ̀kan nínú *ọ* tí ó parí *ọmọ* àti *ọ* tí ó bẹ̀rẹ̀ *ọkunrin* ni.

Ọ̀nà kejì tí a lè gba pa ìró fáwẹ́lì jẹ ni kí a pa fáwẹ́lì tí kò bá fara kan fáwẹ́lì mìíràn jẹ. Irú ìpajẹ báyìí máa ń wáyé ní ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀, pàápàá fún ọ̀rọ̀-orúkọ. Bí àpẹẹrẹ

Ọmọbọ́lá → mọbọ́lá
Adéléke → déléke
Iyàrá → yàrá
Ibalùlẹ̀ → balùlẹ̀
Ifágbọlá → Fagbọlá

### 3.3 Ìhun tí Ìpajẹ Fáwẹ́lì ti lè Wáyé

Oun tí Bámgbóṣe (1990) pè ní òté fáwẹ́lì pípajẹ ni Owólabí (2013) pè ní ìhun tí ìpajẹ fáwẹ́lì ti lè wáyé. Àwá rò pé, a dára kí a fara mọ́ ìhun yìí ti Owólabí yìí nítorí pé àwọn ìpajẹ yìí wàyé nínú ìhun gírámà ni.

#### 3.3.1 Ìpajẹ Fáwẹ́lì nínú Àpólà-orúkọ

Owólabí ṣàlàyé pé àpólà-orúkọ tí ìpajẹ fáwẹ́lì ti wayé lè ní ìrísí báyìí:

##### 3.3.1.1 Ọ̀rọ̀-orúkọ àti ọ̀rọ̀-orúkọ

**Commented [O.J40]:** nílò

**Commented [O.J41]:** Ẹ lo táàbù láti to àwọn àpẹẹrẹ yìí àti àwọn tókù kí wọn lè dùn ún wò

**Commented [O.J42]:** Kò fi bẹ́ẹ̀ tọ̀nà láti máa sọ ohun tí ẹnìkọ̀ọ̀kan sọ nípa ohun kan nínú èròjà ìkọ́ni báyìí, àfi tó bá jẹ́ pé àríyànjiyàn ni kọ́ọ̀sì yìí dá lé. Iṣẹ́ olùkọ́ ni wọ́n ní kí a ṣe níbí kì í ṣe ọ̀fintótó. Ohun tí èrò wọn jọ lójú yín ni mo rò pé wọ́n fẹ́ kí ẹ fi kọ́ wọn.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Bámgbóṣé (1990) sọ pé àrànmọ́ ni ó wọ́pọ̀ nínú irú ìhun yìí, bí àpẹẹrẹ

ará oko → aróoko

àmọ́ sá, àpapọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ kan wa tí ó ní ìtumọ̀ àkànlò, irú ọ̀rọ̀ báyìí ipajẹ kó wáyé fún irú wọn. àpẹẹrẹ tí ó fún wa ni:

Commented [O.J43]: À

ewé oko → ewéko
aya ọba → ayaba
ẹ̀bá odò → ẹ̀bádò

irun àgbọ̀n → irungbọ̀n
ọ̀tún ọba → ọ̀túnba
ẹran oko → ẹranko
ìdí ọkọ̀ → ìdíkọ̀ **Ẹ TẸ̀LÉ ÌLÀNÀ YẸN LÁTI TO ÀWỌN TÓKÙ**

nítorí yìí, Bámgbóṣe gbé òfin ìsàlẹ̀ yìí kalẹ̀ láti jẹ́ kí a mọ ìró tí a ó pa jẹ bí ọ̀rọ̀-orúkọ bá fẹ̀gbẹ́ kẹ̀gbẹ́ pẹ̀lú ọ̀rọ̀-orúkọ mìíràn

Commented [O.J44]: Nítorí idí èyí

$F_1 + F_2 \rightarrow F_1$

Èyí túmọ̀ sí pé fáwẹ́lì tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ kejì ni a pajẹ. Ó yẹ kí a sọ pé òfin Bámgbóṣé yìí kìí ṣe gbé e tán o. Àwọn kòbẹ́gbẹ́mu kan wa tí òun náà tọ́ka sí

orí òkè → orókè
ojú omi → ojómi
ìlú ètò → ìletò
ojú orun → ojórun

ohun mìíràn tí a tún gbọ́dọ̀ fàyọ ni pé kò sí ìtumọ̀ àkànlò nínú ọ̀rọ̀-orúkọ méjì tó fẹ̀gbẹ́ kẹ̀gbẹ́ tí ìpajẹ sì wáyé gẹ́gẹ́ bí àlàyé Bámgbóṣé. Àbí ìtumọ̀ àkànlò wo ni ó wà nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

Commented [O.J45]: Àkòrí kọ̀ọ̀sì yìí kì í s.e àríyànjiyàn rárá o.

ọbọ̀ ìkan → ọbàkan
ìyá alájé → ìyálájé
ọba obìnrin → ọbabìnrin
ẹrú ọkùnrin → ẹrúkùnrin

#### 3.3.1.2 Oní + ọ̀rọ̀-orúkọ

Owólabí (2013:176) ṣàlàyé pé nínú àpólà-orúkọ tí ó ní irú ìhun yìí, fáwẹ́lì *i* ni ó máa ń bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ. Bẹ́ẹ̀ ni fáwẹ́lì *i* yìí ni ìpajẹ máa ń kàn nígbà gbogbo gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ wọ̀nyí ṣe fi hàn:

oní igi → onígi
oní ìgbàgbọ́ → onígbàgbọ́
oní ìmọ̀le → onímọ̀le
oní ìwàásù → oníwàásù

òfin tí a lè dábàá fún ìhun yìí ni:

Commented [O.J46]: O

$$\mathbf{F_1 + F_2 \rightarrow F_2}$$

Èyí túmọ̀ sí pé fáwẹ́lì tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ kejì ni a ó pajẹ.

Àmọ́ sá, bí ọ̀rọ̀ tí a bá so oní mọ́ bá bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú fáwẹ́lì mìíràn yàtọ̀ sí fáwẹ́lì i, òfin òkè yìí kò ṣiṣẹ́. Àti pé àyọrísí rẹ̀ máa ń kọjá ìpajẹ nìkan. Àwọn ìgbésẹ̀ mìíràn bí i àrànmọ́, ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò abbl. náà máa ń wáyé. Ṣùgbọ́n nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìpajẹ nìkan ni a ó wò.

oní ata → aláta
oní ẹmu → ẹlẹ́mu
oní epe → elépo
oní ọmọ → ọlọ́mọ

A ó ṣàkíyèsí pé fáwẹ́lì tí ó parí *oní* ni a pajẹ nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí. Èyí gan an ni ó fa ìyípada *n* sí *l*. Nítorí náà, a gbọdọ̀ bàbàá òfin mìíràn ìwọ̀n ìgbà tí òfin àkọ́kọ́ kò lè ṣiṣẹ́ fún àwọn àpẹẹrẹ yìí.

Commented [O.J47]: gan-an

Commented [O.J48]: ???bàbàá

$$\mathbf{F_1 + F_2 \rightarrow F_1}$$

### 3.3.2 Ìpajẹ Fáwẹ́lì nínú Àpólà-ìṣe

Owólabí (2013:177) sọ pé àpólà-ìṣe tí ìpajẹ ti lè wáyé ni ọ̀rọ̀-ìṣe + ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí ọ̀rọ̀-ìṣe + ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ.

#### 3.3.2.1 Ọ̀rọ̀-ìṣe + Ọ̀rọ̀-orúkọ

Bámgbóṣé (1990:60) ní ó sòro púpọ̀ láti fi òté tí ó múná dóko lé irú fáwẹ́lì tí a ó pajẹ ní irú ìhun yìí. Ó ṣàlàyé pé, ó ṣe é ṣe kí fáwẹ́lì kan náà ní pípajẹ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, bí àpẹẹrẹ:

fọ aṣọ → fọṣọ
fọ apẹ → fapẹ

a ṣe àkíyèsí pé *a* tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ (aṣọ) ni a pajẹ nínú àpẹẹrẹ àkọ́kọ́ ṣùgbọ́n *ọ* tí ó gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀-ìṣe (fọ) ni a pajẹ nínú àpẹẹrẹ kejì. A tún lè fi ọ̀pọ̀ àpẹẹrẹ hànníbi tí a ti pa fáwẹ́lì tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ jẹ

**Commented [O.J49]:** A

ka owo → kawó
gbé ẹsẹ̀ → gbésẹ̀
gbẹ́ odó → gbẹ́dó
gba iná → gbaná

àpẹẹrẹ ibi tí a ti pa fáwẹ́lì tí ó gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀-ìṣe jẹ nìyí

**Commented [O.J50]:** À

gbé odó → gbódó
fẹ́ ọmọ → fọ́mọ
pa ẹran → pẹran
fọ́ àwọ → fáwo

ó tún ṣe é ṣe kí a rí àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀-ìṣe + ọ̀rọ̀-orúkọ tí ó jẹ́ pé èyí tí ó bá wù wá ni a ó pajẹ nínú àwọn fáwẹ́lì tí wọ́n pàálà:

**Commented [O.J51]:** Ó

jẹ iyán → jiyán tàbí jẹyán
gbé ẹaẹ̀ → gbésẹ̀ tàbí gbẹ́sẹ̀

gba iná → gbiná tàbí gbana **Ẹ LO TÁÀBÙ FÚN ÀWỌN TÓKÙ**
fọ aṣọ → fọṣọ tàbí faṣọ

Bámgbọ́ṣé (1990) sọ pé irú ìpajẹ báyìí le mú pọ́nna lọ́wọ́. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

bọ́ aṣọ → bọ́ṣọ (yàtọ̀ sí básọ tí a rí láti bá aṣọ)
ta epo → tepo (yàtọ̀ sí tapo tí a rí láti ta epo)
bí ọmọ → bímọ (yàtọ̀ sí bọ́mọ tí a rí láti bọ́ ọmọ)

a ó ṣàkíyèsí pé àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe yìí ni ó ń fa ìtumọ̀ onípọ́nna ti ìpajẹ báyìí lè mú wà. Ẹ jẹ́ kí a tún wo àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

bọ́ ọba/bú ọba/ bí ọba → bọ́ba
gbé aago/gbá aago/ gbọ́ aago/ → gbáago
ra epo/ ru epo/ re epo → repo **Ẹ TÚN WỌN TÒ**

ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn àyorísí òkè yìí ni ó ní pọ́nna bí wọ́n bá dá dúró tí ènìyàn yóò sì máa wá ìtumọ̀ wọn lọ sí ọ̀kan lára ìṣẹ̀dá wọn tí ó bá ọ̀rọ̀ tàbí ìsẹ̀lẹ̀ tí ó bá ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́ tí ìpèdè bẹ́ẹ̀ fi wáyé.

Àwọn ipajẹ kan tún wà tí Bámgbóṣe (1990) ní wọ́n ní ìtumọ̀ àkànlò. Irú ọ̀rọ̀-ìṣe àkànmórúkọ yìí ni Awóbùlúyì (2013:127) pè ní "Iṣe-ní-àkànpọ̀". Awóbùlúyù ní àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe kan wà tí ó jọ pé àwọn ará ìgbànì fi àṣà kàn pọ̀ mọ́ àbọ̀ wọn. irú àwọn àpólà-ìṣe àkànpọ̀ bẹ́ẹ̀ sì tipasẹ̀ bẹ́ẹ̀ di àkànlò fún gbogbo èèyàn. Àpẹẹrẹ ni:

gbá ara → dára
rán etí → rántí
jẹ́ ọwọ́ → jẹ́wọ́
gbà ègbé → gbàgbé
mú ara → múra

**Commented [O.J52]:** A

**Commented [O.J53]:** Ọ̀

**Commented [O.J54]:** Awóbùlúyì

**Commented [O.J55]:** Irú

a ó ṣàkíyèsí pé gbogbo àwọn àpẹẹrẹ yìí ló ní ìtumọ̀ àkànlò àmọ́ àwọn kan tún wà tí ó jẹ́ pé èyí tí a bá ba fáwẹ́lì rẹ̀ jẹ ni yóó sọ bóyá yóó ní ìtumọ̀ àkànlò tàbí kò ní ní. Wo àpẹẹrẹ ìyàlẹ̀ yìí

Commented [O.J56]: níí ní

| | |
|---|---|
| gbé ẹsẹ̀ → gbẹ́sẹ̀ (ìtumọ̀ àdámọ́) | gbésẹ̀ (ìtumọ̀ àkànlò) |
| gba iná → gbaná | gbiná |
| gba ilẹ̀ → gbalẹ̀ | gbilẹ̀ |
| rí ọ̀nà → rọ́nà | rínà |
| fẹ́ ọwọ́ → fọ́wọ́ | fẹ́wọ́ |

A ṣàkíyèsí pé èrò Bámgbóṣé (1990) yìí dára ṣùgbọ́n kò fẹ́ẹ̀ẹ́ sí ìyàtọ̀ nínú yíya àwọn onítumọ̀ àkànlò sátọ̀ sí onítumọ̀ àdámọ́ nítorí pé méjéèjì ni àwa Yorùbá òde oní ń lò gẹ́gẹ́ bí onítumọ̀ àkànlò tàbí onítumọ̀ àdámọ́. Èyí gan-an náà fara pẹ́ èyí tí ó pè ní ẹlẹ́ka-èdè. Bámgbóṣé ní ẹni tó bá wá láti agbègbè Ọ̀yọ́ àti Ìbàdàn yóó ṣe ìpajẹ àkọ́kọ́ nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí; ṣùgbọ́n ẹni tó bá wa láti agbègbè Ìjẹ̀bú yóó ṣe ìpajẹ fáwẹ́wì kejì:

jẹ ọkà → jẹkà / jọkà
bu ọbẹ̀ → bubẹ̀ / bọbẹ̀
pín epo → pínpo/ pénpo

#### 3.3.3 Ìpajẹ Fáwẹ́lì nínú Ìhun Mìíràn

Commented [O.J57]: Ẹ sà á lámì dúdú

Owólabí (2013:178) ni dẹ̀ nínú àwọn ìhun mìíràn tí a ti pa fáwẹ́lì kan nínú méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí wọ́n dúró ti ara wọn ni:

àfi ènìyàn → àfẹ̀nìyàn
àti ẹ̀yin → àtẹ̀yin
aya-kí-aya → ayakáya
bí o → bó (bí ó bá dé → bó bá dé)
nì bá → ǹbá (n ìbá pariwo → ǹbá pariwo)

### 3.4 Ìpajẹ ohùn

Ọ̀kan nínú àwọn ègé tí ó ṣe é ṣe láti pajẹ ni ohùn wà. Owólabí (2013:178) ṣàlàyé pé a lè fi òfin tàbí ìlànà lélẹ̀ fún irú ohùn tí a ó pajẹ àti èyí tí a ní láti dásí nígbà tí àwọn méjéèjì bá pàdé nínú ìhun kan.

### 3.4.1 Ìhun tí ìpajẹ ohùn ti lè wáyé

Owólabí (2013:179) pín ìhun tí ìpajẹ ohùn ti lè wáyé sí ọ̀nà méjì: ìpajẹ ohùn nínú ìhun tí ọ̀rọ̀-arópò-orúkọ ti jẹ́ wúnrẹ̀n kèjì àti ìpajẹ ohùn nínú àwọn ìhun mìíràn.

Commented [O.J58]: Kí ló dé tí ẹ kò lè sọ pé: ìhun tí ìpajẹ ohùn ti lè wáyé pín sí ọ̀nà méjì kí ẹ yọ Owólabí kúrò?

**Ìpajẹ ohùn nínú ìhun tó ọ̀rọ̀-arapò-orúkọ ti jẹ́ wúnrẹ̀n kejì**

Commented [O.J59]: tí

Nínú irú ìhun yìí, ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ máa ń jẹ́ kìkìdá fáwẹ́lì tí ó ní ohùn òkè tàbí ohùn ààrín. Ohùn tí òun àti ti arọ́pò-orúkọ bá jọ pàdé ni ìpajẹ máa ń kàn nígbà gbogbo. Fún ìdí èyí, Owólabí dábàá àwọn òfin àti ìlànà ìsàlẹ̀ yìí:

Commented [O.J60]: ọ̀rọ arọ́pò-orúkọ/arọ́pò-orúkọ

i. Nígbà tí ohùn òkè àti ohùn ààrin ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ bá pàdé, ohùn òkè ni a níláti pa jẹ. A óò dá ohùn ààrín ti ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ sí:

    pín in → pin
    bí o → bo (b.a bí o ba jà → bo bá jà)
    kí a → ka (kí a jó → ka jó)

    òfin náà ní sókí **O + A → A**

ii. Nígbà tí ohùn ààrín àti ohùn òkè ti ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ bá pàdé, ohùn ààrín ni a níláti pa jẹ. a ó dá ohùn òkè ti ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ sí

    pa á → pá (ó pa á → ó pá)

jọ ọ́ → jọ́ (o jọ ọ́ → o jọ́)
ṣe é → ṣé (kò ṣe é → kò ṣé)

òfin náà ní sókí A **+ O → O**

iii. Nígbà tí ohùn ìsàlẹ̀ àti ohùn òkè ti ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ bá pàdé, ohùn ìsàlẹ̀ ni a níláti pa jẹ. A ó dá ohùn òkè ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ sí:

bàtà ó pọ̀ → bàtá pọ̀
fìlà ó sí → fìlá sí
ẹ̀wù ó ya → ẹ̀wú ya
òfin rẹ̀ ní sókí **I + O → O**

Àmọ́ o, bí ohùn mìíràn, yàtọ̀ sí ohùn ìsàlẹ̀, bá jẹ yọ ṣáájú ohùn ìsàlẹ̀ tí òun àti ohùn òkè ti ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ jọ pàdé, ìpajẹ ohùn ìsàlẹ̀ lábẹ́ òfin kẹta yìí kò ní wáyé. Bí àpẹẹrẹ:

tíṣà ó wá → tíṣàá wá
ọbẹ̀ ó dùn → ọbẹ̀ẹ́ dùn

Àpẹẹrẹ yìí fi hàn pé kí a tó lè mú òfin kẹta lò, ohùn ìsàlẹ̀ mìíràn gbọ́dọ̀ jẹ yọ ṣáájú ohùn òkè tí òun àti ohùn ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ.

#### 3.4.1.1 Ìpajẹ ohùn nínú àwọn ìhun mìíràn

Fún ìpajẹ ohùn nínú ìhun mìíràn àwọn òfin tí a ó tẹ̀lé ni èyí:

i. Nígbà tí ohùn òkè àti ohùn àárín bá pàdé. Ohùn àárín ni a ó pa jẹ, a ó dá ohùn òkè sí: àpẹẹrẹ ni

ìdí ọkọ̀ → ìdíkọ̀
ewé ọbẹ̀ → ewébẹ̀
kó owó → kówó

ii. Nígbà tí ohùn àárín àti ohùn ìsàlẹ̀ bá fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́, ohùn àárín ni a ó pa jẹ, a ó dá ohùn ìsàlẹ̀ sí. Àpẹẹrẹ ni:

pa ìgbín → pàgbín
kọ ìwé → kọ̀wé
jẹ ẹ̀ba → jẹ̀bà
jẹ ẹ̀fọ́ → jẹ̀fọ́

iii. Nígbà tí ohùn òkè àti ohùn ìsàlẹ̀ bá fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́, ohùn ìsàlẹ̀ ni a ó pa jẹ, a ó dá ohùn òkè sí (àmọ́ ohùn ìsàlẹ̀ tí a pa jẹ yìí lè di ohùn ìsàlẹ̀ amúkùn-ún tàbí kó má dì í)

gbé ìwé → gbéwèé
kó ẹ̀pà → kẹ́pà
ojú òde → ojúde

**4.0 Isonísókí**

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti wo ìpajẹ gẹ́gẹ́ bí ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì. A ṣe àgbéyẹ̀wò ìpajẹ kọ́nsónáǹtì, fáwẹ́lì àti ohùn. A wo ìhun tí àwọn ìpajẹ yìí ti lè wáyé gẹ́gẹ́ bí àlàkalẹ̀ àwọn onímọ̀. Bẹ́ẹ̀ náà ni a wo àbá òfin ìpajẹ tí àwọn onímọ̀ dá tí a sì mẹ́nu ba àwọn kòbẹ́gbẹ́mu àpẹẹrẹ fun àwọn òfin náà.

Commented [O.J61]: àwọn àpẹẹrẹ kòbẹ́gbẹ́mu

Ohun tí ó hànde ni pé òfin gbé e tán ò tîì sí fún ìpajẹ èdè Yorùbá pàá pàá ìpajẹ fáwẹ́lì. Nítorí náà iṣẹ́ kò dúró láti wá òfin gbé e tán fún ìpajẹ nínú èdè Yorùbá.

**5.0 Ìdánwò Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

i. Ṣe àlàyé àwọn ìró tí a lè pajẹ

ii. Ṣe àlàyé àwọn òfin tí ó de pípa ìró jẹ

iii. Ṣe àfihàn ìhun tí pípa ìró jẹ ti lè wáyé

**Àtòjọ Ìwé tí a lò**

Commented [O.J62]: "Ìwé Ìtọ́kasí" ni wọ́n ní kí a lò

Awóbùlúyì Ọládélé (2013) *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*. Osogbo. ATMAN Limited

Bámgbóṣé Ayọ̀ (1990) *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ibadan. University Press PLC.

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá 1: Fónẹ́tíìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

Oyebade Francis (2001) Ìgbésẹ̀ àti Ìlànà Fonọ̀lọ́jì Èdè Yorùbá nínú Ajayi Bade (Olóòtú) *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá-Èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà*. Ìjẹ̀bú-Òde. Shebiotimọ Publications

Oyelaran O.O. (1971) Yoruba Phonology. Doctoral Dissertation, Stanford University, Palo Alto, California.

**Àtò ìsàlẹ̀ yìí ni Ọ̀jọ̀gbọ́n ní kí a tẹ̀lé o**

(1). Writers must obligatorilly follow the presentation psttern thus:

1.0. Ifaara

2.0. Erongba ati Afojusun

3.0. Ibeere Isaaju

4.0. Idanilekoo

5.0. Isonisoki

6.0. Ise Sise

7.0. Iwe Itokasi

# ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ KJÌ
# ÀRÀNMỌ́

## 1.0 Ìfáárà

A ṣàlàyé àrànmọ́ ní inú LIY 214, a ó tún mẹ́nu bà á nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Ìdí tí a ó fi ṣe bẹ́ẹ̀ ni pé, o di dandan fún wa láti tún ṣe àgbéyẹ̀wò ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì yìí nítorí pé, òun náà pẹka bí i ti ìpajẹ fáwẹ́lì ni. Ó sì yẹ kí á wò ó fínnifínni. A ó wo ohun tí àwọn onímọ̀ ti sọ, bẹ́ẹ̀ ni a ó ṣe àríwísí tiwa náà si. Lára àwọn ohun tí a ó gbéyẹ̀wò ni: àwọn ẹ̀yà àrànmọ́, ìhun tí àrànmọ́ ti máa ń wáyé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## 2.0 Èròǹgbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Lópin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó le:

i. ṣe àlàyé ẹ̀yà àrànmọ́ tí ó wà

ii. sọ ìhun tí àrànmọ́ ti máa ń wáyé

### 2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ẹ̀kọ́

Dáhùn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí:

1. Pẹ̀lú àpẹẹrẹ ṣàlàyé àwọn ẹ̀yà àrànmọ́ tí ó wà nínú èdè Yorùbá

2. Pàálà sáàrin ìró agbàrànmọ̀ àti ìró afàrànmọ̀.

### 3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Kí ni àrànmọ̀?

Àrànmọ̀ ni agbára tí ìró kan ni láti sọ ìró mìíràn ti irú ara rẹ̀???. Bámgbóṣé (1990:47) ní, nígbà tí ìró kan bá yí padà láti fara jọ ìró mìíràn, irú ìyípadà báyìí ni à ń pé ní àrànmọ̀. Owólabí (2013:189) kì àraǹmọ̀ báyìí: Àrànmọ̀ gẹ́gẹ́ bí ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì tọ́ka sí agbára tí ìró kan ní lórí (pípe) ìró mìíràn èyí tí ó lè mú kí ìró méjéèjì di ọ̀kan-ùn tàbí kí wọ́n fi nǹkankan jọ ara wọn. Ìyí túmọ̀ sí pé ìró kan lè mú gbogbo àbùdá ìró kan tàbí kí ó mú lára àbùdá ìró mìíròn. Àpẹẹrẹ ni

ọdún ọdún → ọdọọdún
ọ̀wọ̀ ọ̀wọ̀ → ọ̀wọ̀ọ̀wọ̀

nínú àpẹẹrẹ àkọ́kọ́ ìró *un* mú gbogbo àbùdá ìró *ọ* tí ó sì yí fáwẹ̀lì *un* di *ọ*.

Àpẹẹrẹ kejì fi ohùn òkè hàn pé ó mú àbùdá ohùn ìsàlẹ̀.

Ìró tí ìró mìíràn mú lára abùdá rẹ̀ tàbí gbogbo àbùdá rẹ̀ ni a mọ̀ sí ìró ***afàrànmọ́***. Nígbà tí ìró tí ó mú gbogbo àbùdá tàbí lára àbùdá ìró mìíràn ni a mọ̀ sí ìró ***agbàrànmọ́***. Bámgbóṣé (1990:47) sọ pé, ìró tí ó yí padà ni ó gba àrànmọ̀ sára; nítorí náà a lè pè é ní **àgbàrànmọ̀**. Ìró tí ó mú kí èkejì gba àrànmọ̀ ni ó máa ń ràn mọ́ ìró mìíràn. Nítorí èyí a lè pè é ní **aṣàrànmọ̀**.

A ó rí pé ohun tí Owólabí pè ní afàràmọ̀ ni Bámgbóṣé pè ní asàrànmọ̀. A wá lè fi àpẹẹrẹ òkè yìí ṣe àlàyé àwọn kókó ọ̀rọ̀ méjéèjì (afàrànmọ̀ àti agbàrànmọ̀) báyìí; ìró *ọ* ni ìró afàràmọ̀ nítorí pé òun ni ìró *un* mú àbùdá rẹ̀. Ìró *un* sì ni ìró agbàrànmọ̀ nítorí pé, oun ni ó mú àbùdá ìró mìíràn.

Commented [O.J63]: Align left

#### 3.1 Ẹ̀yà (Orísìí) Àrànmọ̀

Àwọn wọ̀nyí ni orísìí àrànmọ̀ tí ó fojú hànde jù nínú èdè Yorùbá:

Commented [O.J64]: wà

(a) Àrànmọ̀wájú àti Àrànmẹ́yìn

(b) Àrànmọ̀ aláìfòró àti Àrànmọ̀ afòró

(d) Àrànmọ̀ kíkún àti Àrànmọ̀ Ẹlẹ́bẹ

## (a) Àrànmọ̀wájú

Bí a bá lo apá ọ̀tún àti apá òsì, tí a sì gbà pé apá ọtún wà ní iwájú apá òsì tí ìró afàrànmọ́ tí ó wà ní apá òsì lo agbára àrànmọ́ rẹ̀ lọ sí iwájú lọ bá ìró agbàrànmọ́ láti sọ ọ́ di irú ara rẹ̀, èyí ni a mọ̀ sí àrànmọ́-wájú.

ilé ìwé → iléèwé
a ò wá → a à wá
owó iṣẹ́ → owóoṣẹ́

ìró *é* tí ó gbẹ̀yìn *ilé* lo agbára àrànmọ́ rẹ̀ láti sọ ìró *i* tí ó bẹ̀rẹ̀ *ìwé* di irú ara rẹ̀. Ìró *e* gẹ́gẹ́ bí ìrí afàrànmọ́ lo agbára àrànmọ́ rẹ̀ síwájú láti sọ ìrí *i* gẹ́gẹ́ bí ìró agbàrànmọ́ di irú ara rẹ̀. Bẹ́ẹ̀ lọmọ́ sorí fún ìró *à* àti *ò*. Nígbà tí ìró *a* jẹ́ ìró afàrànmọ́, ìró *ò* ni ìró agbàrànmọ́. Ìgbésẹ̀ kan náà ló ṣelẹ̀ láarin ìró *ó* àti ìró *i*.

Owólabí (2013:191) gbé àlàkalẹ̀ ìsọnísókí yìí kalẹ̀:

**R** fún ìró (yálà kọ́nsónáǹtì, fáwẹ́lì tàbí ohùn)

**R₁** fún ìró apá òsì

**R₂** fún ìró apá ọ̀tún

Nítorí náà, àrànmọ́ iwájú yóò wá jẹ́

$\mathbf{R_1\ R_2 \rightarrow\ R_1R_1}$

**Àrànmẹ́yìn**

Àmọ̀ bí ìró afàrànmọ́ bá wà ní apá ọ̀tún tí ó wá lo agbára àrànmọ́ rẹ̀ sẹ́yìn lọ bá ìró agbàrànmọ́ tí ó wà ní apá òsì, a ó pe irú àrànmọ́ bẹ́ẹ̀ ní àrànmẹ́yìn. Àpẹẹrẹ ni:

ọdún ọdún → ọdọọdún
ará ọ̀run → arọ́ọ̀run
ará oko → aróoko

Commented [O.J65]: gbé gbogbo àbùdá ajẹ́mọ́fónẹ́tíìkì rẹ̀ wọ ìró *i* tí ó bẹ̀rẹ̀ *ìwé* láti sọ́ di irú ara rẹ̀

Commented [O.J66]: gbé gbogbo àbùdá ajẹ́mọ́fónẹ́tíìkì rẹ̀ wọ ìró láàrin agbàrànmọ́

a ó ṣàkíyèsí pé ìró *ọ* tí ó bẹ̀rẹ̀ ọdún kejì ni ìró afàrànmọ́ tí ó sọ ìró *un* tí ó parí ọdún alákọ̀ọ́kọ́ di irú ara rẹ̀. Nínú àpẹẹrẹ kejì, ìró *ọ̀* ni ìró afàrànmọ́ nígbà tí ìró *á* jẹ́ ìró àgbàrànmọ́. Àpẹẹrẹ kẹta kò yàtọ̀, òrí *o* lo agbára àrànmọ́ rẹ̀ sẹ́yìn láti sọ ìró *á* di irú ara rẹ̀.

Ìsọnísókí Owólabí yóó gbé àlàkalẹ̀ yìí fún wa nípa àrànmọ́yìn

**$R_1$ $R_2$ → $R_2R_2$**

**(b) Àrànmọ́ aláìfòró**

Ó ṣe é ṣe láti pín àrànma sí afòró àti aláìfòró bí a bá lo òsùnwọ̀n bí ìró mìíràn bá jẹ yọ láàrin ìró afàrànmọ́ àti agbàrànmọ́.

Ní ìgbà tí kò bá sí ìró kankan láàrin ìró afàrànmọ́ àti ìró agbàrànmọ́, tí àrànma sì wáyé, a ó sọ pé àrànmọ́ aláìfòró ti ṣẹlẹ̀. Àpèèrè ni

ilé ìwé → iléèwé
ará ọ̀run → arọ́ọ̀run
kú àbọ̀ → káàbọ̀
ọmọ àlè → ọmàálè

A ó rí pé kò sí ìró kankan láarin ìró afànrànmọ́ àti àgbàrànmọ́ nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí. Nítorí náà, a ó pe irú àpẹẹrẹ bẹ́ẹ̀ ni àrànmọ́ aláìfòrò.

**Àrànmọ́ afòró**

Bí ìró afàrànmọ́ àti agbàrànmọ́ kò bá fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ tààrà, tí ìró kan tàbí òmíràn bá wà láarin wọn, tí irú ìpààlà bẹ́ẹ̀ kò sì dí àrànmọ́ lọ́wọ́, a ó pe irú àrànmọ́ bẹ́ẹ̀ ni àrànmọ́ afòró. Àpẹẹrẹ ni:

oní + ata → aláta
oní + ẹja → ẹlẹ́ja
oní + ewé → eléwé

A ó rí pé ìró méjì ló wà láàrin ìró agbàrànmọ́ àti ìró afàrànmọ́: ìró *í* àti ìró *ń*. Ìró *a*, *ẹ*, àti *e* ni ìró afàrànmọ́ nígbà tí ìró *o* jẹ́ ìró agbàrànmọ́. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èrò àwọn onímọ̀ sọ̀ọ̀tọ̀tọ̀ lórí ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì tí ó ṣelẹ̀ nínú

Commented [O.J67]: lááàrin

àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí. Àwọn kan gbà pé àǹkóò fáwẹ́lì ni a ṣelẹ̀ tí ó mú ìyípadà bá *oní* + *ata* láti di *alata*. Àwọn mìíràn gbà pé ìpajẹ ìró *í* ni ó kọ́kọ́ wáyé. Ẹ má gbàgbé pé ìró *í* yìí jẹ́ aránmú. Bí a bá mú ìró aránmú yìí kúrò, ìró *n* yóó sọ ìránmú rẹ̀ nù, yóó wá ní àbùdá àìránmú èyí tí ṣe *l* gẹ̀gẹ̀ bí a ṣe rí i nínú àbájáde òkè yẹn. lẹ́yìn náà ni àrànmọ́yìn afòró wá wáyé ní ibi tí fáwẹ̀lì tí ó bá bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ orúkọ yóó ti sọ fáwẹ̀lì tí ó bẹ̀rẹ̀ *oní* di irú ara rẹ̀.

**(d) Àrànmọ́ Kíkún**

Tí ìró afàrànmọ́ bá lo agbára àrànmọ́ rẹ̀ láti jẹ́ kí ìró àgbàrànmọ́ mú gbogbo àbùdá ìró afàrànmọ́ tó bẹ́ẹ̀ tí ìró afàrànmọ́ àti ìró agbàrànmọ́ di ọ̀kan-ùn, irú àrànmọ́ bẹ́ẹ̀ ni a mọ̀ sí àrànmọ́ kíkún. Àpẹẹrẹ ni:

ọdún + ọdún → ọdọọdún
ọmọ + àlè → ọmàálè

a ṣe àkíyèsí pé ìró *un* tí ó ní ohùn òkè gba gbogbo àbùdá ìró *ọ* olóhùn ààrín tí ó jẹ́ ìró afàrànmọ́ pẹ̀lú gbogbo àbùdá rẹ̀ tó bẹ́ẹ̀ tí àwọn méjééjì fi di ọ̀kan-ùn. Ohun kan náà ni ó ṣẹlẹ̀ ni àpẹẹrẹ kejì ní ibi tí ìró *ọ* tí ó gbẹ̀yìn *ọmọ* sọ àbùdá rẹ̀ nù láti mú àbùdá ìró *a* tí ó bẹ̀rẹ̀ *àlè* pẹ̀lú ohùn rẹ̀.

**Àrànmọ́ Ẹlẹ́bẹ**

Bí ìró agbàrànmọ́ bá mú apá kan tàbí díẹ̀ lára àbùdá ìró afàrànmọ́, a jẹ́ pé irú àrànmọ́ bẹ́ẹ̀ jẹ́ àrànmọ́ ẹlẹ́bẹ. Àpẹẹrẹ ni:

ìwọ̀nyí → ìwọ̀nín
ó wà níbí → ó wà ńbí → ó wà ḿ b̄í

Commented [O.J68]: Align all these and others with left margin

ohun tí ó sẹlẹ̀ níbí ni pé, ìpajẹ ìró ‘y’ mú kí ìró *í* tí kìí ṣe aránmú súnmọ́ ìró aránmú ìyẹn ìró *ọ̀n*, èyí mú kí ìró *í* mú àbùdá ìránmú lára *ọ̀n* tí òun náà fi ni ìránmú láti fi *ín*. Ohun tó ṣẹlẹ̀ níbí gan-an ni pé ìránmú nìkan ni ìró *í* mú nínú àwọn àbùdá *ọ̀n*. Ìpajẹ fáwẹ̀lì nínú ọ̀rọ̀ *níbí* sọ kọ́nsónáǹtì [n] di

kọnsónáǹtì aránmú aṣesílébù. Ṣùgbọ́n torí pé ń jẹyọ sáájú kọnsónáǹtì afèjì-ètè-pè, òun náà mú àbùdá yìí láti sọ ọ́ di ḿ. Nítorí ìdí èyí, a ó sọ pé irú àrànma yìí jẹ́ àrànmọ́ ẹlẹ́bẹ.

## 3.2 Àrànmọ́ Ohùn àti Àrànmọ́ Fáwẹ́lì

Bámgbóṣé (1990:47-48) ni àrànmọ́ lè jẹ́ àrànmọ́ ohùn àtí àrànmọ́ fáwẹ́lì

### 3.2.1 Àrànmọ́ Ohùn

Àrànmọ́ ohùn ni ìyípadà ohùn kan láti fara jọ ohùn mìíràn. Bí àpẹẹrẹ

| | | |
|---|---|---|
| eégún | → | éégún |
| oókan | → | óókan |
| aájò | → | áájò |
| eérú | → | éérú |

ohun tí ó fojú hàn nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí ni pé ohùn òkè ni ó sọ ohùn àárín di irú ara rẹ̀. Ìyẹn ni pé, ohùn òkè ni ìró afàrànmọ́ nígbà tí ohùn àárín jẹ́ ìró agbàrànmọ́.

Àpẹẹrẹ mìíràn níbi tí ohùn ìsàlẹ̀ ti jẹ ìró afàrànmọ́ tí ohùn àárín sì jẹ ìró agbàrànmọ́ ni ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí:

| | | |
|---|---|---|
| oògùn | → | òògùn |
| eèpẹ̀ | → | èèpẹ̀ |
| oòrùn | → | òòrùn |
| ò-ṣiṣẹ́ | → | òṣìṣẹ́ |
| ò-jowú | → | òjòwú |

a ṣàkíyèsí pé ohùn ìsàlẹ̀ ràn mọ́ ohùn àárín nínú àpẹẹrẹ òkè yìí.
Ibi tí ohùn àárín ti jẹ́ ìró afàrànmọ́ ni àpẹẹrẹ tí ó kàn. Àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí jẹ́ kí a rí ibi tí ohùn àárín ti sọ ohùn ìsàlẹ̀ di irú ara rẹ̀.

| | | |
|---|---|---|
| ọ̀rọ̀ ọmọ | → | ọ̀rọ ọmọ |
| irú ẹran | → | iru ẹran |
| igò epo | → | igo epo |

ohun tí ó fojú hàn níbí ni pé ohùn àárín ràn mọ́ ohùn ìsàlẹ̀

| | | |
|---|---|---|
| ẹgbẹ́ ẹgbẹ́ | → | ẹgbẹẹgbẹ́ |
| ọjọ́ ọjọ́ | → | ọjọọjọ́ |

àrànmọ́ tí ó wáyé níbí ni pé ohùn àárín sọ ohùn òkè di irú ara rẹ̀

| | | |
|---|---|---|
| ọ̀wọ́ ọ̀wọ́ | → | ọ̀wọ̀ọ̀wọ́ |
| èló èló | → | èlèèló |

àpẹẹrẹ yìí fi hàn pé ìró ohùn ìsàlẹ́ sọ ohùn òkè di irú ara rẹ̀.

Commented [O.J69]: Align to left margin

### 3.2.2 Àrànmọ́ Fáwẹ̀lì

Àrànmọ́ fáwẹ̀lì ni ìyípadà fáwẹ̀lì kan láti fara jọ fáwẹ̀lì mìíràn. Bámgbóṣé (1990) ní tí $F_1$ bá dúró fún fáwẹ̀lì àkọ́kọ́, tí $F_2$ bá dúró fún èkèjì, ó wá gbé òfin àrànmọ́ yìí kalẹ̀

$$F_1 + F_2 \rightarrow F_1 + F_1$$

Tàbí

$$F_2 + F_2$$

Èyí túmọ̀ sí pé bí fáwẹ̀lì méjì bá pàdé ní ààlà sílébù, ó ṣe é ṣe kí ọ̀kan nínú wọn mú àbùdá èkejì. Àpẹẹrẹ ni

| | | |
|---|---|---|
| ilé iṣẹ́ | → | iléeṣẹ́ |
| kú iṣẹ́ | → | kúuṣẹ́ |
| ẹ̀rù igi | → | ẹ̀rùugi |

Bámgbóṣé wá ṣe àfihàn àpẹẹrẹ kòbẹ́gbẹ́mu òfin yìí. Ó ní *i* tàbí *in* kò gba àrànmọ́ lára fáwẹ̀lì tàbí kọ́nsónáǹtì aránmúpè aṣesílébù tí ó fẹ́gbẹ́ tìí

| | | |
|---|---|---|
| mí ò lọ | → | mi ìn lọ |
| kì ń parọ́ | → | kì í parọ́ |

Lóòótọ́ ni a lè sọ pé àpẹẹrẹ kejì kò gba arànmọ́ láti ara fáwẹ̀lì ṣùgbọ́n a ò lè sọ bẹ́ẹ̀ fún àpẹẹrẹ àkọ́kọ́. Ìdí ni pé ìró *ò* mú àbùdá méjì láti ara *í*. Àwọn àbùdá ni àhánupè/òkè, àti ìránmú. Irú

àrànmọ́ yìí ni a lè pè ní àrànmọ́ kíkún. A rí irú àrànmọ́ yìí nínú irú ìyísódì bẹ́ẹ̀ ní inú àpẹẹrẹ mìíràn:

| | | |
|---|---|---|
| ẹ ò lọ | → | ẹ è lọ |
| a ò lọ | → | a à lọ |
| wọn ò lọ | → | wọn ọ̀n lọ |

ṣùgbọ́n ni ti àpẹẹrẹ kejì, ìró kọ́nsọ́náǹtì aránmú aṣesílébù ni ó gba àrànmọ́. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a ò lè pè é ní fáwẹ́lì, àmọ́ asiṣẹ́ odo sílébù ni ó jẹ́ gbogbo àbùdá ìró afàrànmọ́ ni ó mú àyàfi ohun orí rẹ̀ nìkan.

### 3.3 Ìhun tí Àrànmọ́ ti máa ń wáyé

Àrànmọ́ fáwẹ́lì máa ń jẹyọ nínú àwọn ẹ̀hun wọ̀nyí:

1. **Ọ̀rọ̀-Orúkọ àti Ọ̀rọ̀- Orúkọ**

Nínú ẹ̀hun yìí, fáwẹ́lì *i* tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ kejì gbọdọ̀ yí padà láti gba àrànmọ́ lára fáwẹ́lì tí ó gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀-orúkọ kìíní nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

Commented [O.J70]: àbùdá

| | | |
|---|---|---|
| ilé ilẹ̀ | → | iléelẹ̀ |
| ọ̀rọ̀ iṣẹ́ | → | ọ̀rọọṣẹ́ |
| ètò ìlú | → | ètòòlú |

Bámgbóṣé pe àkíyèsí wa sí i pé bí fáwẹ́li **i** bá gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀-orúkọ kìíní, irú àrànmọ́ òkè yìí kìí sábá wáyé:

| | | |
|---|---|---|
| ìdí omi | → | *ìdóomi |
| orí oko | → | *oróoko |

Àmọ́ ni ti àwọn fáwẹ́lì tí ó kù, tí àrànmọ́ bá wáyé, fáwẹ́lì tí ó gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀-orúkọ kìíní ni ó máa ń gba àrànmọ́ lára fáwẹ́lì tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ kejì.

| | | |
|---|---|---|
| ará oko | → | aróóko |
| ìyá ẹgbẹ́ | → | ìyẹẹgbẹ́ |
| aṣọ òkè | → | aṣoòkè |
| ọmọ oko | → | ọmooko |

ó fi kún un pé kì í ṣe gbogbo ọ̀rọ̀-orúkọ àti ọ̀rọ̀-orúkọ ni a máa ń ṣe àrànmọ́ fún. Bí àpẹẹrẹ

| | | |
|---|---|---|
| adé ọba | → | *adọọba |
| ewé obì | → | *ewóobì |
| ijó agbo | → | ijáagbo |

2. **Awọn wúnrẹ̀n gírámà kan àti ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ gẹ́gẹ́ bí olùwà**. Àwọn wúntẹ̀n gírámá bí ǹjẹ́, ṣèbí/ṣebí, àní, àṣẹ́, tí, tàbí/àbí, pé, kí, bí. Fáwẹ̀lì àwọn wúnrẹ̀n yìí ni ó máa gba àrànmọ́

| | | |
|---|---|---|
| ǹjẹ́ o lọ? | → | ǹjó o lọ? |
| ṣé o lọ? | → | ṣó o lọ? |
| ó yẹ kí o lọ | → | ó yẹ kó o lọ |

àwọn kòbẹ́gbẹ́mu kan wà tí a máa ń ṣe fáwẹ̀lì pípajẹ fún dípò àrànmọ́. Àpẹẹrẹ ni

| | | |
|---|---|---|
| bí o bá lọ | → | * bó ó bá lọ |
| bí o bá lọ | → | b'ó bá lọ |

3. **Ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ gẹ́gẹ́ bí olùwà àti Atọ́ka ìyísódì**

Atọ́ka ìyísódì máa ń gba àrànmọ́ lára ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ

| | | |
|---|---|---|
| mì ò lọ | → | mì ìn lọ |
| ẹ ò lọ | → | ẹ ẹ̀ lọ |
| wọn ò lọ | → | wọn ọ̀n lọ |

4. **Ọ̀rọ̀-ìṣe Kú àti Ọ̀rọ̀-orúkọ**

Nínú ẹ̀hun yìí *u* ni ó máa ń gba àrànmọ́ lára fáwẹ̀lì mìíràn

| | | |
|---|---|---|
| kú àbọ̀ | → | káàbọ̀ |
| kú iṣẹ́ | → | kuuṣẹ́ |
| kú alẹ́ | → | káalẹ́ |

akíyèsí ni pé *kú* + *iṣẹ́* tako àlàyé Bámgbóṣé níbí yìí; tí ó sọ pé ìró *u* ni ó gba àrànmọ́. A ó ri pé *u* gan-an ni ó fa àrànmọ́ nígbà tí ó bá di *kú* +

Commented [O.J71]: wúnrẹ̀n

*iṣẹ́*. Ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé kò tîì sí òfin gbéetán fún àrànmọ́ èdè Yorùbá

Owólabí (2013) fún wa ni àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí láti gbe àlàyé wa lẹ́sẹ̀

| | | |
|---|---|---|
| kú ìgbádùn | → | kúùgbádùn |
| kú ilé | → | kúulé |

ìyẹn ni pé bí ọ̀rọ̀-orúkọ bá ti bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú fáwẹ́lì iwájú àhánupè /i/, a jẹ́ pé fáwẹ́lì tí ó gbẹ́yìn ọ̀rọ̀-ìṣe *kú* ni yóó jẹ́ ìró afàrànmọ́.

**5. Àfòmọ́-ìbẹ̀rẹ̀ oní àti Ọ̀rọ̀-orúkọ**

Nínú ẹ̀hun yìí, fáwẹ́lì *ó* nínú *oní* ni ó má ń gba àrànmọ́. Fáwẹ́lì tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ ni ó máa ń fa àrànmọ́. Àmọ́ sá, ó ye kí a fi kún un pé irú fáwẹ́lì bẹ́ẹ̀ kò gbọdọ̀ jẹ́ fáwẹ́lì iwájú ahánupè/òkè. Kí èyí tó lè rí bẹ́ẹ̀, kọ́nsónáǹtì *n* gbọ́dọ̀ di *l*.

| | | |
|---|---|---|
| oní ata | → | aláta |
| oní ẹja | → | ẹlẹ́ja |
| oní ewé | → | eléwé |

**6. Olùwà àti wúnrẹ̀n ìbá tàbí ìbáà**

Fáwẹ́lì *i* ni ó máa ń gba àrànmọ́ nínú ẹ̀hun yìí

| | | |
|---|---|---|
| ọ̀rọ̀ ìbá jáde | → | ọ̀rọ̀ọ̀ bá jáde |
| ìlú ìbáa tú | → | ìlúù báa tú |
| àwa ìbá lọ | → | àwaà bá lọ |

**7. Ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ gẹ́gẹ́ bí olùwà àti wúnrẹ̀n á**

Nínú ẹ̀hun yìí, kan-ńpa ni fún wúnrẹ̀n á láti para dà di ẹ. Ṣùgbọ́n wọ̀fún ni àrànmọ́ pẹ̀lú fáwẹ́lì inú wọ́n.

| | | |
|---|---|---|
| *ẹ̀ á lọ | → | ẹ̀ ẹ́ lọ |
| Wọ́n á lọ | → | wán án lọ |

**8. Atọ́ka ibá-ìsẹ̀lẹ̀ *ń* nínú àwọn ẹ̀hun kan**

Atọ́ka ìbá-ìsẹ̀lẹ̀ ń ni ó máa ń gba àrànmọ́ nínú àwọn ẹ̀hun wọ̀nyí:

(i) Pẹ̀lú atọ́ka ìyísódì: **kì**

kì ń jáde → kì í jáde

wọn kì ń sèkà → wọn kì í sèkà

Commented [O.J72]: ṣèkà

(ii) Pẹ̀lú **tí** tàbí **ni**

ọ̀rọ̀ tí ń túlé → ọ̀rọ̀ tí í túlé

ojú oró ni ń lékè omi → ojú oró ní í lékè omi

(iii) Pẹ̀lú ibá-ìsẹ̀lẹ̀ ń kejì

*ó ń bá wọn ń lọ → ó ń bá wọn ọn lọ

*ó ń sọ̀rọ̀ ń bọ̀ → ó ń sọ̀rọ̀ ọ́ bọ̀

## 9. Ọ̀rọ̀-ìṣe àti Ọ̀rọ̀-ìṣe ọ̀bọ̀rọ́

Nínú ẹ̀hun yìí, **í** tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe ọ̀bọ̀rọ́ gbọ́dọ̀ gba àrànmọ́ lára fáwẹ́lì tí ó ṣáájú rẹ̀

ó ṣòro i ṣe → ó ṣòro ó ṣe
ó fẹ́rẹ̀ í dé → ó fẹ́rẹ̀ ẹ́ dé

Owólabí (2013:196) ṣàlàyé pé nínú ìhun tí ìsọ̀rí àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe kan (bí àpẹẹrẹ, sèro, bẹ̀rẹ̀sí, mọ̀, pé, fẹ́, tó, wù, yé, dẹ́kun abbl) àti ọ̀rọ̀-ìṣe ọ̀bọ̀rọ́ èyí tí fáwẹ́lì *i* olóhùn òkè máa ń bẹ̀rẹ̀ rẹ̀ bá ti jọ jẹ yọ, àrànmọ́ a máa wáyé báyìí:

i. Bí ọ̀rọ̀-orúkọ (tàbí ọ̀rọ̀-arọ́pò) kò bá jẹ yọ láàrin àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe tí a ń wí yìí àti ọ̀rọ̀-ìṣe ọ̀bọ̀rọ́, fáwẹ́lì (ìparí) àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe náà ni ìró afàrànmọ́, fáwẹ́lì ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe ọ̀bọ̀rọ́ sì ni ìró agbàrànmọ́. Bí àpẹẹrẹ”

Ìwé sòro ikà → ìwé sòroókà
Bọ́lá pẹ́ ídé → Bọ́lá pẹ́ẹ́ dé
ẹmu tó imu → ẹmu tóó mu

ii. Bí ọ̀rọ̀-orúkọ (tàbí ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ) bá jẹ yọ láàrin àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe tí a ń wí yìí àti ọ̀rọ̀-ìṣe ọ̀rọ̀bọ́, fáwẹ́lì (ìparí) ọ̀rọ̀-

orúkọ (tàbí ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ) ni ìró afàrànmọ́, fáwẹ́lì ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe ọ̀bọ̀rọ́ ni ìró agbàrànmọ́. Bí àpẹẹrẹ:

| | | |
|---|---|---|
| wọ́n dẹ́kun ariwo ipa | → | wọ́n dẹ́kun ariwoo pa |
| Bọ́lá mọ ayò íta | → | Bọ́lá mọ ayòó ta |
| ẹmu wù wọ́n ímu | → | ẹmu wù wọ́n-ọ́n mu |

**10. Ẹ̀hun tàbí ọ̀rọ̀ nínú èyí tí a ti ṣe kọ́nsónáǹtì pípajẹ**

Lẹ́yìn tí a bá pa kọ́nsónáǹtì jẹ, àrànmọ́ máa ń wáyé. Ẹ jẹ́ kí a wo àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí

| | | |
|---|---|---|
| lọ sílé | → | lọọlé |
| òtítọ́ | → | òótọ́ |
| ẹ̀rìnméjì | → | ẹ̀ẹ̀mejì |

Commented [O.J73]: tí a ti pa kọ́nsónáǹtì jẹ

### 3.4 Ìhun tí Àrànmọ́ nìkan ti wáyé láàrin Fáwẹ́lì tàbí láàrin Fáwẹ́lì àti Kọ́nsónáǹtì Aránmú Aṣesílébù

A fẹ́ wo díẹ̀ nínú àwọn àlàyé Owólabí tí Bámgbóṣé kò mẹ́nu bà nínú àwọn ìhun tí àrànmọ́ ti lè wáyé.

#### 3.4.1 Ọ̀rọ̀-orúkọ (ìṣẹ̀dá) onírìísí à + ọ̀rọ̀-ìṣe (àpólà-ìṣe) + ì + ọ̀rọ̀-ìṣe (àpólà-ìsé)

Nínú ọ̀rọ̀-orúkọ onírú èyí, fáwẹ́lì ọ̀rọ̀-ìṣe kìíní ni ìró afàrànmọ́, fáwẹ́lì *i* (tí i ṣe atọ́ka ìyísódì) tí ó tẹ̀lé fáwẹ́lì ọ̀rọ̀-ìṣe kìíní yìí sì ni ìró agbàrànmọ́ gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí fi hàn:

| | | |
|---|---|---|
| àjẹìjẹtán | → | àjẹẹ̀jẹtán |
| àlọìdé | → | àlọọ̀dé |
| àsunìdákẹ́ | → | àsunùndákẹ́ |
| àgbọ́nìgbẹ | → | àgbọ́nọ̀ngbẹ |

#### 3.4.2 Ọ̀rọ̀-orúkọ + Ọ̀rọ̀-orúkọ ẹ̀yán onífáwẹ́lì-níbẹ̀rẹ̀

Nínú ìhun yìí, aránmọ́ a máa wáyé ní ìbámu pẹ̀lú àlàkalẹ̀ yìí:

i. Bí ó bá jẹ́ pé fáwẹ́lì *i* ni ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ ẹ̀yán, fáwẹ́lì *i* yìí ni ìró agbàrànmọ́, nígbà tí fáwẹ́lì ìparí ọ̀rọ̀-orúkọ kìíní sì ni ìró afàrànmọ́ gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí

Commented [O.J74]: jẹ́

| | | |
|---|---|---|
| àgbà ìlú | → | àgbààlú |
| ilé ìwé | → | iléèwé |
| iṣẹ́ ipá | → | iṣẹ́ẹ́pá |
| igun ile | → | igununlé |

ii. Bí ó bá jẹ́ pé fáwẹ́lì mìíràn yàtọ̀ sí *i* ni ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ ẹ̀yán, fáwẹ́lì bẹ́ẹ̀ ni ìró afàrànmọ́, nígbà tí fáwẹ́lì ìparí ọ̀rọ̀-orúkọ kìíní sì ni ìró agbàrànmọ́ gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ

| | | |
|---|---|---|
| ẹyẹ àlùkò | → | ẹyaàlùkò |
| ọmọ ẹran | → | ọmẹẹran |
| ará ọ̀run | → | arọ́ọ̀run |

## 4.0 Ìsọnísókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ti wo agbára tí ìró kan ni láti sọ ìró mìíràn di irú ara rẹ̀. A pààlà sáàrín ìró afàrànmọ́ àti ìró agbàrànmọ́. a sì wo ẹ̀yà àrànmọ́ tí ó wà ní èdè Yorùbá; àwọn bí i àrànmọ́wájú, àrànmẹ́yìn, aránmọ́ aláìfòró, aránmọ́ afòró, aránmọ́ kíkún àti aránmọ́ ẹlẹ́bẹ. A kò sài mẹ́nu ba àrànmọ́ ohùn àti àrànmọ́ fáwẹ́lì àti ìhun tí àrànmọ́ fáwẹ́lì ti máa ń wáyé

## 5.0 Ìdánwò Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Dáhùn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí:

1. Pẹ̀lú àpẹẹrẹ ṣàlàyé àwọn ẹ̀yà àrànmọ́ tí ó wà nínú èdè Yorùbá
2. Pààlà sáàrin ìró agbàrànmọ́ àti ìró afàrànmọ́.

## 6.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Bamgbose Ayo (1990) *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ibadan. University Press Limited

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tíìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

# ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ KẸTA

## ÌGBÉSẸ̀ AJẸMÓHÙN

**1.0 Ìfáárà**

Lára ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì tí ó máa ń wáyé nígbà tí a bá ń fọ̀ tàbí sọ̀rọ̀ ni ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìyípada ohùn àti ìhun tí wọ́n ti lè wáyé nìkan ni a ó wò. A ó sọ ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò di ìdánilẹ́kọ̀ọ́ karùn-ún.

**2. 0 Èròǹgbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè:

i. Fún ìyípadà ohùn ní oríkì.

ii. Ṣàlàyé ìhun tí ìyípadà ohùn ti máa ń wáyé

**2.1 Ìdánwo Ìbèrè Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

i. Fún Ìyípadà ohùn ní oríkì?

ii. Ṣe àlàyé pẹ̀lú àpẹẹrẹ ìhun tí ìyípadà ohun ti máa ń wáyé

**3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọjá, a mẹ́nu ba àrànmọ́ ohùn. Àrànmọ́ ohùn yìí jẹ́ ọ̀kan lára ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn. Lára àwọn ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn mìíràn ni ìyípadà ohùn, ìsóhùnnípò, ìgbohùnnípò abbl. gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe sọ sa á jú, ìyípadà ohùn àti àwọn ìhun tí wọ́n ti máa ń wáyé nìkan ni a í wò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. A ó sọ àwọn ìgbésẹ̀ tó kù di ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó ń bọ̀. Kí wá ni Ìyípadà ohùn? Èyí ni fífi ohùn kan rọ́pò ohùn òmíràn nínú ìsọ (wo Owólabí 2013:126).

## 3.1 Ìyípadà ohùn

Ìyípadà ohùn ni kí ohùn ọ̀rọ̀ kan yìí padà kúrò gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀ sí ohùn mìíràn nígbà tí a bá lò ó nínú ẹ̀hun. Èyí túmọ̀ sí wí pé, bí ọ̀rọ̀ bá dá wà láì lò ó nínú gbólóhùn, irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ ni ohùn àdámọ́ rẹ̀. Bí irú ohùn àdámọ́ yìí bá yí padà bí a bá lo irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ ní gbólóhùn, a ó sọ pé ìyípadà ohùn ti wáyé. Ohun tí o fojú hande ni pé ohùn máa ń yí padà bí a bá ń fọ̀ tàbí sọ̀rọ̀. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

Commented [O.J75]: hànde

ìyà *ìyà jẹ mi → ìyá jẹ mí

rà *Mo rà bàtà → Mo ra bàtà

Bí a bá wo àpẹẹrẹ méjéèjì òkè yìí, a ó ṣàkíyèsí pé ohùn ọ̀rọ̀ bí i **ìyà** ní ohùn ìsàlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀ ṣùgbọ́n nígbà tí a lò ó nínú ẹ̀hun ohùn náà yí padà sí ohùn ìsàlẹ̀ àti ohùn òkè (**ìyá**). Bẹ́ẹ̀ náà ni ọ̀rọ̀ rí fún àpẹẹrẹ kejì; **rà** tí ó ní ohùn ìsàlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀ yí padà nínú ẹ̀hun sí ohùn ààrín (**ra**). Àwọn àpẹẹrẹ oníràwọ̀ fi hàn pé, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ọ̀rọ̀ tí a fi ṣàpẹẹrẹ yìí ni ohùn ìdámọ́ wọn nínú ẹ̀hun, sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí elédè, a kìí sọ bẹ́ẹ̀. Ìyẹn ni pé, bí a bá ń fọ̀ tàbí sọ̀rọ̀, ìwọ́hùn sókè sódò máa ń ṣẹlẹ̀ yàtọ̀ sí ìgbà tí ọ̀rọ̀ bá dá wà tàbí dá dúró. Irú ìyípadà báyìí ni a fẹ́ yẹ̀wò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí; òun sì ni à ń pè ní ìyípadà ohùn. Oun tí ó kàn báyìí ni láti wo ìhun tí ìyídapà ohùn ti máa ń wáyé

Commented [O.J76]: òkè

Commented [O.J77]: tí ó gbàràwọ̀

Commented [O.J78]: síbẹ̀

### 3.1.1 Ìhun tí Ìyípadà Ohùn ti Máa ń Wáyé

Owólabí (2013:126-132) ṣàlàyé ìhun gírámà mẹ́sàn-án tí ìyípadà ohùn ti máa ń wáyé. A ó wo ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn báyìí:

#### 3.1.1.1 Ọ̀rọ̀-Ìṣe + Ọ̀rọ̀-Orúkọ Àbọ̀

Bí ọ̀rọ̀-ìṣe oní sílébù kan bá ni ohùn ìsàlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀ bá gba ọ̀rọ̀ orúkọ gẹ́gẹ́ bí àbọ̀ rẹ̀ tààrà, ìyẹn ni pé, bí ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí àpólà orúkọ bá tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe onísílébù kà tààrà gẹ́gẹ́ bí i àbọ̀ rẹ̀; irú ọ̀rọ̀-ìṣe bẹ́ẹ̀ yóó yìí ohùn ìsàlẹ̀ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀ padà sí ohùn ààrín.

Commented [O.J79]: tí ó sì gba ọ̀rọ̀ orúkọ gẹ́gẹ́ bí àbọ̀ tààrà

Commented [O.J80]: ohùn ìsàlẹ̀ àdámọ́ rẹ̀

sè (cook): sè ẹ̀wà → se ẹ̀wà
jò (leak): jò omi → jo omi
sùn (sleep): sùn ilé → sun ilé
nà (beat): nà Fúnmi → na Fúnmi
sà (pick): sà owó → sa owó

Bí irú ìyípadà ohùn yìí kò bá wáyé, ó lè dàbí ẹni pé, ẹni tí ó pe irú ìpèdè bẹ́ẹ̀ kò gbọ́ èdè tàbí kí ó wa ìtumọ̀ mìíran bo ìpèdè bẹ́ẹ̀ lọ́rùn. Ìtumọ̀ àkọ́kọ́ tí yóó wá sí ènìyàn lọ́kàn ni pé, ẹni náà ń pàṣẹ. Irú àṣẹ bẹ́ẹ̀ sì lè máa pa ni lẹ́rìn-ín, nítorí pé, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a lè sọ bẹ́ẹ̀, síbẹ̀ẹ̀ kò tọ̀nà nínú àwọn ìsọ Yorùbá. Bí àpẹẹrẹ, a lè sọ pé:

Commented [O.J81]: "kí ó wa ìtumọ̀ mìíran bo ìpèdè bẹ́ẹ̀ lọ́rùn" Báwo?

sùn, ọmọ mi

ṣùgbọ́n, a kò lè sọ pé *sùn ilé* gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà lókè nítorí pé, ilé kìí sùn. Síbẹ̀ *sun ilé* náà jẹ́ gbólóhùn onípọ́nna. Ìdí ni pé, ìyàtọ̀ wà nínú *sùn* àti *sun*. Ní báyìí tí ìyípadà ohùn ti sọ *sùn* di *sun*, sàkáni ìpèdè ni yóó sọ irú ìtumọ̀ tí a ó wà bọ *sun* lọ́rùn.

Mo sun ilé

Lè túmọ̀ sí pé *mo sùn sí ilé* tàbí *mo dáná sún ilé*.

A nílò láti jẹ́ kí a mọ ìtumọ̀ onípọ́nna tí irú ìyípadà ohùn báyìí lè mú dáni. Ó yẹ kí a yànnánná rẹ̀ dáadáa ìpèdè aṣeégbà ni àwa onímọ̀ ẹ̀dá èdè máa ń fúnka mọ́ jù lọ.

Commented [O.J82]: pé ìpèdè

### 3.1.1.2 Ọ̀rọ̀ Arọ́pò Orúkọ Olùwà + Ẹ̀rún Ọ̀rọ̀ Ìṣe 'ń'

Tí ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ ẹni kínní tàbí ẹnì kejì tí a lò gẹ́gẹ́ bí olùwà gbólóhùn bá jẹyọ saájú ẹ̀rún ọ̀rọ̀-ìṣe, tí a mọ̀ sí ibá ìsẹ̀lẹ̀ àìṣetán atẹ́rẹẹ 'ń' báyìí; ohùn olùwà náà lè yí padà tàbí kí ó má yí padà

Commented [O.J83]: arọ́pò-orúkọ

mo → mò ń bọ̀

tàbí

mo ń bọ̀

a → à ń lọ ata

tàbí

a ń lọ ata

### 3.1.1.3 Ọ̀rọ̀-Ìṣe + Ọ̀rọ̀ Arọ́pò Orúkọ Àbọ̀

Tí ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ tí a lò gẹ́gẹ́ bí abọ̀ fún ọ̀rọ̀-ìṣe bá ní ohùn òkè tí ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó jẹyọ saájú rẹ̀ bá ní ohùn ìsàlẹ̀ tàbí ohùn àárín gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀.

Funkẹ́ kọ̀ wá
Túnráyọ̀ yọ̀ wọ́n
Kẹmi jọ mí

Ṣùgbọ́n bí ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó jẹyọ saájú ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ àbọ̀ yìí bá ni ohùn òkè gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀, ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ àbọ̀ yìí yóó ni ohun àárín.

Olùkọ́ kọ́ wa
Fúnkẹ́ bú wọn
Tunráyọ̀ kọ́ mi

#### 3.1.1.4 Ẹ̀rún Ọ̀rọ̀-Ìṣe 'ń' + Ọ̀rọ̀-Ìṣe (pẹ̀lú àbọ̀) + Ọ̀rọ̀-Ìṣe

Nínú gbólóhùn, ni ibi tí ẹ̀rún ọ̀rọ̀-ìṣe tí a pè ní atọ́ka ìbá-ìṣẹ̀lẹ̀ atẹ́rẹrẹ 'ń' àti ọ̀rọ̀-ìṣe méjì ti jẹyọ ní tẹ̀léǹtẹ̀lé, a lè fa fáwẹ́lì ọ̀rọ̀-ìṣe kìíní tàbí àbọ̀ rẹ̀ gùn pẹ̀lú ohùn òkè tàbí kí á má fà á gùn bí a bá fẹ́

Adé ń bú wa á lọ

tàbí

Adé ń bú wa lọ

Ọbẹ̀ náà ṣe é jẹ

tàbí

Ọbẹ̀ náà ṣe jẹ

Commented [O.J84]: Ẹ̀yí kò tọ̀nà tàbí bétí mu o

#### 3.1.1.5 Olùwà + Kókó-Gbólóhùn

Bí sílébù ìparí àpólà orúkọ olùwà bá ni ohùn àárín gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀, tí ohùn òkè kò bá sì jẹyọ ṣáájú ohùn àárín yìí tààrà, tàbí tí sílébù tí ó parí àpólà orúkọ olùwà bá ní ohùn ìsàlẹ̀, tí ohùn ìsàlẹ̀ mìíràn sì jẹyọ ṣáájú ohùn ìsàlẹ̀ yìí, a ó yí ohùn àárín tàbí ohùn ìsàlẹ̀ ìparí àpólà orúkọ bẹ́ẹ̀ padà di ohùn òkè nínú àwọn gbólóhùn kan tí wọ́n ní ìhun olùwà àti kókó gbólóhùn

ẹlẹ́mu mi → ẹlẹ́mu mí tà

Abọ́ ẹ̀wà → abọ́ ẹ̀wá sonù

Òjò → òjó rọ̀ púpọ̀

#### 3.1.1.6 Ọ̀rọ̀ Arọ́pò Orúkọ Olùwà + Ìsọ̀rí àwọn Wúnrẹ̀n kan

Tí ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ ẹnì kẹta ọ̀pọ̀ olùwà *Wọ́n* ba jẹyọ ṣáájú àwọn wúnrẹ̀n kan tààrà (àwọn wúnrẹ̀n bí i: ìbá, ìbáà, yóó, kò/ò, kí) ohùn òkè tí i ṣe ohùn àdámọ́ rẹ̀ yóó yí padà sí ohùn ààrín

Wọ́n → { wọn ìbáà lọ
wọn yóó lọ
wọn ò lọ
wọn kìí lọ }

#### 3.1.1.7 Ọ̀rọ̀ Arọ́pò Orúkọ Olùwà + Wúnrẹ̀n 'a'

Bí ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ oluwà ẹnì kìíní tàbí ẹnì kejì ọ̀pọ̀ olùwà bá jẹyọ tààrà ṣáájú wúnrẹ̀n 'á' tí ó ń ṣiṣẹ́ àsìkò ọjọ́ iwájú, ohùn ààrín ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ yìí lè yí padà di ohùn ìsàlẹ̀ tàbí kí ó máà yí padà.

a → a á lọ

tàbí

à á lọ

ẹ → ẹ ẹ́ lọ

tàbí

ẹ̀ ẹ́ lọ

Ó yẹ kí a fi kún un pé àrànmọ́ ṣẹlẹ̀ nínú àpẹẹrẹ kejì níbí. Atọ́ka àsìkò ọjọ́ iwájú 'á' gbà àrànmọ́ àbùdá ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ olùwà ẹnì kejì ọ̀pọ̀ láti di irú rẹ̀.

Commented [O.J85]: Yọ ọ́ kúrò.

Commented [O.J86]: gba

#### 3.1.1.8 Ọ̀rọ̀ Orúkọ + Ẹ̀yán

Bí àwọn ẹ̀yán kan bá yán ọ̀rọ̀ orúkọ, ìyípadà ohun a máa wáyé gẹ́gẹ́ bí a ó ṣe fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí láti inú àlàyé Owólabí (2013:129-130).

Bí ẹ̀yán bá jẹ́ ẹ̀yán ajórúkọ tí ó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú kọ́nsónáàtì tàbí ọ̀rọ̀ arópọ̀-orúkọ kan, bí sílébù ìparí ọ̀rọ̀ orúkọ tí ẹ̀yán ń yán kò bá ni ohùn àárín lórí, a gbọdọ̀ fa fáwẹ́lì sílébù ìparí ọ̀rọ̀ orúkọ tí ẹ̀yán ń yán gùn pẹ̀lú ohùn àárín.

ọkọ̀ → ọkọ̀ọ Dúdú

bàtà → bàtàa Bọ́sẹ̀

Bí sílébù ọ̀rọ̀ orúkọ tí ẹ̀yán ń yán bá ni ohùn àárín lórí tàbí tí ẹ̀yán bá jẹ́ ọ̀rọ̀ orúkọ tí ó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú fawẹ́lì, a lè fa fáwẹ́lì sílébù ìparí ọ̀rọ̀ orúkọ bẹ́ẹ̀ gùn pẹ̀lú ohùn àárín tàbí kí a má fà á gùn

àwo → àwoo Dàda

tàbí

àwo Dàda

ó ṣe é ṣe kí irú ìgbésẹ̀ yìí mú pọ́nna dán ni tàbí iyè méjì, bí ọ̀rọ̀ bá rí báyìí a gbọdọ̀ ṣe ìfàgùn sílébù ọ̀rọ̀ orúkọ. Wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí

ẹran → ẹran an dúdú

tàbí

ẹran dúdú

oun tí ó fojú hàn níbí ni pé, orúkọ ẹni tí ó ni ẹran akọ́kọ́ ni dúdú nítorí náà dúdú jẹ́ ẹ̀yán ajórúkọ nígbà tí dúdú kejì tí kò ní ìfàgùn sílébù jẹ́

Commented [O.J87]: Yọ ọ́ kúrò.

Commented [O.J88]: dání

Commented [O.J89]: àfàgùn

ọ̀rọ̀ àpèjúwe tí ó ń sọ irú àwọ̀ tí ẹran kèjí ní. Nítorí náà, dúdú nínú gbólóhùn kejì jẹ́ ẹ̀yán asàpèjúwe. Ìfàgùn báyìí ni Bámgbóṣé (1990) fi ṣàlàyé dídá ọ̀rọ̀ orúkọ mọ̀.

Bí ẹ̀yán bá jẹ́ gbólóhùn àsọdorúkọ, a lè fa fáwẹ́lì sílébù ìparí ọ̀rọ̀-orúkọ tí ẹ̀yán yìí ń yán gùn pẹ̀lú ohùn àárín tàbí kí a má fà á gùn

ayọ̀ → Mo yọ ayọ̀ọ pé Bọ́sẹ̀ bí ọmọ

tàbí

Mo yọ ayọ̀ pé Bọ́sẹ̀ bí ọmọ

Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe fi ojú hàn, a ó ṣe akìyèsí pé ìtumọ̀ gbólóhùn tí ìfàgùn tí wáyé yàtọ̀ sí ti èyí tí ìfàgùn fáwẹ́lì bẹ́ẹ̀ kò ti wáyé.

Bí sílébù ìparí ọ̀rọ̀ orúkọ tí ẹ̀yán ń yán bá ni ohùn ìsàlẹ̀ èyí tí ohun ìsàlẹ̀ mìíràn saájú rẹ̀, bí ẹ̀yán bá sì jẹ́ ọ̀rọ̀ orúkọ tí fáwẹ́lì olóhùn àárín bẹ̀rẹ̀ rẹ̀, ohùn sílébù ìparí ọ̀rọ̀ orúkọ yóò di ohùn àárín

èdè → ède ewì

ọ̀rọ̀ → ọ̀rọ ọmọ

ó yẹ kí a fi kún un pé àrànmọ̀ ohùn ni ó ṣẹlẹ̀ nínú àpẹẹrẹ òkè yìí

Èrò Awóbùlúyì lórì èyí yàtọ̀. Ó ṣàlàyé pé èrò àwọn onímọ̀ ìsàajú kò sòótọ́ lórí kókó yìí. Ó gbé àríyànjiyàn rẹ̀ lé orí ìmọ̀ tí ó ti inú ẹ̀ka èdè wá (wo Awóbùlúyì 2008:Afikun III). Ó ní dípò

ìwé  e Kọ́lá

ìlú uKánò

ohun tí a ó rí nínú ẹ̀kan èdè Èkìtì àti Mọ̀bà ni:

ìwé iKọ́lá

ùlú iKánò

ẹ̀kọ́ tí a wá rí kọ́ nínú àlàyé láti inú ẹ̀ka èdè yìí ni pé, fáwẹ́lì ni ó máa ń bẹ̀rẹ̀ gbogbo ọ̀rọ̀-orúkọ tí ó ń ṣiṣẹ́ ẹ̀yán, gẹ́gẹ́ bí a ti rí *Kọ́lá* àti *Kánò* nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí. Awóbùlúyì wá là á mọ́lẹ̀ pé, ọ̀rọ̀-orúkọ aṣẹ̀yán tí kò bá ní fáwẹ́lì tirẹ̀ ní ìbẹ̀rẹ̀ tẹ́lẹ̀ gbọ́dọ̀ gba fáwẹ́lì *i* aláfibọ̀ olóhùn-àárín, kí ó ba lè ní ìrísí ọ̀rọ̀-orúkọ inú èdè Yorùbá. Ó sì pọdandan fún fáwẹ́lì *i* aláfibọ̀ yìí láti mú ìrísí fáwẹ́lìkífáwẹ́lì tí ó bá tì í gbọ̀ngbọ̀n-gbọ̀n ní ẹ̀gbẹ́ òsì nínú èdè Yorùbá àjùmọ̀lò.

**Commented [O.J90]:** Ṣé ẹ̀yin wá gba èyí gbọ́? Tó bá rí bẹ́ẹ̀, kí ló fà á tó jẹ́ pé kìkì ìgbà tí ọ̀rọ̀-orúkọ bá wà ní ipò ẹ̀yán ló gbọ́dọ̀ gba àfibọ̀ fáwẹ́lì àpàpàǹdodo? Kí ló dé tí kò sí "Mo lọ sí Ikánò ní àná TÀBÍ Ikánò tóbi ju Ìbàdàn lọ." Ṣé kì í ṣe ẹ̀kọ́ aṣinilọ́nà nìyí?

### 3.1.1.9 Gbólóhùn Alátẹnumọ́

Gbólóhùn kan lè di alátẹnumọ́ nípa síṣe ìyípadà ohùn bí i:

Bí sílébù ìparí gbólóhùn bá ni ohùn òkè tàbí ohùn àárín gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀, láti sọ irú gbólóhùn bẹ́ẹ̀ di gbólóhùn alátẹnumọ́, a ó fa fáwẹ́lì ìparí gbólóhùn náà gùn pẹ̀lú ohùn ìsàlẹ̀

Adé fà mí → Adé fà míì

Bọ́lá ga →Bọ́lá gaà

Bí sílébì ìparí gbólóhùn bẹ́ẹ̀ bá ni ohùn ìsàlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀, a le sọ gbólóhùn bẹ́ẹ̀ di alátẹnumọ́ fífa fáwẹ́lì sílébù ìparí gbólóhùn ọ̀hún gùn pẹ̀lú ohùn àárín

Ọbẹ̀ náà sàn → Ọbẹ̀ náà sàn an

Adé gbá Dàpọ̀ → Adé gbá Dàpọ̀ọ

Ó yẹ kí ó di mímọ̀ pé, gbólóhùn alátẹnumọ́ ní ibi tí ìyípadà ohùn ti wáyé yìí ni a máa ń lò nígbà tí a bá ń já ẹnìyàn lẹ́gọ tàbí bí ènìyàn bá ń bínú sọ̀rọ̀ (rojọ́)

**4.0 Ìsọnísókí**

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti mẹ́nu ba ìyípadà ohùn. A ṣàlàyé pé, ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan ni ó máa ń ni ohùn àdámọ̀ rẹ̀ nígbà tí ó bá dá wà tàbí dá dúró. Bí ohùn àdámọ̀ yìí bá wá yí padà nígbà tí a bá lo irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ nínú ẹ̀hun, a ó sọ pé ìyípadà ohùn ti wáyé. A tún wo ìhun tí àwọn ìyípadà ohùn yìí ti máa ń wáyé. A sì ṣe àwílé lórí àwọn ti ó yẹ, bẹ́ẹ̀ ni a ṣe àfihàn èrò àwọn onímọ̀ tí ó yàtọ̀ sí àwọn díẹ̀ nínú wọn.

**5.0 Ìdánwò Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

Dáhùn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí

i. Fún Ìyípadà ohùn ní oríkì?

ii. Ṣe àlàyé pẹ̀lú àpẹẹrẹ ìhun tí ìyípadà ohun ti máa ń wáyé

**6.0 Àtòjọ Ìwé tí a lò**


Awóbùlúyì Ọládélé (2008) *Ẹ̀kọ́ Ìsẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*. Akure. Montem Paperbacks

Awóbùlúyì Ọládélé (2013) *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*. Osogbo. Atman Limited

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tíìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

## ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ KẸRIN
## ÌGBÉSẸ̀ AJẸMÓHÙN

### 1.0 Ìfáárà

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọjá ni a ti bẹ̀rẹ̀ sí jíròrò lórí kókó yìí. A ti sọ̀rọ̀ lórí ìyípadà ohùn, a sì wo ìhun mẹ́sàn-án tí Owólabí ti ní ìyípadà ohìn ti lè wáyé. A ṣe àwílé níbi tí ó ti yẹ, bẹ́ẹ̀ ni a fi èrò àwọn onímọ̀ mìíràn bí Awóbùlúyì hà lórí àwọn àlàyé kan. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ó tẹ̀síwájú láti wo ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò. A kò ní sàì mẹ́nu ba lílo ohùn àti èrò àwọn onímọ̀ nípa rẹ̀.

### 2.0 Èròǹgbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè:

i. ṣe àlàyé ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò

ii. pààlà sáarin lílo ohùn fún ìtumọ̀ àdámọ́ àti ìtumọ ijẹmọ́ gírámà

**2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

Dáhùn ìbèèrè ìsàlẹ̀ yìí

i. ṣe àlàyé ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò

ii. pààlà sáarin lílo ohùn fún ìtumọ̀ àdámọ́ àti ìtumọ ijẹmọ́ gírámà

**3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ, inú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọjá ni a ti bẹ̀rẹ̀ ìjíròrò yìí. A ti wo ìyípadà ohùn àti àwọn ìhun tí wọ́n ti lè wáyé. Níbí ni a ó ti wo ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò.

**3.1 Isóhùnnípò àti Ìgbohùnnípò**

Ìsóhùnnípò ni gbígbé ohùn kan láti ipò tí ó wà ló sí ipò mìíràn (ì-sí-ohùn-ní-ipò). Nígbà tí ìgbohùnnípò jẹ́ fífi ayè gba ohun tí a sí nípò ní ipò mìíràn (ì-gba-ohùn-ní-ipò). Àwọn m''ejéèjì fi ara kọ́ ara wọn. Wọ́n sábá jọ máa ń wáyé ni. Amọ́ sá, ó ṣe é ṣe kí a rí isóhùnnípò nikan láì jẹ́ pé ìgbohùnnípò wáyé ṣùgbọ́n ìgbohùnnípò kò lè wáyé láì sí ìsóhùnnípò. Owólabí (2013) fún wa ni àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí:

| | (1) | (2) | (3) |
|---|---|---|---|
| i. | gbé àga | gb´àga | gbága |
| ii. | kọ ìwé | kọ `wé | kọ̀wé |
| iii. | aya-kí-aya | aya-k´-aya | ayakáya |
| iv. | pa ìgbín | pa `gbín | pàgbín |
| v. | wọ́n wà nílé | wọ́n wà n´lé | wọ́n wà ńlé |
| vi. | èmi ni mo lọ | emi n´mo lọ | emi m mo lọ |

Àwọn ọ̀rọ̀ abẹ́ (1) jẹ́ àwọn ọ̀rọ̀ pẹ̀lú ohùn àdámọ́ wọn. Láti ara wọn sì ni a ó ti mọ ohùn tí a ó sí nípò. Ìgbésẹ̀ (2) fi hàn pé a pa fáwẹ́lì tí a ó si ohùn rẹ̀ ipò jẹ, èyí tí ó

mí kí ohùn náà máa léfòó. Ìyẹn ni pé, ohùn náà kò ní fáwẹ́lì tí ó gbà á nítẹ̀ẹ́. Níwọ̀n ìgbà tí èdè Yorùbá kò sì fàyè gba ohùn aléfòó, a ní láti sí i nípò lọ sí ibi tí àyè yóó ti gbà á. Ní ìgbá tí ìgbésẹ̀ (3) fi hàn pé ohùn aléfòó tí ó jẹ́ àbájáde ìgbésẹ̀ (2) gbà ipò ohùn mìíràn. Ní àpẹẹrẹ (i) ohùn aléfòó sí ohùn ìsàlẹ̀ fáwẹ́lì tí ó bẹ̀rẹ̀ *àga* nípò, ó sì gba ipò rẹ̀. Ṣùgbọ́n ní àpẹẹrẹ (ii) ohùn aléfòó gba ipò ohùn tí ó saájú rẹ̀. Ó yẹ kí a fi kún un pé ohùn tí ohùn aléfòó gba ipò rẹ̀ yóó pòórá. Ní àpẹẹrẹ (v-vi) a sí ohùn nípò lọ sí orí kọ́nsónáàtì tí kò ní ohùn kankan tẹ́lẹ̀ ṣùgbọ́n tí a sọ di Kọ́nsónáǹtì aránmú aṣesílébù kí ó ba à lè gba ohùn. Ìyẹn túmọ̀ sí pé, nínú àpẹẹrẹ yìí ìsóhùnnípò nìkan ló wáyé, ìgbésẹ̀ ìgbohùnnípò kà wáyé.

Ohun kan pàtàkì tí a gbọdọ̀ dì mú pẹ̀lú àlàyé òkè yìí ni pé, lẹ́yìn ìpajẹ ni ìgbésẹ̀ ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò máa ń wáyé. Èyí sì ni ìyàtọ̀ kan pàtàkì láàrin ìgbésẹ̀ méjéèjì yìí àti ìyípadà ohùn. Kò di dandan kí ìpajẹ fáwẹ́lì wáyé kí ìyípadà ohùn tó wáyé.

### 3.2 Lílo Ohùn

Ọ̀nà méjì ni Yorùbá ń gbà lo ohùn:

Fífi ìtumọ̀ àdámọ́ hàn

Fífi ìtumọ̀ gírámà hàn

#### 3.2.1 Fífi Ìtumọ̀ Àdámọ́ Hàn

A máa ń lo ohùn láti fi ìyàtọ̀ itumọ̀ ọ̀rọ̀ tàbí wúnrẹ̀n tí kọ́nsónáǹtì àti fáwẹ́lì wọ́n jẹ́ ìkan-ùn hàn. Apẹẹrẹ

| | | |
|---|---|---|
| bú | gbá | igbá |
| bù | gbà | igbà |

bu gba igba

ìgbá

ìgbà

Bí a bá fi ohùn kan rọ́pò èkejì yóó fa ìyàtọ̀ itumọ̀ fún àwọn ọ̀rọ̀ òkè yìí. Ohùn ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí wọ́n ní ni ó jẹ́ kí á mọ̀ pé wọ́n jẹ́ ọ̀rọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ pẹ̀lú ìtumọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Nítorí náà, a kò lè fi ohun ọ̀rọ̀ kan rapò èkejì láì jẹ́ pé a si ìpàrọ̀ ìtumọ̀ náà.

### 3.2.2 Fífi Ìtumọ̀ Gírámà Hàn

Ohùn tún ṣe é lò láti fi ìyàtọ̀ ẹ̀hun gírámà kan hàn sí òmíràn.

**Commented [O.J91]:** ẹ̀hun gírámà kan sí òmíràn hàn ???

i. Ayìẹ funfun

ii. Adìẹ́ funfun

Ìyàtọ̀ wo ni ó wà nínú ẹ́hun gírámà òkè méjéèjì yìí? Nígbà tí àkọ́kọ́ jẹ́ àpólà-orúkọ, ní ibi tí a ti rí ọ̀rọ̀ orukọ (Adìẹ) àti ẹ̀yán rẹ̀ (ẹ̀yán asàpèjúwe). Ìkejì jẹ́ odidi gbólóhùn ní ibi tí a ti rí Àpólà orúkọ (Adìẹ) àti kókó gbólóhùn (funfun). Ohun tí ó fà ìyàtọ̀ yìí gan ni ohùn. Ohùn sílébù tí ó parí adìẹ nínú àpẹẹrẹ méjéèjì yàtọ̀, èyí ni ó sì fa ìyàtọ̀ ẹ̀hun gírámpa wọn.

**Commented [O.J92]:** Èyí kì í ṣe odindi gbólóhùn.

### 3.3 Èrò Oyèbádé

Oyèbádé (2001) ṣàlàyé pé bí ìró ohùn méjì bá padé ní ààlà mọ́fíìmù, èyí tí ó bá lágbara jù ni yóó dúró, tí èkejì yóó sì pòórá tàbí kí ó sún lọ sí ibòmìíràn. Bí O ba dúró fún òkè, tí A dúró fún àárín, tí I sì dúró fún ìsàlẹ̀; àpẹẹrẹ tí Oyèbádé fún wa ni:

i. O + I → O: kó àre→káre

ii. O + A →O: ní ọ̀pá →lọ́pàá

iii. A + A → A: ta ayò → tayò

iv. A + I → I: jẹ ìgbágbùn →jẹ̀gbágùn

v. I + I → I: bà ẹ̀rù → bẹ̀rù

vi. I + A → A: rà ilẹ̀ → ralẹ̀

Ó ṣàlàyé pé ìdí tí àpẹẹrẹ vi rí bẹ́ẹ̀ ni pé, èdè Yorùbá ní òfin tí ó ń sọ ohùn ìsàlẹ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe di ohùn ààrín tí ó bá gba ọ̀rọ̀-orúkọ gẹ́gẹ́ ní ipò àbọ̀ gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn nínú àlàyé Owólabí (2013) nípa ìhun tí ìyípadà ohùn ti lè wáyé. Oyèbádé fi kún àlàyé rẹ̀ pé a kò rí O + O, A + O, àti I + O nítorí pé èdè Yorùbá kò fi àyè gba kí ọ̀rọ̀ tí fáwẹ́lì bẹ̀rẹ̀ rẹ̀ ní ohùn òkè ní ìbẹ̀rẹ̀.

Commented [O.J93]: fi rí

**4.0 Ìsọnísókí**

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a sọ̀rọ̀ nípa ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn pàápàá ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò. A ṣàlàyé pé ìsóhùnnípò kò lè wáyé láì sí ìgbohùnnípò ṣùgbọ́n ó ṣe é ṣe kí ìgbohùnnípò wáyé láì jẹ́ pé ìsóhùnnípò wáyé. A kò sài sọ̀rọ̀ lórí lílo ohùn. A pín eléyìí sí ọ̀nà méjì: fífi ìtumọ̀ àdámọ́ hàn àti fífi ìtumọ̀ gírámà hàn. Àwọn ọ̀rọ̀ tí wọ́n ní kọ́nsónáǹtì àti fáwẹ́lì kan náà máa ń ní ìtumọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ nípa ohùn ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí wọ́n ní. Ní ìgbà tí ìyàtọ̀ ohùn náà lè fa ìyàtọ̀ ẹ̀hun gírámà gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí

**5.0 Ìdánwò Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

Dáhùn àwọn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí:

i. ṣe àlàyé ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò

ii. pààlà sáarin lílo ohùn fún ìtumọ̀ àdámọ́ àti ìtumọ ijẹmọ́ gírámà

**6.0 Ìwé Ìtọ́kasí**


Bámgbóṣé Ayọ̀ (1990) *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ibadan, University Press Ltd

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tíìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

Oyèbádé Francis (2001) Ìgbẹ́sẹ̀ àti Ìlànà Fonọ́lọ́jì Èdè Yorùbá nínú *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá-Èdè, Lítírésọ̀ àti Àṣà*. Olóòtú: Bádé Àjàyí

**MÓÒDÙ KEJÌ**

**ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ ÌKÍNNÍ: ÀǸKÓÒ FÁWẸ́LÌ**

## 1.0 Ìfáárà

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí tóó dá lórí àǹkóò fáwẹ́lì. Báwo ni àwọn fáwẹ́lì kan ṣe jọ máa ń bá ara wọn ṣiṣẹ́ tí wọn kìí bá àwọn mìíràn ṣiṣẹ́; kín ni ó fì fà á? Ìbéèrè yìí ṣe pàtàkì púpọ̀, ìdáhùn rẹ̀ sì ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí dá lé lórí. Ohun mìíràn ni pé, kín ni ó ya àǹkóò fáwẹ́lì sọ́tọ̀ sí ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì? Gbogbo eléyìí ni a ó yẹ̀wò ti a ó sì mú àpẹẹrẹ wá láti inú olórí ẹ̀kà èdè, ẹ̀ka èdè àárin gbùngbùn Yorùbá àti àwọn èdè mìíràn láti dáhùn ìbéèrè tí àwọn kan máa ń bèèrè bí Yorùbá bá ni ohun tí à ń pè ní àǹkóò fáwẹ́lì.

## 2.0 Èròǹgbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, akẹ́kọ̀ọ́ yóó le:

i. Sọ bí Yorùbá bá ni àǹkóò fáwẹ́lì pẹ̀lú àpẹẹrẹ láti inú Yorùba àjùmọ̀lò àti ẹ̀ka èdè

ii. Ṣe àlàyé àǹkóò fáwẹ́lì oníwájú àti ẹ̀yìn

### 2.1 Ìdánwò ìbẹ̀rẹ̀ ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Dáhùn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí

i. Sọ bí Yorùbá bá ni àǹkóò fáwẹ́lì pẹ̀lú àpẹẹrẹ láti inú Yorùba àjùmọ̀lò àti ẹ̀ka èdè

ii. Ṣe àlàyé àǹkóò fáwẹ́lì oníwájú àti ẹ̀yìn

Commented [O.J94]: i. . Ǹjẹ́ Yorùbá ní àǹkóò fáwẹ́lì? Fún wa ní àpẹẹrẹ láti inú Yorùba àjùmọ̀lò àti ẹ̀ka èdè rẹ̀.

Commented [O.J95]: alábùdá iwájú àti alábùdá ẹ̀yìn

## 3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Bámgbóṣé (1990:28) ní àjùmọ̀rìn fáwẹ́lì ní ọ̀wọ̀ọ̀wọ́ ni à ń pè ní àǹkóò fáwẹ́lì. Ó fún wa ní àpẹẹrẹ bí i: *ewé*, *owó*, *ọjọ́*, *ẹ̀fọ́*, ṣùgbọ́n a kò lè rí ọ̀rọ̀ bí i **ojọ́*, *èfọ́*, *ewẹ́*, *owọ́*. Bámgbóṣé ni èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé ìró fáwẹ́lì *e* àti *o* ń bá ara wọn rìn nínú ọ̀wọ́ kan náà, wọn kò sì lè bá ìró fáwẹ́lì *ẹ* àti *ọ* rìn nítorí pè, àwọn náà wà ní ọ̀wọ́ mìíràn.

Commented [O.J96]: Ó dà bí ẹni pé "sọ pé" já gaara ju "ní" lọ.

Owólabí (2013:145) ni àǹkóò fáwẹ́lì jẹ ẹ̀yà ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì ní ibi ti gbogbo àwọn fáweẹ́lì tí wọ́n jẹ́ yọ tẹ̀lé awa wọn nínú ọ̀rọ̀ tàbí ìsọ (ọlópọ̀ sílébù) ti maa ń jọ ní àbùdá kan náà. Èyí sì ni ìyàtọ̀ pàtàkì tí ó wà láàrin àǹkóò fáwẹ́lì àti ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì.

Orísìí bátànì àǹkóò fáwẹ́lì méjì ni ó wà nínú èdè Yorùbá (Bámgbóṣé 1990:24). Bátànì kìíní jẹ mọ́ fifẹ tàbí àìfẹ káà-ọ̀fun; nígbà tí bátánì kejì sì jẹ mọ́ fáwẹ́lì iwájú àti ẹ̀yìn.

Commented [O.J97]: Ṣé kò sí àbùdá [ÒKÈ] àti [ODÒ] náà?

### 3.1 Àǹkóò fáwẹ́lì oní-káà-ọ̀fun

Bí a bá fẹ káà-ọ̀fun nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀, ìsọ̀rí tàbí irú ọ̀wọ́ fáwẹ́lì kan ni yóó máa jẹ yọ. Ẹ̀wẹ̀, bí a ò bá fẹ káà-ọ̀fun, orísìí tàbí irú ọ̀wọ́ fáwẹ́lì mìíràn ni a ó máa pè. Àpẹẹrẹ àwọn èdè tí ó ní irú àǹkóò

fáwẹ̀lì yìí ni èdè Twi, èdè Igbo abbl. Nínú èdè Igbo, fáwẹ̀lì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni ó wà nínú ọ̀wọ́ méjéèjì:

Igbo

| Ọ̀wọ́ I | | Ọ̀wọ́ II | |
|---|---|---|---|
| (Fífẹ káà-ọ̀fun) | | (Àìfẹ káà-ọ̀fun) | |
| i | u | ị | ụ |
| e | o | a | ọ |

nínú ọ̀rọ̀ bí i:

| | |
|---|---|
| isi (orí) | ịsị (purọ́) |
| oke (eku) | ụm̀ụ (ọmọ) |
| ego (owó) | `ụdọ̀ (okùn) |
| òkù (ìpè) | ọkụ (iná) |
| ùdù (ìkòkò ìlù) | afọ̀ (ikùn) |

a ó ṣe àkíyèsí pé ọ̀wọ́ àwọn fáwẹ̀lì tí wọ́n wà ní ọ̀wọ́ I ni wọ́n dì jọ jẹyọ nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí, nígbà tí àwọn tí ọ̀wọ́ II náà ń bá ara wọn ṣiṣẹ́.

Bámgbóṣé (1967) sọ pé Ladefoged ṣe àlàyé bátani àǹkóò Yorùbá sí ọ̀nà méjì tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ni fáwẹ̀lì márùn-ún báyìí:

| Ọ̀wọ́ 1 | | | Ọ̀wọ́ 2 | | |
|---|---|---|---|---|---|
| i | | u | i | | u |
| e | | o | ẹ | | ọ |
| | a | | | a | |

**Commented [O.J98]:** Ǹjẹ́ a nílò èyí nínú ẹ̀kọ́ yìí níwọ̀n bí kì í ti í ṣe ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè ni a fẹ́ fi kọ́? Kìkì ohun tí mo rò pé ẹ lè ṣe ni kí ẹ jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mọ díẹ̀ nínú èdè tí ojúlówó àǹkóò ti máa ǹ wáyé.

**Commented [O.J99]:** Yọ ọ́ kúrò

**Commented [O.J100]:** Ẹ̀wẹ̀, gẹ́gẹ́ bí mo ti sọ ṣáájú, ohun tí ó yẹ kí ó jẹ wá lógún ni ohun tí ó máa fún akẹ́kọ̀ọ́ ní òye ohun tí àǹkóò jẹ́ kì í ṣe àwọn onímọ̀ tó ti sọ nípa wọn. Olùkọ́ yìí sì ni alárinà láàárín àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti àwọn onímọ̀ tí a lè ṣe àmúlò èròjà láti inú iṣẹ́ wọn. Kìkì ìgbà tí a lè máa mẹ́nu ba àwọn onímọ̀ bẹ́ẹ̀ ni tí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ wa bá jẹ mọ́ àríyànjiyàn. Kò sì dà bí ẹni pé àríyànjiyàn jẹ YOR 341 lógún.

ohun tí bátánì yìí fẹ́ kí a gbà ni pé, àwọn fáwẹ́lì tí wọ́n wà ní ọ̀wọ́1 nìkan ni wọn yóó máa bá ara wọn ṣiṣẹ́; tí àwọn tí wọ́n jọ wà ní ọ̀wọ́2 náà yóó jọ máa kó àǹkóò.

Bámgbóṣé (1990:29) fún wa ni àpẹẹrẹ bí i:

Ọ̀wọ́1: adé, ilé, epo, ogun, olè, edé, odò, èrú, dòdò, wèrè, rere bèbè

Ọ̀wọ́2: ọjà, ẹ̀fọ́, ilẹ̀, ẹ̀wà, ẹ̀bi, ẹrù, yẹ̀yẹ́, wẹ́rẹ́, rọ̀rọ̀

Nínú àwọn ọ̀rọ̀ oníbátánì FKF àti KFKF. Ó ní fáwẹ́lì aránmúpè *ọn* tí àkọtọ́ rẹ jẹ́ ọ/a lẹ́yìn kọ́nsónáǹtì aránmúpè tàbí *ọn*/*an* lẹ́yìn kọ́nsónáǹtì yókù wà nínú ọ̀wọ́ II. Bí àpẹẹrẹ:

ọmọ, ọ̀nà, ẹràn

ọ̀ràn, ìbọn, ahọ́n

Commented [O.J101]: Àbá mi ni kí ẹ kàn fún wa ní àpẹẹrẹ láìṣẹ̀ṣẹ̀ máa dárúkọ inú iṣẹ́ tí ẹ ti fà wọ́n yọ.

Ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ ò rí bí bátánì náà ṣe fẹ́ kí a gbà á. Ọ̀pọ̀ àwọn onímọ̀ ni wọ́n ti tọ́ka sí àìṣedédé tí ó wà nínú bátánì yìí. A ó ṣàkíyèsí pé àwọn fáwẹ́lì mẹ́ta kan jẹ yọ ní ọ̀wọ́ méjéèjì (*i*, *u*, àti *a*). Oyebade (2001) dábàá ọ̀wọ́ mẹ́ta fún èdè Yorùbá:

| Ọ̀wọ́1 | Ọ̀wọ́2 | Ọ̀wọ́3 |
|---|---|---|
| e o | ẹ ọ | i u |
| | | a |

àwọn fáwẹ́lì ọ̀wọ́1 kò lè bá fáwẹ́lì ọ̀wọ́2 ṣiṣẹ́ nígbà tí fáwẹ́lì ọ̀wọ́3 lè bá fáwẹ́lì ọ̀wọ́1 àti ọ̀wọ́2 ṣiṣẹ́.

Ó yẹ kí a fi kún un pé Bámgbóṣé (1967) ṣe ìwádìí àǹkóò fáwẹ́lì yìí dé àwọn ẹ̀ka èdè àrìn gbùngbùn Yorùbá tí ó sì ṣe àmúlò ẹ̀ka èdè Ìjẹ̀sà àti Èkìtì. Ó sì fi wọ́n wéra pẹ̀lú ẹ̀ka èdè Ọ̀yọ́ àti olórí-ẹ̀ka-èdè (Yorùbá àjùmọ̀lò). Ó ní ẹ̀kọ́ tí a rí dìmú láti ẹ̀ka èdè ni pé irú ìdènà tàbí àìṣe dédé tí ó wà nínú Yorùbá àjùmọ̀lò kò sí nínú ẹ̀ka èdè.

Fún àpẹẹrẹ irú ìyanra tí ó wà nínú èdè Igbo láàrin ọ̀rọ̀ arọ́pò-orúkọ àti ọ̀rọ̀-ìṣe náà wà nínú ẹ̀ka-èdè Ọ̀yọ́. Ẹ jẹ́ kí à kọ́kọ́ wo ìpèdè èdè Igbo ìsàlẹ̀ yìí

ó zòrò (ó sá pamọ́)

ọ́ zọ̀rọ̀ (a gbà á là)

a ó ṣàkíyèsí pé, ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ tí ó ṣiṣẹ́ olùwà bá àwọn fáwẹ́lì ọ̀rọ̀-iṣe kó àǹkóò. Bẹ́ẹ̀ ni ọ̀rọ̀ sorí nínú àwọn ìpèdè Ọ̀yọ́ àti Ẹ̀gbádò ìsàlẹ̀ yìí

| Ọ̀yọ́/Ẹ̀gbádò | Ólórí Ẹ̀ka èdè |
|---|---|
| mọ lọ | mo lọ |
| mo jó | mo jó |
| ọ fẹ́ | o fẹ́ |
| o dé | o dé |
| ọ wá | o wá |

ó yẹ kí o dí mímọ̀ pé àǹkóò yìí kò ṣiṣẹ́ bí ó ba ti di ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ ẹnikẹta ọ̀pọ̀, bí ó ṣe hàn nínú àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí

ẹ fẹ́

ẹ dé

Orie (2003) ṣàlàyé pé fáwẹ́lì ẹ̀bádò lè bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ ní olórí ẹ̀ka èdè ṣùgbọ́n ẹ̀bákè nìkan ni ó lè bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ nínú ẹka èdè Ifẹ̀ àti Èkìtì gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

| | Olórí ẹ̀ka èdè | Ẹ̀ka èdè Ifẹ̀ àti Èkìtì |
|---|---|---|
| a. | ẹ̀bi | èbi |
| | ẹwìrì | ewìrì |
| | ebi | ebi |

**Commented [O.J102]:** Ṣe ohun tí ẹ ń sọ ni pé kò sí ebi, etí, ní Ẹka èdè Ifẹ̀ àti Èkìtì?

| | |
|---|---|
| èkuru | èkuru |

ó fi kún àlàyé rẹ̀ pé fáwẹ̀lì òkè tí ó jẹyọ láàrin ọ̀rọ̀ a máa dí àǹkóò lọ́wọ́ nínú olórí-ẹ̀ka èdè ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀ fún ẹ̀ka èdè Ifẹ̀ àti Èkìtì

| Olórí Ẹ̀ka Èdè | Ifẹ̀ | Èkìtì |
|---|---|---|
| orúkọ | ọrúkọ | ọrúkọ |
| èlùbọ́ | ẹ̀lùbọ́ | ẹ̀lùbọ́ |
| ewúrẹ́ | ẹúrẹ́ | ẹúrẹ́ |
| òsùpá | ọ̀sùpá | ọ̀ṣùpá |

Commented [O.J103]: Ṣé àwọn àyàbá yìí kò le fa ìṣòro fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́?

### 3.2.1 Àǹkóò Fáwẹ̀lò Nínú Àwọn Ọ̀rọ̀-Orúkọ

Oyebade (2001) sọ pé ẹ̀yà àǹkóò fáwẹ̀lì irú èyí ni à máa ń rí nínú ọ̀rọ̀-orúkọ oníhun FKF àti KFKF, níbi tí F ti dúró fún Fáwẹ̀lì, tí K sì dúró fún Kọ́nsónáǹtì. Ó fún wa ní àpẹẹrẹ bí i:

Commented [O.J104]: Ẹyin ni olùkọ́ kọ́ọ̀sì yìí. Ẹyin ni agbẹnusọ àwọn onímọ̀ bí Oyèbádé abbl.

| Ọ̀wọ́ Kìnní | Ọ̀wọ́ kéjì | Ọ̀wọ́ kẹta |
|---|---|---|
| epo | ẹ̀kọ | òbí, ọtí |
| edé | Ẹdẹ | adé, ẹ̀bà |
| òde | ọ̀dẹ̀ | àpò, ọ̀pá |
| wèrè | wẹrẹ | eku, ẹ̀kú |
| dòdò | rọ̀rọ̀ | ilú, ilà |

Ẹ má jẹ́ ká gbàgbé pé ọ̀nà mẹ́tà ni Oyebade pín fáwẹ̀lì Yorùbá sí gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn lókè. Àwọn àyàfi sì wà nínú àwọn àgbékalẹ̀ òkè yìí pàápàá nínú àwọn ọ̀rọ̀ àyálò bí i:

| | | |
|---|---|---|
| télọ | mọ́tò | fọ́tò |
| lébọ̀ | fẹ́lò | tésọ̀n |

ìbáṣepọ̀ wa láàrin fáwẹ̀lì ọ̀wọ́1 àti fáwẹ̀lì ọ̀wọ́2.

### 3.2.2 Àǹkóò Àfòmọ́-Asọdorúkọ

Àwọn fáwẹ́lì yìí a tún máa yan ara wọn bí a bá ń ẹ̀dá ọ̀rọ̀-orúkọ láti ara ọ̀rọ̀-ìṣe. Oyebade (2001) ni tí ọ̀rọ̀-ìṣe bá ní fáwẹ́lì tí ó ti ọ̀wọ́1 wá, inú ọ̀wọ́1 náà ni a gbọdọ̀ ti mú àfòmọ́-ìbẹ̀rẹ̀ tí a ó fi ṣe ìsọdorúkọ fún un. Àpẹẹrẹ ni

| | | |
|---|---|---|
| gbé | ègbè | |
| gbó | ogbó | |
| ṣe | èṣe, | ṣeré |
| ṣẹ̀ | ẹ̀ṣẹ̀ | |
| so | èso | |
| tò | ètò | |

bí ọ̀rọ̀-ìṣe bá ní fáwẹ́lì ọ̀wọ́2, inú fáwẹ́lì ọ̀wọ́2 náà ni yóó ti mú àfòmọ́-ìbẹ̀rẹ̀ láti ṣe ìsọdorúkọ gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

| | |
|---|---|
| tẹ́ | ẹ̀tẹ́ |
| bẹ̀ | ẹ̀bẹ̀ |
| kọ́ | ẹ̀kọ́ |
| tọ́ | ẹ̀tọ́ |
| jẹ̀lú | ọ̀jẹ̀lú |
| gbọ́n | ọgbọ́n |

níwọ̀n ìgbà tí Oyebade àti ọ̀wọ́1 àti ọ̀wọ́2 ni wọ́n lè bá ọ̀wọ́3 siṣẹ́, nítorí náà fáwẹ́lì ọ̀wọ́3 lè jẹyọ bí àfòmọ́-ìbẹ̀rẹ̀ fún èyíkéyìí ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó bá ní fáwẹ́lì ìbá a ṣe ti ọ̀wọ́1 tàbí ọ̀wọ́2 gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí ṣe fi hàn

**Commented [O.J105]:** ṣẹ̀dá

| | |
|---|---|
| ró | ìró |
| dè | ìdè |
| jó | ijó |
| sè | àsè |
| fẹ́ | ìfẹ́ |
| tọ̀ | àtọ̀ |
| ṣẹlẹ̀ | ìṣẹlẹ̀ |

### 3.2.3 Àǹkóò Fáwẹ́lì nínú Àwọn Ọ̀rọ̀-Orúkọ Ọlọ́pọ̀-Sílébù

Oyebade (2001:87) ní àǹkóò fáwẹ́lì yìí kan náà ni ó fa ìjẹyọpọ̀ àwọn fáwẹ́lì ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ ọlọ́pọ̀ sílébù. Ó ní, tí a bá rí ọ̀rọ̀-orúkọ oní-sílébù mẹ́ta tí ó ní ìhun FKFKF, gbogbo àwọn fáwẹ́lì náà lè ní àbùdá fífẹ káà ọ̀fun [+FKO]; ìyẹn ni pé, wọ́n lè jẹ́: *i*, *e*, *o*, tàbí *u* nínú ọ̀rọ̀ bí i:

| | | |
|---|---|---|
| ehoro | èkúté | òkété |
| eruku | òjòjò | ètùtù |

ṣùgbọ́n bí gbogbo àwọn fáwẹ́lì náà bá ní àbùdá [-FKO] ìyẹn ni pé wọ́n lè jẹ́ *ẹ*, *ọ*, tàbí *a* nínú ọ̀rọ̀ bí i

| | | |
|---|---|---|
| ọ̀pẹ̀lẹ̀ | | ọ̀jọ̀jọ̀ |
| ẹ̀rẹ̀kẹ́ | àkàrà | abẹ̀bẹ̀ |

Àmọ́ sá, bí fáwẹ́lì tí ó kẹ́yìn bá jẹ́ [-FKO] (ẹ, ọ tàbí a), tí fáwẹ́lì kejì bá jẹ́ àhánupè, fáwẹ́lì àkọ́kọ́ gbọ́dọ̀ jẹ́ [+FKO]:

| | | |
|---|---|---|
| ewúrẹ́ | èkùrọ́ | orúkọ |

**Commented [O.J106]:** Kò yẹ kí ẹ máa lo àbùdá [-FKO] àti àbùdá àhánupè pọ̀ fi ṣe àlàyé ohun kan náà.

| | | |
|---|---|---|
| òdìdẹ̀ | ògùsọ̀ | òrìsà |

Àlàyé Òyèbádé ni pé fáwẹ́lì àhánupè a máa ṣe ìdènà fún ìtànká àbúdá [-FKO] tí kì í jẹ́ kí ó tàn dé fáwẹ́lì tí ó bẹ̀rẹ̀ irú ọ̀rọ̀ yìí. Fáwẹ́lì *a* nìkan ni ó lè tàpá sí ìlànà yìí kí ó mú un jẹ. nítorí náà  ni a fi rí *àkùkọ*, *adìyẹ*, *àdìrẹ* àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.  A ṣàkíyèsí pé bí a bá tẹ̀lé àlàyé Oyèbádé òkè yìí, àlàyé wo ni a fẹ́ ṣe fún àǹkóò fáwẹ́lì nínú ọ̀rọ̀ bí i *ìmọ̀dò*?

### 3.2.4 Àǹkóò Fáwẹ́lì nínú Àwọn Òǹkà

Oyebade (2001) ní ìgbésẹ̀ àǹkóò fáwẹ́lì tún farahàn nínú òǹkà. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

| | |
|---|---|
| egbejì | ẹgbẹ̀ta |
| | ẹgbẹ̀rin |
| | ẹgbẹ̀rún |
| | ẹgbẹ̀fà |
| egbèje | ẹgbẹ̀jọ |
| | ẹgbẹ̀sán |
| | ẹgbẹ̀wá |
| ogójì | ọgọ́ta |
| | ọgọ́rin |
| | ọgọ́rùnún |
| | ọgọ́fà |
| ogoje | ogọ́jọ |

ojú ọ̀tọ̀ ni Owólabí (1989) fi wo ìgbésẹ̀ yìí. Ó gbà pé dípò àǹkóò fáwẹ́lì, ìgbésẹ̀ àrànmọ́ ni ó wáyé. Ó ṣàlàyé pé:

> Nígbà tí òǹkà méjì bá jẹ yọ tẹ̀lé ara wọn tààrà, tí ìkínní àwọn òǹkà bẹ́ẹ̀ sì jẹ́ 'ìgba', àrànmọ́ a máa wáyé ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà wòyìí:
>
> A óò pa fáwẹ́lì 'a' àti ohùn (orí) rẹ̀ jẹ ní ìparí òǹkà 'igba' bàyìí:
> igba èjìlá ➔ igb èjìlá
> igba èje ➔ igb èje
> igba ẹ̀ta ➔ igb ẹ̀ta
> igba ẹ̀rin ➔ igb ẹ̀rin
>
> Àrànmọ́ (afòró) yóò wáyé nípa fifi fáwẹ́lì ìbẹ̀rẹ̀ òǹkà kejì, èyí tí í ṣe ìró afàràmọ́ rópò fáwẹ́lì *i* ìbẹ̀rẹ̀ òǹkà kìnní, èyí tí i ṣe ìró agbàrànmọ́ gẹ́gẹ́ bí
>
> | | | | | |
> |---|---|---|---|---|
> | igba èjìlá | ➔ | igb èjìlá | ➔ | egbìjìlá |
> | igba èje | ➔ | igb èje | ➔ | egbèje |
> | igba ẹ̀ta | ➔ | igb ẹ̀ta | ➔ | ẹgbẹ̀ta |
> | igba ẹ̀rin | ➔ | igb ẹ̀rin | ➔ | ẹgbẹ̀rin |

Irú àrànmọ́ yìí kò ṣiṣẹ́ nígbà ti ó kan òǹkà *ìgba* àti *ọ̀kànlá*. Kò ṣe e ṣe láti ní **ọgbọ̀kanlá*. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Owólabí wá àlàyé àrànmọ́ fún ẹ̀gbọkanlá, aléébù méjì ni Oyebádé rí sí èrò Owólabí. Ní àkọ́kọ́, Oyebádé ní ìlànà méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni Owólabí gbé èrò rẹ̀ lórí òǹkà kà bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ihun kan náà ni gbogbo wọ́n ní. Ọ̀kànlá dá ní ìlànà tirẹ̀ lọ́tọ̀, bí àwọn yókù náà ṣe ni ti wọn lọ́tọ̀. Aléébù kejì ni pé, ó dàbí ẹni pé òǹkà nìkan ni ó fàyè gba àrànmọ́ tí a fi ṣe àmúlò àrànmọ́ afòró tó bẹ́ẹ̀. Ó dún nu mọ́ ọn pé kọ́nsónáǹtì *l* àti *r* ni wọn máa ń fàyè gba àrànmọ́ afòró nígbà tí a bá ń so àfòma-ìbẹ̀rẹ̀ mọ́ ọ̀rọ̀-orúkọ àti bí a bá yá ọ̀rọ̀ wọ inú èdè Yorùbá.

Commented [O.J107]: dúnnumọ́

Oyèbádé wá dábàá àlàyé tí ó gùn lé àǹkóò fáwẹ́lì aábùdá fífẹ káà ọ̀fun. Àlàyé rẹ̀ gbà kí a gbà pé òǹkà *igba* ní ẹ̀dà kan, *ẹgbẹ*, èyí tí kò lè dá dúró, tí ó sì jẹ́ pé òǹkà mìíràn ni a máa ń so ó mọ́. Nítorí náà, a lè pa *ẹ* kejì nínú *ẹgbẹ* jẹ, *ẹ* àkọ́kọ́ yóò bá fáwẹ́lì tí ó bẹ̀rẹ̀ òǹkà tí a so ẹ̀dà yìí mọ́ kó àǹkóò:

Commented [O.J108]: gba

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| ẹgbẹ èje | Ìpajẹ → | ẹgbèje | Àǹkóò → | egbèje |
| ẹgbẹ ẹ̀ta | → | ẹgbẹ̀ta | → | ẹgbẹ̀ta |
| ẹgbẹ ọ̀kaǹlá | → | ẹgbọ̀kanlá | → | ẹgbọ̀kanlá |

ìrú àlàyé yìí kan náà ni ó ṣe fún àwọn òǹkà tí ó máa ń fi ogún saájú:

| | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|
| ogó èje | Àrànmọ́ → | ogóèje | Ìpajẹ → | ogóje | Àǹkóò → | ogóje |
| ogó ẹ̀ta | → | ogóẹ̀ta | → | ogọ́ta | → | ọgọ́ta |
| ogó àrún | → | ogọ́àrún | → | ogọ́rùnún | → | ọgọ́rùnrún |

ìwọ̀ gẹ́gẹ́ bí àkẹ́kọ̀ọ́ ni kí o gbé àlàyé Owólabí àti Oyèbádé wò, kí o sì wo èyí tí ó bá ìlànà fonọ́lọ́jì òde òní mú.

Commented [O.J109]: tọ̀nà lójú tìrẹ

### 3.2.5 Àǹkóò Fáwẹ́lì Oníwájù àti Ẹ̀yìn

Oyèbádé ṣàlàyé pé Awóbùlúyì (1967) ni ó kọ́kọ́ tọ́ka sí ẹ̀yà àǹkóò fáwẹ́lì yìí nínú èdè Yorùbá. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Bámgbóṣé (1990) ṣàlàpé àǹkóò fáwẹ̀lì yìí jẹ mọ́ àjùmọ̀rìn fáwẹ́lì iwájú, àti fáwẹ́lì ẹ̀yìn pẹ̀lú fáwẹ́lì ẹ̀yìn. Èyí fún wa ní ọ̀wọ́ méjì

| Ọ̀wọ́ Iwájú | Ọ̀wọ́ Ẹ̀yìn |
|---|---|
| i | u |
| e | o |
| ẹ | ọ |
| a | a |

Fáwẹ́lì *a* lè bá ọ̀wọ́ iwájú tàbí ti ẹ̀yìn rìn.

Àǹkóò fáwẹ́lì oníwájú àtẹ̀yìn máa ń bá àwọn ọ̀rọ̀ oníbátánì KFKF ṣiṣẹ́. Àpẹẹrẹ ni

Ọ̀wọ́ Iwájú: gìrì, wèrè, fìlà, yẹ̀yẹ́

Ọ̀wọ́ Ẹ̀yìn: dùrù, dòdò, pákó, rọ̀rọ̀

Bámgbóṣe fi kún un pé, àwọn ọ̀rọ̀ Yorùbá oníbátànì KFKF tí ó dá dúró kò pọ̀ rárá. Ṣùgbọ́n ọ̀pslọpọ̀ ọ̀rọ̀ ní ó wà tí a ti lè fa bátánì yìí yọ lára rẹ̀. Àwọn fáwẹ́lì inú KFKF tí a fa yọ gbọdọ̀ ni àǹkóò fáwẹ̀lì iwájú tàbí ẹ̀yìn. Irú àwọn ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ àti bátánì wọn ni:

Commented [O.J110]: tẹ̀lé àbùdá iwájú tàbí àbùdá ẹ̀yìn

(i) F-KFKF
Ògiri, òkèlè, òrìsà, àgbèrè, àtíkè, abẹ̀bẹ̀, ọ̀pẹ̀lẹ̀, eruku, ìràwọ̀, èlùbọ́, ọ̀jọ̀jọ̀, òjòjò, òkùnkùn, òṣùpá, ìyàwó, òṣùgbo, ògurọ̀, ètùtù, èkùrọ́

(ii) KFKF-KF tàbí KF-KFKF
Fèrèsé, pẹlẹbẹ, pltẹ́lẹ̀, gegele, rugudu, kòkòrò, kọ́kọ́rọ́, gogoro, gúgúrú, pòrògún, wọ̀rọ̀kọ̀, tàtàṣé

(iii) KFKF-KFKF
Porogodo, bàlùbàlù, kòbòkóbò, gìrìgìrì

(iv) F-KFKF-KF tàbí F-KF-KFKF
Ògógóró, ọ̀gẹ́gẹ́rẹ́, ọ̀gìnnìtìn

Yàtọ̀ sí bátánì KFKF, Bángbóṣé (1990:31) ní  àǹkóò fáwẹ̀lì iwájú àti ẹ̀yìn wà nínú àwọn bátánì wọ̀nyí:

(a) F-KFFKF
Ìhòòhò, àpẹẹrẹ

(b) KFNKF
Kọ̀nkọ̀, dùndú

(d) F-KFNKF
Ògòǹgò

Ó wá ṣàlàyé pé àwọn ọ̀rọ̀ kan wà tó jẹ́ pé wọn ò bẹ́gbẹ́mu fún àǹkóò fáwẹ̀lì oníwájú àtẹ̀yìn. Nínú àwọn ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀, a máa ń rí àjùmọ̀rìn fáwẹ̀lì iwájú àti ẹ̀yìn. Àpẹẹrẹ ni:

èkúté, ewúrẹ́, àpótí, iyànrìn, àtòrì, àsìkò, òtòsì, àwòdì, gọ̀bì,

Àìrí àlàyé fún àwọn kòbẹ́gbẹ́mu yìí ni Oyèbádé gbìyànjú láti wá ẹ̀rí fún nínú àlàyé Awóbùlúyì. Ẹ̀rí náà ni pé bí a bá yá ọ̀rọ̀ wọ inú èdè Yorùbá, tí ọ̀rọ̀ náà bá ni ìsùpọ̀ kansónáǹtì, Yorùbá máa ń fi fáwẹ̀lì *i* tàbí *u* la ìsùpọ̀ kọ́nsónàǹtì bẹ́ẹ̀. Èyí tí a ó yàn nínú méjéèjì dá lórí ìlànà àǹkóò yìí:

| Iwájú | Ẹ̀yìn |
|---|---|
| kíláàsì, bíríkì | sọ́ọ̀bù, góòlù |
| búrẹ́dì, bíléèdì | ṣùkúrù, dúrọ́ọ̀mù |
| búréèkì, síléètì | sítóòfu, kílọ́ọ̀bù |
| bíbélì | síkáòtù |

### 3.2.6 Àǹkóò Fáwẹ̀lì Nínú Ọ̀rọ̀ Àyálò

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀rọ̀ àwíjare Oyèbádé wà nínú ọ̀rọ̀ àyálò, Bámgbóṣe gan-an ti sọ̀rọ̀ lórí irú àǹkóò fáwẹ̀lì yìí. Ó ní nígbà tí a bá yá ọ̀rọ̀ láti inú èdè mìíràn wọ inú èdè Yorùbá, a máa ń gbìyàbjú láti fi ara wọn mọlé gẹ́gẹ́ bí àwọn ọ̀rọ̀ ìṣẹ̀dálẹ̀. Bí àpẹẹrẹ

kọ́bọ̀, títì, ṣọ́jà, kọ́búrù, kọ́nà, ṣimí, búlù, góòlù, ṣọ́ọ̀bù, féélì

Bámgbóṣé wá ṣàlàyé pé kìí ṣe gbogbo ọ̀rọ̀ àyálò ni ó ní àǹkóò fáwẹ̀lì. Ó tọ́ka sí àwọn kò bẹ́gbẹ́mu kan bí i:

fọ́tò, mọ́tò, télọ̀, lébọ̀, tésọ̀n,

àwọn kan tilẹ̀ wà tí wọ́n rú òfin àǹkóò fáwẹ̀lì oníwájú àti ẹ̀yìn bí i:

pọ́tì, pílò, sọ́bírì, tébúlù/tébúrù, gómínà, kalẹ́jì, férémù

fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí èyí, mo rọ̀ ọ́ kí o wo Bámgbóṣe (1990: 32-35).

### 4.0 Ìsọnísókí

Commented [O.J111]: àlàyé ṣe fún

Commented [O.J112]: Gbogbo ohun tó jọ mọ́ àríyànjiyàn, YOR 441 ló yẹ kó ti wáyé

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a wo àǹkóò fáwẹ́lì. A wo bí ó ṣe ń ṣiṣẹ́ nínú èdè mìíràn àti èdè Yorùbá. A wo bí àwọn onímọ̀ ṣe pín àwọn fáwẹ́lì Yorùbá sí ọ̀wọ̀ọ̀wọ́. a mẹ́nu ba bí àwọn àǹkóò fáwẹ́lì yìí ṣe ń ṣiṣẹ́ nínú àwọn ẹ̀ka èdè Yorùbá pàápàá ẹ̀ka èdè àrin gbùngbùn Yorùbá. Lẹ́yìn náà ni wo bí àwọn fáwẹ́lì yìí ṣe máa ń ṣe nínú àwọn ọ̀rọ̀ orúkọ. A kò sài wò ó dé ibi ẹ̀yà àǹkóò fáwẹ́lì títí ó fi dé ọ̀rọ̀ àyálò.

Commented [O.J113]: ???

**5.0 Ìdánwò Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

Dáhùn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí

i. Sọ bí Yorùbá bá ni àǹkóò fáwẹ́lì pẹ̀lú àpẹẹrẹ láti inú Yorùba àjùmọ̀lò àti ẹ̀ka èdè

ii. Ṣe àlàyé àǹkóò fáwẹ́lì oníwájú àti ẹ̀yìn

**6.0 Ìwé Ìtọ́kasí**


Bámgbóṣé Ayọ̀ (1967) Vowel Harmony in Yoruba. *Journal of African Languages*, Vol. 6, pp 268-273

Bámgbóṣé Ayọ̀ (1990) *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ibadan, University Press Ltd

Orie Olanike (2001) An Alignment-Based Account of Vowel Harmony in Ife Yoruba. *JALL*, Vol 22. pp 117-143

Orie Olanike (2003) Two Harmony Theories and High Vowel Pattern in Ebira and Yoruba. *The Linguistics Review* Vol 20. pp 1-35

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tíìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

Oyèbádé Francis (2001) Ìgbẹ́sẹ̀ àti Ìlànà Fonọ́lọ́jì Èdè Yorùbá nínú *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá-Èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà*. Olóòtú: Bádé Àjàyí

# ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ KEJÌ

## ÌYÀTỌ̀ ÀǸKÓÒ FÁWẸ́LÌ ÀTI ÌJẸYỌPỌ̀ FÁWẸ́LÌ

### 1.0 Ìfáárà

Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí tí ó kọjá, a ṣe àgbéyẹ̀wò àǹkóò fáwẹ́lì. A wo bí àwọn onímọ̀ ṣe pín fáwẹ́lì èdè Yorùbá nípa fífẹ̀ káà ọ̀fun. A wo bí àwọn fáwẹ́lì kan ṣe le bá àwọn fáwẹ́lì kan ṣiṣẹ́ àti bí àwọn kan kò ṣe lè bá àwọn fáwẹ́lì kan ṣiṣẹ́. a fi àǹkóò fáwẹ́lì èdè Yorùbá wé àǹkóò fáwẹ́lì tí ó wà nínú èdè Igbo. Ìdí yìí gan an ni ó fà á tí àwọn kan fi rò pé, kò sí ìyàtọ̀ kankan nínú àǹkóò fáwẹ́lì àti ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì. Kókó ọ̀rọ̀ yìí gan-an sì ni a fẹ́ wò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.

Commented [O.J114]: Yọ ọ́ kúrò

Commented [O.J115]: Ó lọ́ púpọ̀, kò já gaara

## 2.0 Èròǹgbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, akẹ́kọ̀ọ́ yóó le:

i. Ṣe àlàyé ìyàtọ̀ tó wà láàrin àǹkóò fáwẹ́lì àti ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì.

ii. Pẹ̀lú àpẹẹrẹ tí ó pèye, tọ́ka sí àwọn òté ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì nínú ọ̀rọ̀ oníbátànì F-KF

### 2.1 Ìdánwò ìbèrè ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Dáhùn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí

i. Ṣàlàyé ìyàtọ̀ tó wà láàrin àǹkóò fáwẹ́lì àti ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì.

ii. Tọ́ka sí àwọn òté ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì nínú ọ̀rọ̀ oníbátánì F-KF pẹ̀lú àpẹẹrẹ tí ó péye.

## 3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Owólabí (2013:140) ṣàlàyé ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì nígbà tí ó ń sọ̀rọ̀ nípa ọ̀rọ̀ olópọ̀ sílébù. ó ní, nínú èdè Yorùbá, àwọn fáwẹ́lì kì í jẹ yọ pọ̀ ṣegeṣège núnú ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù. ó lójú àwọn fáwẹ́lì tí wọ́n lè jọ jẹ yọ pọ̀. Ìyẹn ni pé, ètò tàbí bátánì ìjẹyọpọ̀ wà fún àwọn fáwẹ́lì nínú àwọn ọlọ́pọ̀ sílébù. ó sì rorùn láti sàpèjúwe bátànì ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì tí a ń wí yìí nínú àwọn ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù oníbátánì $F_1$- $KF_2$ . Ní ibi tí $F_1$ ti jẹ́ fáwẹ́lì àkọ́kọ́ àti sílébù àkọ́kọ́ tí $F_2$ sì jẹ́ fáwẹ́lì kejì nínú sílébù kejì.

Bámgbóṣé (1990:37) fún wa ní bátánì méjì: F-KF àti KFKF. Ó wá ní orísi jíjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì mìíràn wà tí wọn kò bá ara wọn ṣiṣẹ́ bi i ti àǹkóò fáwẹ́lì. Ó fún wa ní àpẹẹrẹ pé kò sí òfin tí ó de àjùmọ̀rìn *e* ati *a* nítorí pé a máa ń rí ọ̀rọ̀ bí i: *adé*, *ayé*, *ajé*, *àsé*,

*àwé* ṣùgbọ́n kò sí ọ̀rọ̀ bí i *èdá, *èya, *eja àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bámgbóṣé wá fún wa ní òté mẹ́ta fún jíjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì èdè Yorùbá.

### 3.1 Òté Ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì nínú Ọ̀rọ̀ Oníbátánì F-KF

Bámgbóṣé (1990) ní òté wà tí ó de jíjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì yàtọ̀ sí òté àǹkóò fáwẹ́lì. Àwọn òté náà ni:

1. Fáwẹ́lì tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ kò lè jẹ́ *u* tàbí fáwẹ́lì àránmúpè. Bí àpẹẹrẹ, kò sí srọ̀ bí *usu, *ulé, *unrun, *ọnkan, *ìnwà nínú Yorùbá Gbogbogbo. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé *u* lè bẹ́rẹ̀ ọ̀rọ̀ nínú àwọn ẹ̀ka èdè pàápàá ẹ̀ka èdè àrin gbùngbùn Yorùbá.
2. Tí fáwẹ́lì *e* tàbí *o* bá bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀, fáwẹ́lì tí ó tẹ̀lé kò lè jẹ́ *a*. Bí àpẹẹrẹ, kò sí ọ̀rọ̀ bí i *elà, *ebà, *eka, *olá, *ojà, *orá.
3. Tí fáwẹ́lì *ọ* bá bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀, fáwẹ́lì tí ó tẹ̀lé e kò lè jẹ́ *u*. Bí àpẹẹrẹ, kò sí ọ̀rọ̀ bí i *ọdú, *ọ̀fu, *ọ̀ru

Ohun tí Bámgbóṣe pè ní òté yìí ni Owólabí pè ní àkìyèsí lórí ìj]eyọpọ̀ fáwẹ́lì nínú ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù. Mẹ́tà péré ni òté tí Bámgbóṣé mẹ́nubà, Owólabí fi ẹyọ kan kún tirẹ̀ tí ó fi jẹ́ mẹ́rin. Ẹ̀yí tí ó fi kún ún náà ni pé:

Bátànì ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì *i* àti *a* fẹ́rẹ̀ẹ́ kọ ara wọn nítorí pé fáwẹ́lì *ẹn* nìkan ṣoṣo tí ó lè tẹ̀lé *i* ṣùgbọ́n tí kò le tẹ̀lé *a* ni ó fa ìyàtọ̀ bátánì ìjẹyọpọ̀ wọn.

### 3.2 Ìyàtọ̀ Àǹkóò Fáwẹ́lì àyi Ìjẹyọpọ̀ Fáwẹ́lì

Owolabí (2013) rí àǹkóò fáwẹ́lì gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì. Ìyàtọ̀ pàtàkì wọn ni pé nínú àǹkóò fáwẹ́lì, àwọn fáwẹ́lì tí wọ́n tẹ̀lé ara wọn máa ń ní àbùdá kan náà. Ṣùgbọ́n nínú ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì, kò pan dandan kí àwọn fáwẹ́lì tí wọ́n jọ jẹyọ pọ̀ ní àbùdá kan náà. Nígbà tí kò jẹ́ kàn-ń-pá láti fi àbùdá pín àwọn fáwẹ́lì sí ọ̀wọ́ nígbà ti

a bá ń sọ̀rọ̀ ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì, ó dàbí àṣà fún àwọn èdè tí wọ́n ní àǹkóò fáwẹ́lì láti pín àwọn fáwẹ́lì sí ìsọ̀rí ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ nípa lílo àbùdá. Fún èdè Yorùbá, fífe káà ọ̀fun ni a lò gẹ́gẹ́ bí a fi hàn nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọjá. Àwọn fáwẹ́lì tí wọ́n bá wà ní ìsọ̀rí kan náà ni wọ́n máa ń bá ara wọn ṣiṣẹ́ nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa àǹkóò fáwẹ́lì, èyí tí kò rí bẹ́ẹ̀ nínú ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì.

Commented [O.J116]: àbùdá ajẹmófónẹ́tíìkì

Commented [O.J117]: rìn

Fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́, àlàyé lórí ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì, wo LIY 214 tàbí Bámgbóṣe (1990) àti Owólabí (2013).

## 4.0 Ìsonísókí

Ohun tí a wò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni ìyàtọ̀ tó wà nínú àǹkóò fáwẹ́lì àti ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì. Nígbà tí ọ̀kan no òté, ìkejì ní ìsọ̀rí. Fún ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì, òté wà ti àwọn fáwẹ́lì Yorùbá ń tẹ̀ẹ́lé ṣùgbọ́n fún àǹkóò fáwẹ́lì, bí a bá tẹ̀lé àgbékalẹ̀ Oyèbádé (2001) ìsọ̀rí mẹ́ta ni a pín fáwẹ́lì Yorùbá sí nípa lílo òté fifẹ káà ọ̀fun. Àwọn fáwẹ́lì tí ó wà ní ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan ni ó lè bá ara wọn ṣiṣẹ́ àyàfi àwọn fáwẹ́lì tí wọ́n wà ní ìsọ̀rí kẹta tí wọ́n lè bá méjèèjì àkọ́kọ́ ṣiṣẹ́.

Commented [O.J118]: Kò dà bí ẹni wí pé bẹ́ẹ̀ lọ̀rọ̀ rí o. [i, u, a] ṣeé pín sí Fífẹ̀ káà ọ̀fun àti àìfẹ̀káà ọ̀fun.

## 5.0 Ídáwò Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

i. Ṣàlàyé ìyàtọ̀ tó wà láàrin àǹkóò fáwẹ́lì àti ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì.

ii. Tọ́ka sí àwọn òté ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì nínú ọ̀rọ̀ oníbátánì F-KF pẹ̀lú àpẹẹrẹ tí ó péye.

## 6.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Bámgbóṣé Ayọ̀ (1990) *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ibadan, University Press Ltd

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tíìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

Oyèbádé Francis (2001) Ìgbẹ́sẹ̀ àti Ìlànà Fonọ́lọ́jì Èdè Yorùbá nínú *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá-Èdè, Lítírésọ̀ àti Àṣà*. Olóòtú: Bádé Àjàyí

## ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ ÌKẸTA

## ÌYỌ́PỌ̀ FÁWẸ́LÌ

### 1.0 Ìfáárà

Kókó ọ̀rọ̀ ni a ti já léwé nínú LIY 214 ṣùgbọ́n a ó wà á légbò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Kókó ọ̀rọ̀ ti a fẹ́ ṣisẹ́ lórí náà ni Ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, àwọn onímọ̀ kan gbà pé ìgbéṣẹ̀ fonọ́lọ́jì yìí kò sí nínú èdè Yorùbá àti pé ohun tí àwọn kan ń pè ní ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì yìí ni ó jẹ́ àrànmọ́ tí a lè tọ pinìn rẹ̀ dé inú ẹ̀ka-èdè. Ṣé bẹ́ẹ̀ lọ̀rọ̀ sì rí? Nítorí náà a ó mú ẹ̀rí wa láti apá méjéèjì tó bẹ́ẹ̀ tí akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè sọ ìyàtọ̀ ìgbésẹ̀ fonọ́lajì ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì àti àrànmọ́.

Commented [O.J119]: Ohun tí mo rò pé ó yẹ kí iṣẹ́ YOR 341 gbájúmọ ni àlàyé tó jinlẹ̀ lórí àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì wọ̀nyẹn kẹ́ fi àríyànjiyàn sílẹ̀ fún YOR441.

**Eròǹgbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:

i. Ṣe àlàyé ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì.

ii. Pàálà sáàrin ìyọ́pọ̀ tààrà àti ìyọ́pọ̀ àsọdòdì

Ìdánwò ìbẹ̀rẹ̀ ẹ̀kọ́

i. Ṣe àlàyé Ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì

ii. Pàálà sáàrin ìyọ́pọ̀ tààrà àti ìyọ́pọ̀ àsọdòdì

**2.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

Bamgboṣe (1990:65) ki ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì báyìí: Àpapọ̀ fáwẹ́lì méjì tí àbájáde rẹ̀ jẹ́ fáwẹ́lì kẹta tí ó yàtọ̀ gédégédé ni a máa ń pè ní ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì. Ohun tí Bámgboṣe ń sọ ni pé, nígbà tí fáwẹ́lì méjì bá padé ní ààlà mọ́fíìmù, àwọn méjéèjì yóò dá àbùdá wọn jọ láti mú fáwẹ́lì kẹta tí ó mú lára àbúdá àwọn méjéèjì tí wọ́n pàdé yìí.

Commented [O.J120]: ó máa mú

Oyèbádé (2001:101) jábọ̀ pé Crowther (1852) ni ó kọ́kọ́ sísọ lójú ọ̀rọ̀ yìí, àmọ́ Ọ̀jọ́gbọ́n Awóbùlúyì ni ó ṣe akitiyan jù lórí ọ̀rọ̀ náà. Awóbùlúyì (1992) ṣàlàyé pé àwọn ẹ̀ka èdè Yorùbá fún wa ní ẹ̀rí pùpọ̀ láti ṣe ọ̀fín tótó ìgbésẹ̀ fonọ́lajì yìí. Ó ṣàlàyé pé orísìí ìyọ́pọ̀ mẹ́ta ló wà:

Coalescence by merger ➔ ìyọ́pọ̀ alákànpọ̀

Coalescence by Assimilation ➔ ìyọ́pọ̀ aláràǹmọ́

Coalescence by Polarisation ➔ ìyọ́pọ̀ ẹlẹ́là

Ó ni èrò àti jọ́ ni pé ìyọ́pọ̀ ẹlẹ́là nìkan kọ́ ni ó wà ní èdè Yorùbá, ẹ̀rí láti inú ẹ̀ka èdè fi hàn pé gbogbo ẹ̀yà ìyọ́pọ̀ mẹ́tẹ̀ta ní ó wà ní èdè Yorùbá.

Oyebádé tọ́ka sí ìṣẹ́ Awóbùlúyì ti ọdún 1983 àti 1987 lórí kókó ọ̀rọ̀ yìí. Ó mẹ́nu ba àwọn àpẹẹrẹ yìí:

(a)

| | | | |
|---|---|---|---|
| (i) | i + o => u | a-rí- ogbó | => arúgbó |
| (ii) | ọ + i => u | ò-mọ-ìwẹ̀ | => òmuwẹ̀ |
| | | gbọ́ ìró | => gbúròó |
| (iii) | un + e =>o | ogún-èje | => ogóje |
| (iv) | un + a => ọ | ogún àrún | => ogọ́rùn-ún |
| | (b) | | |
| (i) | i + i =>u | iṣe-kí-ìṣe | => ìṣekúṣe |
| | | ibi-ìjẹ-ẹran | => ibùjẹran |
| (ii) | e + i =>u | ò ṣe-ìwọ̀n | => òsùwọ̀n |
| (iii) | a + o =>u | ò sà ògbó | => òsùgbó |
| (iv) | a + ọ => u | dá ọpẹ́ | => dúpẹ́ |

àwọn àpẹẹrẹ tí wọ́n wà ní abẹ́ ìsọ̀rí (a) kò fa ìyàn lọ títí, ìdí ni pé, gbogbo àbùdá tí a bá lára fáwẹ́lì kẹta ni a lè rí lára fáwẹ́lì àkọ́kọ́ tàbí ìkejì. Ibi tí ọ̀rọ̀ ti lọ́jú pọ̀ díẹ̀ ni àpẹẹrẹ tí ó wa ní abẹ́ ìsọ̀rí (b). Bí a bá wo àpẹẹrẹ (i) àti (ii) àkíyèsí tí a ó ṣe ni pé fáwẹ́lì àbájáde ní àbùdá kan tí kò pàpọ̀ mọ́ ọ̀kankan lára ìkínni tàbí ìkejì. Àbùdá náà sì ni roborto. Tí a bá wo àpẹẹrẹ (iii) àti (iv) ni àbẹ́ ìsọ̀rí yìí kan náà, àbùdá tí fáwẹ́lì àmújáde ní tí àwọn méjéèjì ò ní ni àhánu.

Oyèbádé (2001) wá ṣàlàyé pé, Awóbùlúyì dàbàá orísìí ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì méjì ni ó wà lédè Yorùbá:

**Commented [O.J121]:** Kí ló dé kí ẹ kò lọ tàárà sí ohun tí ìyọ́pọ̀ jẹ́, òté tó dè é àti àwọn àpẹẹrẹ láìṣẹ̀ṣẹ̀ máa gbẹnusọ fún ẹnìkọ̀ọ̀kan àwọn onímọ̀ tó ti sọ̀rọ̀ lórí ohun kan.

**Commented [O.J122]:** àríyànjìyàn

**Commented [O.J123]:** àhánupè

**Commented [O.J124]:** dàbàá pé

Ìyọ́pọ̀ tààrà

Ìyọ́pọ̀ àsọdòdì

Ìyọ́pọ̀ tààrà ni a rí nígbà tí gbogbo àwọn àbùdá fáwẹ́lì àmújáde bá wá láti ara fáwẹ́lì ìpìlẹ̀ ìkínní tàbí ìkejì (gẹ́gẹ́ bí a ti rí i lábẹ́ (a) lókè). Ìyọ́pọ̀ àsọdòdì yóó sọ fáwẹ́lì kejì di òdi pẹrẹsẹ (ìyẹn roboto). Tí ó bá jẹ́ roboto àìhanupè, yóó sọ ọ́ di àhánupè. Lẹ́yìn eléyìí ni fáwẹ́lì kiíni yóó pòórá.

Ọ̀jọ̀gbọ́n Bámgbóṣé ta ko àbá yìí. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ wọn ọdún 1986 ni wọn ti ṣàlàyé pé irú ìyọ́pọ̀ àsọdòdì yìí lòdì sí ohun tí a mọ̀ sí ìyọ́pọ̀ bí ó ti ń ṣiṣẹ́ nínú àwọn èdè ọmọnìyàn tí ó fàyè gbà á. Wọ́n fi kún un pé ó sòro láti mo àgbègbè ibi tí ó tilè ṣiṣẹ́. Bí àpẹẹrẹ:

Commented [O.J125]: Iṣẹ́ YOR 441 ni gbogbo àríyànjiyàn tó ń wáyé lórí àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì yẹn

ibi + ìjẹ => ibùjẹ (ẹran)

ibi + ìsùn => ibùsùn

ibi + isọ̀ => ibùsọ̀

ṣùgbọ́n

ibi + ìkan => ibikan

ibi + ìsinmi => ibisinmi

Wọ́n ṣàlàyé pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àpẹẹrẹ ìyọ́pọ̀ ni a lè lo ìparójẹ láti ṣe àlàyé wọn tí a bá gba ẹ̀rí ẹ̀ka èdè wọlé. Wọ́n sọ síwájú sí i pé gbogbo ibi tí àmújáde ti jẹ́ àhánupè roboto [u], ni a lè lo ẹ̀rí ẹ̀ka èdè láti ìpìlẹ̀ ọ̀kan nínú àwọn fáwẹ́lì náà kalẹ̀ pé [u] ni. Àlàyé wọn lọ báyìí:

Ìpìlẹ̀: ò-ṣe-ùwọ̀n ìṣe-kí-ùṣe

Ìpàrójẹ: òsùwọ̀n ìṣekúṣe

Àmùjáde: òsùwọ̀n ìṣekúṣe

Awóbùlúyì kò gba èrò Bámgbóṣé wọlé. Wọ́n rò pé àlàyé ìṣe-kí-ùṣe mẹ́hẹ. Ìdí ni pé, nínú ìhun tí a ti máa ń ṣe àsọdorúkọ báyìí, ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ kan náà ni ó máa ń wà ní ọ̀tún àti òsì **kí.** Bí àpẹẹrẹ

Orí-kí-orí => oríkórí

A ó sì rí pé, wúnrẹ̀n ìpìlẹ̀ Bámgbóṣé kò rí bẹ́ẹ̀.

Ní ọ̀nà kejì, Awóbùlúyì ní bí a bá tilẹ̀ fi ìparóje ṣàlàyé, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí, a ó sì rí mélòó kan tí kò sí bí a ṣe lè ṣàlàyé wọn àyàfi bí a bá lo ìyọ́pọ̀. Bí ọ̀rọ̀ bá wá rí báyìí, a jẹ́ pé ìyọ́pọ̀ jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì èdè Yorùbá. Àmọ́ sá, Bámgbóṣé (1990) náà gúnlẹ̀ pé, ó rọrùn láti lo ẹ̀dà ọ̀rọ̀, kí á sì lo fáwẹ́lì pípajẹ ju pé kí a máa dàámú àtiwá òfin ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì

### 3.0 Ìsọnísókí

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí sọ̀rọ̀ nípa ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì èdè Yorùbá. A mẹ́nu bà á pé ìyọ́pọ̀ ni ibi tí fáwẹ́lì méjì ti padé tí àyọrí sí rẹ̀ sì jẹ́ fáwẹ́lì kẹta. A wo orísìí ìyọ́pọ̀ méjì tí ó wà gẹ́gẹ́ àgbékalẹ̀ Awóbúlúyì: ìyọ́pọ̀ tààtà àti ìyọ́pọ̀ asọdòdì. A mẹ́nu bá àríyànjiyàn lórí kókó ọ̀rọ̀ yìí láàrin Bmgbóṣe àti Awóbùlúyì. A sì ní ìrètí pé ìjíròrò yìí yóó gún akẹ́kọ̀ọ́ ní kẹ́ṣẹ́ inú láti lọ wá imọ sí i.

Commented [O.J126]: Kò já gaara

### 4.0 Ìdánwò Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Dáhùn àwọn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí

i. Fi ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì àti àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì yòókù hàn

ii. Pàálà sáàrin ìtọ́pọ̀ tààrà àti ìyọ́pọ̀ àsọdòdì

### 5.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Awobuluyi O. (1967) Vowel and Consonant Harmony in Yoruba. *Journal of African Languages* 6.1, pp1-8

Awobuluyi O. (1987) Towards a Typology of Coalescence. *Journal of West African Languages* XVII.2 pp5-22

Awobuluyi O. (1989) Ìyọ́pọ̀ Fáwẹ́lì: Àmójúfò Ara Fonọ́lọ́jì Yorùbá. *Láàńgbàsà (Jọ́nà Akadá ní Èdè Yorùbá*). University of Lagos. pp 1-39

Awobuluyi O. (1992) Aspects of Contemporary Standard Yoruba in Dialectological Perspective in Isola A (ed) *New Findings in Uoruba Studies*. J.F Odunjo Memorial Lecture Series No.3

Bamgbose A. (1986) *Yoruba: A Language in Transition*. Lagos. J.F. Odunjo Memorial Lectures Organising Committee

Bamgbose A (1990) *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yoruba*. Ibadan. University Press Ltd.

Oyèbádé Francis (2001) Ìgbẹ́ṣẹ̀ àti Ìlànà Fonọ́lọ́jì Èdè Yorùbá nínú *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá-Èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà*. Olóòtú: Bádé Àjàyí


## MÓÒDÙ KẸTA: ÌRÁNMÚ ÀTI Ọ̀RỌ̀ ÀYÁLÒ

## ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ ÌKÍNNÍ: ÌRÓ ARÁNMÚPÈ

### 1.0 Ìfáárà

Nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìró, òrísìírísìí àbùdá ni a máa ń wò mọ́ ìró lára. Lára àwọn àbùdá náà ni bí àfàṣe bá gbé sókè tí ó lọ dí ọ̀nà tí ó lọ sí imú, tó bẹ́ẹ̀ tí èémí ń gba ẹnu nìkan jáde. Piró tí a bá pè nígbà náà ni a mọ̀ sí àìránmúpè. Àmọ́, bí àfàṣẹ́ bá wá sí ìsàlẹ̀ tí èémí ń gba imú jáde, irú ìró tí a bá pè ní ìgbà náà ni a mọ̀ sí ìró aránmúpè.

Commented [O.J127]: orísìrísì/orísìírísìí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí a ó ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ìró aránmúpè yií. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó ń bọ̀ ni a wo ìránmúpè gẹ́gẹ́ bí ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì.

## 2.0 Èròǹgbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè:

i. Ṣe àpèjúwe ìró kọ́nsónáǹtì aránmúpè.

ii. Ṣàlàyé ìró fáwẹ́lì aránmúpè

2.1 Ìdánwò ìbẹ̀rẹ̀ ẹ̀kọ́

i. Ṣe àpèjúwe ìró kọ́nsónáǹtì aránmúpè

ii. Ṣàlàyé ìró fáwẹ́lì aránmúpè

## 3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Lára àbùdá ìsàpèjúwe ìró kọ́nsónáǹtì àti fáwẹ́lì ni ipò tí àfàsé wà. Owólabí (2013) ṣàlàyé pé àfàsé lè wá sí ilẹ̀ kí ọ̀nà tí ó lọ sí imú là sílẹ̀ tó bẹ́ẹ̀ tí èémí yóó máa gba imú jáde. Ìró tí a bá pè ní gbà tí àfàsé wá sílẹ̀ ni a mọ̀ sí ìró aránmúpè. Àfàsé lè gbé sókè kí ó dí ọ̀nà sí imú, tí èémí yóó máa gba ẹnu nìkan káde. Irú ìró tí a bá pè nígbà yìí ni à ń pè ní ìró àìránmúpè.

Àfojúsùn wa nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí kìí ṣe ìró àìránmúpè. Ìró aránmúpè gan-an ni a fẹ́ fúnka mọ́. A ó wo àwọn ìró kọ́nsónáǹtì aránmúpè àti àwọn fáwẹ́lì aránmúpè. Ó yẹ kí ó di mímọ̀ pé kìí ṣe àwọn ìró tí wọ́n jẹ́ aránmú nípa ìṣẹ̀dá pàá pàá àrànmọ́ ni a ó mẹ́nu bà níbí**. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ń bọ̀ ni a ó ti sọ nípa rẹ̀.**

### 3.1 Kọ́nsónáǹtì Àránmúpè

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ LIY 214, a fún kọ́nsónáǹtì ni oríkì fónẹ́tíìkì àti oríkì fonọ́lọ́jì. Láti mú àwọn oríkì náà wá sí ìrántí wa, a ó tún tún oríkì náà sọ. Oríkì kọ́nsónáǹtì ní ìlànà fónẹ́tíìkì lọ báyìí: *Kọ́nsónáǹtì* ni *ìró tí a pè nígbà tí ìdíwọ́ wà fún èémí ni ibì kan ní òpópónà ajẹmóhùn*. A ṣàlàyé nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà pé ìró *w* àti ìró *y* kò bẹ́gbẹ́ mu tí a bá gùnlé ìlànà ìrú ìdíwọ́ tí ó wà fún èémí ní ibìkan ní

òpópónà ajẹmóhùn. Bí a bá gùn lé oríkí Kọ́nsónáǹtì ní ìlànà fonọ́lọ́jì, a lè sọ pé *kọ́nsónáǹtì jẹ́ apààlà sílébù* (wo Crystal 2008). Pẹ̀lú oríkì yìí, ìró *w* àti *y* ti bẹ́gbẹ́ mu.

Nínú àbùdá ìsàpèjúwe mẹ́fà tí Owólabí (2013) gbé kalẹ̀, ọ̀kan pàkàkì ni ipò àfàsé wà. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ saájú, ipò méjì ni àfàsé wa, ó lè gbé sókè kí ó dí ọ̀nà èémí tí ó lọ sí imú tàbí kí ó wá sílẹ̀ kí ọ̀nà èémí tí ó lọ sí imú là. Ìró kọ́nsónáǹtì méjì ni a lè pè nígbà tí àfàsé wà sílẹ̀ tí ọ̀nà tí ó lọ sí imú là, tí èémí tí ó gba imú jáde. Àwọn ìró náà ni /n/ àti /m/.

Nígbà tí a pe ìró /n/ àti /m/ àfàsé wá sílẹ̀ tí èémí sì gba imú jáde. A ó wo àwọn ìró yìí ni ẹyọ kọ̀ọ̀kan nípa síṣọ àwọn àbùdá wọn. A ó bẹ̀rẹ̀ àlàyé wa nípa síṣe àpèjúwe ìró /m/.

Ìró /m/ ni orísun èémí ti a lò láti pè é jẹ́ ẹ̀dọ̀-fóró. Nítorí náà, èémí ẹ̀dọ̀-fóró ni a lò láti gbé ìró náà jáde. Irú èémí tí a lò ni èémí àmísóde. Ipò ìkùn ni àlàfo tán-án-ná wà. Ìyẹn ni pé, àwọn tán-án-ná sún mọ́ ara wọn pẹ́kí pẹ́kí dé ibi pé agbára èémí ẹ̀dọ̀-fóró tí ó ń gba ààrín wọn kọjá yóó mú kí wọ́n máa lọ lu ara wọn, kí wọ́n sì tún máa pínyà ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà láàrin ìṣẹ́jú-akàn. Ìgbà tí àwọn tán-án-ná bá ń kọ lu ara wọn, tí wọ́n sì ń pínyà báyìí ni a máa ń sọ pé àwọn tán-án-ná gbọ̀n. Ẹ̀gbọ̀n rìrì tán-án-ná yìí a sì máa fa ariwo tí ó jọ èyí tí a máa ń gbọ́ ní oyin bá ń kùn. Ìkùn yìí ni a pè ni kíkùnyùn. Iró tí a bá sì pè nígbà báyìí ni a mọ̀ sí ìró akùnyùn. Afipe àsúnsí tí a lò ni ètè ìsàlẹ̀. Ètè ìsàlẹ̀ yìí ni ó sún lọ pàdé àfipè akànmọ́lẹ̀. Àfipè Akọ́nmọ́lẹ̀ tí a lò ni ètè. Irú ìdíwọ́ tí ó wà fún èémí nígbà tí a pe ìró yìí ni pé, ọ̀nà èémí sé pátápátá ṣùgbọ́n èémí darí gba imú jáde. Àpẹẹrẹ ibi tí a ti lo kọ́nsónáǹtì náà ni:

| | | |
|---|---|---|
| ọmú | ọmọ | ẹmi |
| mú | mo | máa |

Commented [O.J128]: sì

Commented [O.J129]: kò já gaara

Commented [O.J130]: Dídún

Commented [O.J131]: kò já gaara

Commented [O.J132]: ètè ìsàlẹ̀

Commented [O.J133]: sé pátápátá ní káà ẹnu

Ìró kọ́nsónáǹtì aránmúpè kejì ni /n/. orísun èémí tí a lò ni ẹ̀dọ̀-fóró. Ìyẹn ni pé, èémí ẹ̀dọ́-fóró ni a lò láti gbé ìró náà jáde. Èémí amísóde sì ni a lò làti pe ìró /n/. ìpò ìkùn gẹ́gẹ́ bí a ti ṣàlàyé ti /m/ náà ni a lò fún ìró /n/. Àfipè àsúnsí tí a lò ni iwájú-ahọ́n, nígbà tí àfipè àkànmọ́lè tí a lò ni èrìgì. Ìrú ìdíwọ́ tí ó wà fún èémí ni pé ọ̀nà èémí sé pátápátá, ṣùgbọ́n èémi darí gba imú jáde. Àpẹẹrẹ lílo ìró náà nìyí nínú ọ̀rọ̀ Yorùbá:

inú ọ̀nà ẹnu

ní nà

### 3.2 Fáwẹ́lì Aránmúpè

Gẹ́gẹ́ bí a ti ní kọ́nsónáǹtì aránmúpè náà ni a ní fáwẹ́lì aránmúpè. Àwọn onímọ̀ tilẹ̀ pín gbogbo fáwẹ́lì Yorùbá sí ọ̀nà méjì gbòòrò tí a bá lo ipò tí ti àfàsé wà:

Fáwẹ́lì àránmúpè

Fáwẹ́lì àìránmúpè

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, fáwẹ́lì àránmúpè ni a fẹ́ gbé yẹ̀wò. A kò ní mẹ́nu ba àwọn fáwẹ́lì àìránmúpè rárá. A ti sọ nípa wọ́n nínú LIY 214 tẹ́lẹ̀. ìránniléti gan-an ni ti àránmúpè yóò jẹ́ nítorí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí a ó ṣe lẹ́yìn èyí. Ìmọ̀ inú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí tàbí ìránnilétí yìí yóò wúlò púpọ̀.

Tí a bá fojú fóónù wo àwọn fáwẹ́lì àránmúpè yìí, márùn-ún ni wọn: *an, ọn, ẹn, in* àti *un*. Ṣùgbọ́n ti a bá fojú fóníìmù wò wọ́n, mẹ́rin péré ni wọn. Ìdí ni pé, ìró ọn àti an jẹ́ ẹ̀da fóníìmù kanhun. Àbùdá ìsàpèjúwe ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ni a ó mẹ́nu bà báyìí àti bí wọ́n ṣe jẹyọ nínú ọ̀rọ̀ gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ.

Tí a bá gbé àbùdá ìsàpèjúwe wa òsùwọ̀n mẹ́ta ìsàlẹ̀ yìí, yóò fún wa láti sàpèjúwe àwọn fáwẹ́lì ti a fẹ́ mẹ́nu bà:

**Commented [O.J134]:** sé pátápátá ní káà ẹnu

**Commented [O.J135]:** Ohun tí ìbá dára jù ni kí ẹ kọ gbogbo àwọn àpẹẹrẹ yín ní ìlànà fónẹ́tíìkì níwọ̀n bí ó ti jẹ́ wí pé ìmọ̀ fonọ́lọ́jì ni ẹ fẹ́ fùn àwọn akẹ́kọ̀ọ́.

**Commented [O.J136]:** Ẹ gbìyànjú láti kọ wọ́n ní ìlànà fónẹ́tíìkì dípò ìlànà àkọtọ́

**Commented [O.J137]:** Kò já gaara, ẹ tun kọ

Ipò tí ahọ́n wà

Ipò tí àfàsé wà

Ipò tí ètè wà

**Fáwẹ́lì [ĩ] *in* nínú ọ̀rọ̀ bí ip<u>in</u>, iròy<u>ìn</u>, kẹ́h<u>ìn</u>dé**

Ipò tí ahọ́n wà: iwájú ahọ́n ni ó gbé sókè ju lọ ni ara ahọ́n.

Ipò tí àfàsé wà: àfàsé wá sílẹ̀ láti jẹ́ kí ọ̀nà sí imú là, èémí sì ń gba ẹnu àti imú jáde nígbà kan náà.

Ipò tí ètè wà: ètè méjéèjì rí pẹrẹsẹ, alàfo tí ó gùn, tí ‘p sì rín tín-in-rín wà ní ààrin wọn.

**Fáwẹ́lì [ɛ̃] *ẹn* nínú ọ̀rọ̀ bí ìy<u>ẹn</u>,**

Ipò tí ahọ́n wà: iwájú ahọ́n ni ó gbé sókè jù lọ ní ara ahọ́n

Ipò tí àfàsé wà: àfàsé wá sílẹ̀ láti jẹ́ kí ọ̀nà sí imú là, èémí sì ń gba ẹnu àti imú jáde nígbà kan náà

Ipò tí ètè wà: ètè méjéèjì rí pẹrẹsẹ, alàfo tí ó gùn, tí ‘p sì rín tín-in-rín wà ní ààrin wọn???.

**Fáwẹ́lì [ã] *an* nínú ọ̀rọ̀ bí iy<u>án</u>, ày<u>àn</u>, ak<u>àn</u>, aáp<u>an</u>**

Ipò tí ahọ́n wà: ààrín ahọ́n ni ó gbé sí òkè jù lọ ní ara ahọ́n

Ipò tí àfàsé wà: àfàsé wá sílẹ̀ láti jẹ́ kí ọ̀nà sí imú là, èémí sì ń gba ẹnu àti imú jáde nígbà kan náà

Ipò tí ètè wà: ètè méjéèjì rí pẹrẹsẹ, alàfo tí ó gùn, tí ‘p sì rín tín-in-rín wà ní ààrin wọn???.

**Fáwẹ́lì [ũ] *un* nínú ọ̀rọ̀ bí ikùn, imú, òkun**

Ipò tí ahọ́n wà: ẹ̀yìn-ahọ́n ni ó gbé sókè jù lọ ní ara ahọ́n

Ipò tí àfàsé wà: àfàsé wá sílẹ̀ láti jẹ́ kí ọ̀nà sí imú là, èémí sì ń gba ẹnu àti imú jáde nígbà kan náà

Ipò tí ètè wà: ètè méjéèjì sù roboto, àlàfo sì wà láàrin wọn.

**Fáwẹ́lì [ɔ̃] *ọn* nínú ọ̀rọ̀ bí ibọn, ọpọ́n, ìwọ̀n**

Ipò tí ahọ́n wà: ẹ̀yìn-ahọ́n ni ó gbé sókè jù lọ ní ara ahọ́n

Ipò tí àfàsé wà: àfàsé wá sílẹ̀ láti jẹ́ kí ọ̀nà sí imú là, èémí sì ń gba ẹnu àti imú jáde nígbà kan náà

Ipò tí ètè wà: ètè méjéèjì sù roboto, àlàfo sì wà láàrin wọn.

## 4.0 Ìsọnísókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti mẹ́nu ba ìró kọ́nsónáǹtì àti fáwẹ́lì tí wọ́n jẹ́ àránmúpè. A ṣe àpèjúwe ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ìró àránmúpè yìí. A pààlà ní sókí ìyàtọ̀ nínú ìró àránmúpè àti àwọn ìró tí a sọ di aranmúpè. Ìyẹn ni pé àwọn ìró bẹ́ẹ̀ kìí ṣe àránmúpè fúnra wọn, a sọ wọ́n di aránmúpè ni. Ìyí gan-an ni àfójúsùn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kàn.

Commented [O.J138]: Ibo ni ẹ ti sọ nípa èyí nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí?Ẹ tun wò, bóyá ojú mi sì fò ó ni.

## 5.0 Ìdánwò Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Dáhùn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí

i. Ṣe àpèjúwe ìró kọ́nsónáǹtì aránmúpè

ii. Ṣàlàyé ìró fáwẹ́lì aránmúpè

## 6.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Bámgbóṣé Ayọ̀ (1990) *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ibadan, University Press Ltd

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tíìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

Oyèbádé Francis (2001) Ìgbésẹ̀ àti Ìlànà Fonọ̀lọ́jì Èdè Yorùbá nínú *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá-Èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà*. Olóòtú: Bádé Àjàyí

## ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ ÌKEJÌ: ÌSỌDÌRÁNMÚ

### 1.0 Ìfáárà

Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọjá, a sọ̀rọ̀ nípa àwọn ìró àránmúpè, àmọ́ sá, àwọn ìró kan wà tí ó jẹ́ pé, ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, wọn kìí ṣe ìró àránmúpè, a sọ wọ́n di ìró aránmú ni nítorí agbègbè tí wọ́n ti jẹyọ. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ó ti wo irú àwọn ìró yìí àti sàkání tí wọn ti lè jẹyọ àti irú àwọn ohun tí ó lè fà á.

### 2.0 Èròǹgbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè:

i. Tọ́ka sí àwọn ìró kọ́nsónáǹtì tí a lè sọ di aránmú
ii. Ṣàlàyé sàkání tí a ti lè sọ ìró di aránmú

#### 2.1 Ìdánwò ìdánilẹ́kọ̀ọ́

i. Tọ́ka sí àwọn ìró kọ́nsónáǹtì tí a lè sọ di aránmú
ii. Ṣàlàyé sàkání tí a ti lè sọ ìró di aránmú

### 3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ìgbésẹ̀ fonọ̀lọ́jì ní ibi tí ìró àìránmúpè ti máa ń gbà àbùdá ìránmúpè ni a mọ̀ sí ìsọ-ìró-di-aránmúpè. Àwọn onímọ̀ kan rí i gẹ́gẹ́ bí àrànmọ́, nítorí pé, ìró tí kìí ṣe àránmúpè yìí gba àbùdá ìránmú láti ara ìró mìíràn tí òun náà yóó sì ní àbùdá ìránmúpè gbẹ̀yìn gbẹ́yín. A lè ṣe àpẹẹrẹ ìró kọ́nsónáǹtì ati fáwẹ́lì. A ó kọ́kọ́ wo àpẹẹrẹ ìró kọ́nsónáńtì ná, kí a tó wo àpẹẹrẹ ìró fáwẹ́lì. Ó yẹ kí a fi kúnhun pé ìró aṣèyàtọ̀ ni àwọn ìró àránmúpè náà. Wọn a máa fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀ gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

Commented [O.J139]: ìránmú

Commented [O.J140]: kún un

ìbọ [ìbɔ] ìbọn [ìbɔ̃̀]

wọ́ [wɔ´] wọ́n [wɔ̃́]

àkìyèsí wa ni pé, ìró fáwẹ́lì kan náà àti ìró kọ́nsónáǹtì kan náà ni àpẹẹrẹ àkọ́kọ́ ni, ìyàtọ̀ wọn ni ìránmú. Èyí gan-an ni ó sì fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀. Bẹ́ẹ̀ ni ọ̀rọ̀ rí fún àpẹẹrẹ kejì. Èyí túmọ̀ sí pé, ìró aṣèyàtọ̀ ni ìránmú jẹ́.

Commented [O.J141]: Kò rí bẹ́ẹ̀. Ẹ lo "àbùdá" dípò rẹ̀.

### 3.1.1 Ìsọ-kọ́nsónáǹtì-di-aránmú

Oyelaran (1971) àti Pulley blank (1988:258) ṣàlàyé pé àwọn ìró adún (b.a [r,w,y,h]) a máa gba ìránmú bí wọ́n bá jẹyọ ni àgbègbè tí ìránmú bá wà. Ìyẹn ni pé bí ìró [r], [w], [y] àti [h] bá jẹyọ saájú ìró fáwẹ́lì àránmúpè, wọ́n yóó yípadà di [r̃], [w̃], [ỹ], [h̃] nínú àpẹẹrẹ bí i:

Commented [O.J142]: ìró ìránmú

rìn /rĩ̀/ ==> [r̃ĩ̀]

wọ́n /wɔ̃̀/ ==> [w̃ɔ̃̀]

yún /jṹ/ ==> [j̃ṹ]

hun /hũ/ ==> [h̃ũ]

A ó ṣàkíyèsí pé, àwọn ìró fáwẹ́lì àránmúpé tí wọ́n jẹyọ saájú àwọn ìró adún yìí ni ó fà á tí àwọn ìró kọ́nsónáǹtì yìí náà fi gba àbúdá aránmú. Èyí sì ni a lè pè ni ìsọ-kọ́nsónáǹtì-di-aránmúpè.

### 3.1.2 Ìsọ-fáwẹ̀lì-di-aránmúpè

Èyí ni sísọ ìró fáwẹ́lì tí ó jẹ́ àìránmúpè tẹ́lẹ̀ dí aránmúpè nítorí pé ó gba àbúdá ìránmú yìí lára ìró aránmú tí ó fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ pẹ̀lú rẹ̀. A ó wo àpẹẹrẹ níbi tí ìró fáwẹ́lì ti gba ìránmú láti ara kọ́nsónáǹtì aránmúpè. A ó sì tún wò ó níbi tí wọ́n ti gba ìránmú láti ibi ti ọ̀rọ̀ méjì ti pààlà.

Commented [O.J143]: láàlà ọ̀rọ̀ méjì

#### 3.1.2.1 Ìsọ-fáwẹ̀lì-di-arámúpè-àárín-ọ̀rọ̀

Ìgbésẹ̀ yìí ni sísọ ìró fáwẹ́lì tí ó jẹ́ pé ó jẹ́ àìránmúpè di ránmúpè ní àárín ọ̀rọ̀ kan ní ibi tí ìró kọ́nsónáǹtì aránmúpè ti ń sọ fáwẹ́lì àìránmúpè di aránmúpè. Àpẹẹrẹ ni

| | | | |
|---|---|---|---|
| ọmọ | /ɔmɔ/ | ==> | [ɔmɔ̃] |
| omi | /omi/ | ==> | [omĩ] |
| iná | /ina/ | ==> | [inã́] |
| mu | /mu/ | ==> | [mũ] |

**Commented [O.J144]:** Ṣé ohun tí ẹ ń sọ ni wí pé kò ṣeé ṣe kí fáwẹ̀lì aránmúpè àti kọ́ńsónáǹtì aránmúpè jọ wà pọ̀ ní ìhun ìpìlẹ̀ ni? Kò dà bí ẹni wí pé èrò yẹn máa tọnà nítorí ẹ̀yin pàápàá sọ wí pé àwọn fáwẹ̀lì aránmúpè lè jẹ́ fóníìmù.

A ó ṣe àkíyèsí pé, gbogbo ìró tí ó tẹ̀lé ìró kọ́nsónáǹtì àránmúpè gba ìránmú láti ara wọn, awọn náà sì di ìró aránmu. Èyí ni a lè pè ní àpẹẹrẹ ìsọfáwẹ́lìdàránmúpè.

**Commented [O.J145]:** Tí èrò yẹn bá máa ṣeé fi kọ́ akẹ́kọ̀ọ́, irú àpẹẹrẹ tó yẹ kí a ní ni o+nĩ̀+ ata kó di [anãta], ṣùgbọ́n, ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀. Ohun tó máa ṣeé gbà ni kí a sọ wí pé àwọn fáwẹ̀lì òkè yẹn ti ní àbùdá àdámọ́ fún ìránmú láti ìhun ìpìlẹ̀ ni ní èrò tèmi.

**Ìsọ-fáwẹ́lì-di-arámúpè-ààlà-ọ̀rọ̀**

Awobuluyi àti Oyebade (1995) wòye pé bí a bá pa ìró aránmúpè kan jẹ ni àààlà ọ̀rọ̀ méjì, àbúdá ìránmú kìí sábà di pípajẹ. Àbùdá ìránmú yìí sì máa ń ràn mọ́ ìró fáwẹ́lì tí ó bá tẹ̀lé e. Èyí sáabà máa ń ṣẹlẹ̀ nínú ìhun tí ọ̀rọ̀-ìṣe ti pààlà pẹ̀lú Àpólà Orúkọ. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

| | | | |
|---|---|---|---|
| pín ẹja | /kpĩ ̂ ɛja/ => [kp ̂ ɛja] | => | [kpɛ̃̂ja] |
| rán ẹ̀wù | /rã̂ ɛ̀wù/ => [r ̂ ɛ̀wù] | => | [rɛ̃̂wù] |
| dín ẹja | /dĩ ̂ ɛʤa/ => [d ̂ ɛʤa] | => | [dɛ̃̂ʤa] |

**Commented [O.J146]:** Ṣé ẹ fara mọ́ èrò àwọn onímọ̀ yìí? Yorùbá mélò ló máa ń gbé àwọn àpẹẹrẹ yẹn jáde nínú ìpèdè ojoojúmọ́ wọn? Tí irú ìsọ yẹn bá wáyé, kì í ṣe gbogbo ọmọ Yorùbá ló máa ń sọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ o.

Á ó ṣe àkíyèsí pé ìró fáwẹ́lì ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó jẹ́ fáwẹ́lì àránmúpè ni a pàjẹ nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí. a tún rí i pé, ní ìgbà tí a pa àwọn ìró fáwẹ́lì náà jẹ tán, àbùdá ìránmú àwọn fáwẹ́lì náà kò di pípajẹ. Àbùdá yìí ni ó sì ràn mọ́ fáwẹ́lì àìránmúpè tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ tí ọ̀rọ̀-ìṣe bá pààlà. Èyí mú kí fáwẹ́lì tí kìí ṣe àránmúpè gba àbùdá aránmú gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hànde níbi àbájáde àyọrísí ìgbésẹ̀ ìpajẹ tí ó wáyé.

**Ìsọnísókí**

Èròngbà ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni láti fi hàn pé àwọn fáwẹ́lì kan tí wọ́n jẹ́ àìránmúpè ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ lè gba ìránmú nítorí sàkání tí wọ́n ti jẹ yọ. A ti wo, bí ìró kọ́nsónáǹtì ṣe lè gbá ìránmú àti pàápàá irú àwọn kọ́nsónáǹtì tí a lè sọ di àránmúpè. Bẹ́ẹ̀ náà ni a ṣe fún fáwẹ́lì, a sì fí sákání tí irú ìgbéṣẹ̀ fonọ́lọ́jì bẹ́ẹ̀ ti lè wáyé hàn.

**4.0 Ìdánwò Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

Dáhùn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí

i. Tọ́ka sí àwọn ìró kọ́nsónáǹtì tí a lè sọ di aránmú

ii. Ṣàlàyé sàkání tí a ti lè sọ ìró di aránmú

**5.0 Ìwé Ìtọ́kasí**

Oyelaran, O. O. 1971. Yoruba Phonology. Doctoral dissertation, Stanford University.

Pulleyblank, D. 1988. Vocalic Underspecification in Yoruba. *Linguistic Inquiry* 19.2: 233-270.

**ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ ÌKẸTA: ÌSỌDÀÌRÁNMÚ**

**1.0 Ìfáárà**

Ẹ káàbọ̀ sí ibi ìtẹ̀síwájú ìjíròrò wa nípa ìránmú. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọjá, a wo ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì tí a mọ̀ sí ìsọdìránmú. A wo bí a ṣe lè sọ ìró kọ́nsónáǹtì tí kìí ṣe àránmúpè ṣe lè gba àbùdá ìdámú. Ìdí pàtàkì tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé àwọn ìró máa ń wùwà bí agbègbè wọn bá ṣe rí. A ṣe àfihàn àwọn ìró kọ́nsónáǹtì tí wọ́n lè gba àbùdá ìránmú yìí. A tẹ̀síwájú láti wo bí àwọn fáwẹ́lì tí wọ́n jẹ̀ àìránmúpè gẹ́gẹ́ bí àbùdá wọn sẹ lè gba ìránmú. A mẹ́nu ba sàkáni tí irú ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì yìí ti lè wáyé.

Commented [O.J147]: dìránmú

Commented [O.J148]: paradà

Commented [O.J149]: Ẹ yọ́ kúrò

Ìdàkejì ìgbésẹ̀ tí a wò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọjá ni a fẹ́ wò báyìí. A fẹ́ wo bí àwọn ìró àránmúpè ṣe lè si àìránmúpè nípa sísọ àbùdá ìránmú wọn.

Commented [O.J150]: di

## 2.0 Èròǹgbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè:

i. Ṣàlàyé ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì ìsọdàìránmú pẹ̀lú àpẹẹrẹ
ii. Tọ́ka sí ẹ̀yà ìsọdàìránmú tí ó mọ̀

### 2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Gbìyànjú láti dàhun ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí

i. Pẹ̀lú àpẹẹrẹ, ṣàlàyé ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì ìsọdàìránmú
ii. Tọ́ka sí ẹ̀yà ìsọdàìránmú tí o mọ̀

## 3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì ní ibi tí ìró aránmúpè yóó ti sọ àbùdá ìránmú rẹ̀ nù tí yóó sì di ìró àìránmúpè ni a mọ̀ sí ìsọródàìránmúpè. Ìpajẹ àti àrànmọ́ ni ó sábà máa ń fa ìgbésẹ̀ yìí. A ó wa ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì yìí lẹ́yọ kọ̀ọ̀kan bí wọ́n ṣe máa ń fa ìró àránmúpè sí àìrànmúpè.

#### 3.1.1 Ìsọdàìránmúpè aláràǹmọ́

Ìgbésẹ̀ yìí má ń wáyé nínú mọ́fíìmù kan. Ìpajẹ ni yóó kọ́kọ́ wáye. Lẹ́yìn ní àrànmọ́ yóó wá ṣilẹ̀. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ

èǹìyàn = /ènĩ̀jã̀/ = [èĩ̀jã̀] ==> [èèjã̀]
esinsin = /esĩ̄sĩ̄/ = [eĩ̄sin] ==> [eesĩ̄]
egúngún = /egṹgṹ/ = [eṹgṹ] ==> [eégún]

A ó ṣàkíyèsí pé ìpajẹ́ kọ́nsónáǹtì ni ó kọ́kọ́ ṣẹlẹ̀. Èyí mú kí àwọn fawẹ́lì àránmúpè àti àìrànmúpè fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́, lẹ́yìn náà ni fáwẹ́lì àìránmúpè sọ fawẹ́lì àránmúpè di irú ara rẹ̀ tó bẹ́ẹ̀ tí ìró àránmúpè sọ ìránmú rẹ̀ nù, tí ó sì di àìránmúpè gẹ́gẹ́ bí a ti rí i nínú àpẹẹrẹ òkè yìí.

Ó tún ṣe é ṣe kí irú ìgbésẹ̀ yìí wáyé láààrín mọ́fíìmù méjì nínú ọ̀rọ̀ bí i:

ọdúnọdún =/ɔdũ̂ɔdũ̂/ =[ɔdɔɔdũ̂]

ọgbọ́nọgbọ́n = /ɔgbɔ̃̌ɔgbɔ̃̌/ = [ɔgbɔɔgbɔ̃̌]

ọ̀kanọ̀kan =/ɔkã̂ɔkaɔ/ = [ɔkɔɔkã̌]

Ni ibi yìí, a ṣàkíyèsí pé, kò sí ìpajẹ kankan bí ó tilẹ̀ wù kó mọ. Ìgbésẹ̀ àrànmọ́ nìkan ni ó wáyé. Ìró àìránmúpè sì lo agbara àrànmọ́ rẹ̀ láti sọ ìró àránmúpè di irú ara rẹ̀ tó bẹ́ẹ̀ tí ìró àránmúpè sọ àbùdá ìránmú rẹ̀ nù.

Ìgbésẹ̀ ìsọdàìránmúpè tún lé wáyé lẹ́yìn àwọn ọ̀rọ̀ kan. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ bí i:

rà ũ̂ ==> rà á

tà ũ̂ ==> tà á

kà ũ̂ ==> kà á

ʃe fũ̂ mi = ʃe ũ̂ mi ==> ʃe é mi

jà fũ̂ mi = jà ũ̂ mi ==> jà á mi

Ohun tí ó fojú hàn ni pé, gbogbo ibi tí ìsọdàìránmúpè ti wáyé nínú àpẹẹrẹ òkè yìí ni a ti rí ìfarahàn àrànmọ́.

### 3.1.2 Ìsọdàìránmúpè onípajẹ

Ìgbésẹ̀ yìí ni ibi tí a ti sọ ìránmú nu nípa ìpàrójẹ. Èyí lè wáyé nínú ẹyọ ọ̀rọ̀ tàbí láàárín àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀.

**Commented [O.J151]:** Ṣé kì í ṣe àrànmọ́ lásán ni èyí? Kí ló dé tí a fi rò wí pé ìsọdàìránmú wáyé ní bí /eĩ̂sĩ̂/ ṣe di [eesĩ̂]? Ṣé ẹ mọ̀ wí pé lára àbùdá apàààlà fún /ĩ̂/ ni [+Aṣesílébù], [-Aṣekọ́ńsónáǹtì], [+Òkè], [+Iwájú], [-Roboto], [+Ìránmú]? Nítorí náà, bí /ĩ̂/ ṣe di /e/ kò ju wí pé ó sọ gbogbo àbùdá apàààlà rẹ̀ nù pátápátá tó sì gbé gbogbo àbùdá ti /e/ wọ̀.

**Commented [O.J152]:** Àlàyé tí a ṣe lóke náà ni a lè ṣe níbí. Tí àlàyé yín yìí bá máa wáyé, ohun tí àmújáde yẹn kó jẹ́ b.a. ni [rà ú]

**Commented [O.J153]:** Lójú tèmi, bí ẹni fi àkókò ṣòfò, bí ẹní fi òfin fonọ́lọ́jì ṣòfò àti bí ẹni tí ó ń wè gèlè fúnrọ́ ni èrò ìsọdàìránmú yẹn. Ohun tó rọrùn, tó jẹ́ òótọ́, tó sì lọ geerege ní kí a sọ pé àrànmọ́ pọ́ńbélé ló wáyé nínú àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyẹn.

oní + èdè = elédè

oní + ata = aláta

oní + ɛʤa = ɛlɛ́ʤa

**Commented [O.J154]:** Ṣé kò yẹ kí ẹ kọ èyí ní ìlànà fónẹ́tîìkì kí akẹ́kọ̀ọ́ lè ri pé pípa tí a pa /ĩ̀/ jẹ ló mú kí ó pọndandan kí /n/ sọ àbùdá ìránmú rẹ̀ nù?

kò yẹ kí á gbàgbé pé ìró áránmúpè [í] ni a pajẹ nínú àpẹẹrẹ òkè yìí. Ní ìwọ̀n ìgbà tí àrànmú ti kúró ní àgbegbe tí ìró [n] ti jẹyọ, ìró náa yí padà di irú rẹ̀ tí kìí ṣe aránmúpè (ìró [l]). Èyí gan-an sì ni ìsọdàìránmú tí ó wà nínú àwọn àpẹẹrẹ náà. Àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì mìíràn tí ó wáyé láti ni àyọrísí àbájáde òke yìí ni àrànmọ́, ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò.

Bí a bá tún wo àpẹẹrẹ bí i

| | | |
|---|---|---|
| fũ̂ olú kɛ́ | = f olú kɛ́ | ==> fólúkɛ́ |
| fũ̂ olú ʃɔ́ | = f olú ʃɔ́ | ==> fólúʃɔ́ |
| bù kũ̂ ɔlá | = bù k ɔlá | ==> bùkɔ̀lá |

Nínú àpẹẹrẹ yìí, ìgbésẹ̀ ìpajẹ nìkan ni ó wàyé, ìró aránmúpè sì ni a pajẹ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ohun orí ìró ti a pajẹ ni a fi ààyè gba lórí ìró mìíràn.

A tún lè wo àpẹẹrẹ bí i:

| | |
|---|---|
| mũ̂ owó | ==> mówó |
| fũ̂ ewúrɛ́ | ==> féwúrɛ́ |
| fũ̂ àgùtã̂ | ==> fágùtã̂ |

ìpajẹ ìró aránmú ló mú ìránmú kúrò nínú àwọn ìpèdè òkè yìí.

**4.0 Ìsọnísókí**

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ṣàlàyé bí ìró àrámúpè ṣe lè dí àìránmúpè. A sọ awọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì tí ó máa ń fa èyí; pàápàá ìparóję àti àrànmọ́ jẹ́ pàtàkì nínú àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jè náà. A pè àw\n pigbésẹ̀ náà ní ìsọdàìránmúpè aláràǹmọ́ àti onípajẹ. A sì fi ọ̀pọ̀lọpọ̀ àpẹẹrẹ gbe ọ̀rọ̀ wa lẹ́sẹ̀.

## 5.0 Ìdánwò Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

i. Pẹ̀lú àpẹẹrẹ, ṣàlàyé ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì ìsọdàìránmú

ii. Tọ́ka sí ẹ̀yà ìsọdàìránmú tí o mọ̀

## 6.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Oyelaran, O. O. 1971. Yoruba Phonology. Doctoral dissertation, Stanford University.

Pulleyblank, D. 1988. Vocalic Underspecification in Yoruba. *Linguistic Inquiry* 19.2: 233-270.


Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkẹrin: ọ̀rọ̀ àyálò

YOR341 PHONOLOGY OF YORUBA II (2 CREDIT UNITS C)

A detailed and analytical examination of the phonological processes in Yoruba: assimilation, nasalisation, epenthesis, vowel harmony, vowel elision, length, tonal processes, and syllable structure.

**Commented [O.J155]:** Ó yẹ kí ẹ tú èyí sí Yorùbá o